**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA (NOUN)**

# YOR 318: THOUGHTS AND BELIEFS OF THE YORUBA PEOPLE
# ÈRÒ ÀTI ÌGBÀGBỌ́ ÀWỌN YORÙBÁ

**LÁTI ỌWỌ́**

**ABÍDÈMÍ OLÚṢỌLÁ BỌ́LÁRÌNWÁ**
**B.A (Hons.), M.A. Ph.D (Ìbàdàn)**

**Department of Linguistics and African Languages, University of Ibadan, Ibadan, Nigeria.**

**Course Content: Thoughts and beliefs of the Yorùbá people (3 Credit Units C)**

**Course title and description:YOR 318: A detailed and analytical study of the thought, belief and religious systems of the Yorùbá people**

**Course Writer: Dr Abidemi O. Bolarinwa**

**Course Editor: Dr O.O. Adekọla**

## ÀKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ

**MÓDÙ KÍNNÍ: ÌGBÀGBỌ́ ÀWỌN YORÙBÁ TÓ FARAHÀN NÍNÚ ẸSÌN WỌN**

Ìpín Kìnní: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Olódùmarè

Ìpín Kejì: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Ìṣẹ̀dá Ayé

Ìpín Kẹta: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Àwọn Òrìṣà

`Ìpín Kẹrin: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Àwọn Ẹ̀mí Àìrí

Ìpín Karùn-ún: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Àsẹ̀yìnwáyé àti Abàmì Ẹ̀dá

**MÓDÙ KEJÌ: ÌGBÀGBỌ́ ÀWỌN YORÙBÁ TÍ KÒ NÍÍ ṢE PẸ̀LÚ ẸSÌN WỌN**

Ìpín Kìnní: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Ọmọ

Ìpín Kejì: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Ẹwà

Ìpín Kẹta: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Owó

Ìpín Kẹrin: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Ọ̀rẹ

Ìpín Karùn-un: Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Ẹ̀san

**MÓDÙ KẸTA: ÈRÒ ÀWỌN YORÙBÁ TÓ JẸYỌ NÍNÚ ÀṢÀ WỌN**

Ìpín Kìnní: Èrò Yorùbá Nípa orúkọ

Ìpín Kejì: Èrò Yorùbá Nípa Ìlera

Ìpín Kẹta: Èrò Yorùbá Nípa Orí

Ìpín Kẹrin: Èrò Yorùbá Nípa Ikú

Ìpín karùn-ún: Èrò Yorùbá Nípa Àwọn Ọba Alayé

## Ìfáàrà Sí Kọ́ọ̀sì Yìí

### Ìfáàrà

Ẹ̀yà kan pàtàkì tí kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ séyìn ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni àwọn Yorùbá jẹ́, àwọn tí à ń pè ní Yorùbá ní àwọn ẹ̀yà tí ó ń sọ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí èdè abínibí wọn. Yorùbá jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn ẹ̀yà tó ń gbé ní apá ìwọ̀ oòrùn Áfíríkà. Ààlà ilẹ̀ wọn ní apá Àríwá ni ilẹ̀ àwọn Ìbàrìbà (Borgu), odò ọya àti apá kan ilẹ̀ àwọn Tápà, nígbà tí ààlà ilẹ̀ wọn ní apá Ìlà oòrùn jẹ́ odò ọya, ilẹ̀ àwọn Ìgbìrà, Ilẹ̀ Ìbíní àti ti àwọn Ìṣẹ̀kírì. Ní Gúsù, Òkun Àtìláńtíkì àti díẹ̀ nínú ilẹ̀ Èègùn ni ààlà àwọn Yorùbá. Ilẹ̀ àwọn Ìdàọ̀mì ni ó sì jẹ́ ààlà ilẹ̀ Yorùbá ní ìwọ̀ oòrùn. Àwọn Yorùbá pín sí oríṣìíríṣìí ẹ̀yà, lára àwọn ẹ̀yà yìí ni a ti rí Ọ̀yọ́, Ẹ̀gbá, Àkókó, Àwórì, Ìjẹ̀bú, Ìjẹ̀ṣà, Ìgbómìnà, Èkìtì, Ẹ̀gbádò, Yewa, Ìkálẹ̀, Ìlàjẹ àti Ìyàgbà. Gbogbo àwọn ẹ̀yà tí a dárúkọ wọ̀nyí ni a lè rí ní ìpínlẹ̀ Ọ̀yọ́, Ọ̀ṣun, Ògùn, Èkó, Kwara, Òǹdó, Èkìtì, Kogí àti Ẹdó.

Gbogbo ẹ̀yà kọ̀ọ̀kan tí ó wà láwùjọ ni wọ́n ní ìgbàgbọ̀ àti èrò tí ó rọ̀ mọ́ ìgbe ayé wọn. Àwọn Yorùbá pàápàá gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà kàn náà máa ń ṣe àfihàn èrò àtí ìgbàgbọ́ wọ́n nínú ìwà àti ìṣe wọn. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé òrìṣà tí a kò bá fi ojú ọmọdé mọ̀ ṣe ni ó máa ń parun gbẹ̀yìn. Lọ́nà àti dènà èyí, látí kékeré ni àwọn Yorùbá ti máa ń rí i dájú pé àwọn ọmọ wọn mọ̀ nípa èrò àti ìgbàgbọ́ wọn tí wọ́n sì ń ṣàmúlò rẹ̀ nígbà gbogbo.

Orúkọ kọ́ọ̀sì yìí ní èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá, módù mẹ́ta ni a pín kọ́ọ̀sì yìí sí, bẹ́ẹ̀ ni a pín módù kọ̀ọ̀kan sí ìpín márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Nínú módù kìnní ni a o ti ṣe àlàyé nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá èyí tí ó níí ṣe pẹ̀lú ẹ̀sìn wọn. Ní ìpín kìíní a sọ̀rọ̀ nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Olódùmare. Ní ìpín kejì ní abẹ́ módù kíìní yìí kan náà ni a ti tú iṣu dé ìsàlẹ̀ ìkòkò nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ìṣẹ̀dá ayé. Ìpín kẹta ni a ti walẹ̀jìn nípa àwọn òrìṣà ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìpín kẹrin àti ìkarùn-ún ni a ti ṣe àlàyé kíkún nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀mí àìrí, àsẹ̀yìnwáyé àti abàmì ẹ̀dá

Nínú módù keji ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìgbàgbọ́ Yorùbá tí kò níí ṣe pẹ̀lú ẹ̀sìn wọn. Ní ìpín kínní a sọ bí ọmọ ṣe jẹ́ pàtàkì tó láwùjọ Yorùbá, ohun tí ó lè ṣe okùnfà àìrọ́mọbí àti àwọn aájò tí àwọn baba ńlá Yorùbá máa ń ṣe láti dènà àìrọ́mọbí, èyí nìkan kọ́, a tún ṣàlàyé àwọn ohun tí Yorùbá fi ọmọ wé, èyí tí ó fi pàtàkì ọmọ àti èrò Yorùbá nípa ọmọ

hàn síwájú sí i. Bákan náà ni a sọ díẹ̀ lára orúkọ tí Yorùbá máa ń sọ ọmọ èyí ní àwọn orúkọ tí o fi èrò àti ìgbàgbọ́ wọn nípa ọmọ hàn.Ní ìparí, a ṣe àlàyé lórí ìtọ́jú ọmọ ní àwùjọ Yorùbá. Ìpín kejì ní abẹ́ módù kejì ni a ti ṣe àgbéyẹ̀wò pàtàkì ẹwà ní ilẹ̀ Yorùbá. A tún ṣàlàyé kíkún nípa ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín ẹwà àti ìwà, oríṣìí ọ̀nà tí a lè gbà gbé ẹwà yọ. Bákan náà, a wó ìwòye Yorùbá nípa ẹwà nípa ṣíṣe àlàyé ojú tí wọ́n fi ń wo ẹni tí ó bá lẹ́wà. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe àyẹ̀wò oríṣìíríṣìí ìpèdè tí ó jẹmọ́ ẹwà. Nínú ìpín kẹta lábẹ́ módù kejì ni a ti ṣe àyẹ̀wò ohun tí Yorùbá ń lò fún owó ṣáájú kí àwọn Òyìnbó tó dé. A sọ̀rọ̀ nípa èrò Yorùbá nípa owó àti ihà tí wọ́n kọ sí níní àti àìní owó ẹ̀dá. Bákan náà, a wó ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà yá owó àti bí wọ́n ṣe le rí owó. Ìpín kẹrin nínú módù kejì ni a ti ṣe àlàyé nǹkan tí ọ̀rẹ́ jẹ́ àti oríṣìíríṣìí ọ̀rẹ́ tí ó wà pẹ̀lú ipa tí ọ̀rẹ́ ń kó nínú ayé ẹ̀dá. Bákan náà a ṣe àfìhán èrò àwọn Yorùbá nípa yíyan ọ̀rẹ́ àti irúfẹ́ ọ̀rẹ́ tí a gbọ́dọ̀ gbà láàyé. Ìpín yìí tún ṣàfihàn àbùdá ọ̀rẹ́ àti bí kò ṣe yẹ kí a nífẹ̀ẹ́ ọ̀rẹ́ ju ẹbi lọ nítorí lọ́jọ́ tí ọ̀rẹ́ kítíkítí bá kú, iyèkan kàtàkàtà ni yóó kù. Ìpín karùn-ún módù keji ni a ti ṣàfihàn ẹ̀san gẹ́gẹ́ bí i èrèdí ìṣe ènìyàn ní awùjọ. Bákan náà ni a tọ́ka sí i bí Olódùmarè ṣe jẹ́ Ọba ẹlẹ́san àti bí ó ṣe jẹ́ pé gbogbo ohun tí ènìyàn bá ṣe ló ní èrè. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé àṣegbé kan kò sí àti pé àṣepamọ́ ló wà.

Módù kẹta dá lé èrò àwọn Yorùbá kan. Ìpín kínní módú kẹta ni a ti sọ̀rọ̀ nípa bí orúkọ ṣe jẹ́ pàtàkì ní ilẹ̀ Yorùbá. A ṣàlayé pé ọjọ́ tí a bá fẹ́ sọ ọmọ ní orúkọ ni a máa ń ṣe ayẹyẹ ìkómọjáde. Èyí nìkan kọ́ nítori orúkọ Yorùbá tí ó pọ̀, ní a ṣe pín wọn sí ọ̀nà méjọ a sì ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí àwọn orúkọ Yorùbá wọ̀nyí àti ìtumọ̀ wọn. Lábẹ́ ìpín keji ní módù kẹta ni a ti ṣàlàyé kíkún lórí ojú tí àwọn Yorùbá fi ń wo ìlera. A yiiri wò ohun tí ìlera túmọ̀ sí àti bí a ṣe lè wà ní ìlera àti àwọn ohun tí ó le fún ènìyàn ní ìlera. Orí jẹ́ ohun kan pàtàkì láàárín àwọn Yorùbá. Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí ohun ti wọn lè sọ láìsọ̀rọ̀ nípa orí, nínú ìpín kẹta lábẹ́ módù kẹta ni a ti sọ pàtàkì orí láàárín àwọn Yorùbá, ìtumọ̀ orí, àkúnlẹ̀yàn àti àkúnlẹ̀gbà, àti àwọn ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ nípa orí. Nínú ìpín kẹrin nínú módù kẹta, a jíròrò nipa èrò àwọn Yorùbá nípa ikú, a wo ohun tí à ń pè ní ikú, ìhà tí àwùjọYorùbá kọ sí ikú, lẹ́yìn èyí, a wo bí wọ́n ṣe ń palẹ̀ òkú mọ́ ní ilẹ̀ Yorùbá. Nínú ìpín karùn-ún lábẹ́ módù karùn-ún, a ṣàyẹ̀wò àwọn Ọba alayé ní ilẹ̀ Yorùbá. A wo irúfẹ́ ènìyàn tí àwọn Ọba alayé

jẹ́ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá, bi a ṣe ń j'Ọba nílẹ̀ Yorùbá àti ipò àwọn Ọba láàárín ìlú àti àwùjọ lápapọ̀.

## ÀFOJÚSÙN KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ

Àfojúsùn Kọ́ọ̀sì yìí ni láti rí i pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ wọ̀nyí mọ nípa ọ̀kanòjọ̀kan àwọn èrò àti ìgbagbọ́ àwọn ẹ̀yà Yorùbá tí ó jẹ mọ́ àṣà àti ìṣe àwọn baba-ńlá wọn. Èyí ni yóò jẹ́ kí wọ́n lè sọ̀rọ̀ ní àwùjọ àwọn onímọ̀ níbikíbi tí wọ́n bá bá ara wọn lọ́jọ́ iwájú.

Èyí nìkan kọ́, akẹ́kọ̀ọ́ yóò le ní ìmọ̀ kíkún nípa àwọn ìgbàgbọ́ Yorùbá èyí tí ó ń fi wọ́n hàn gẹ́gẹ́ bí ẹ̀yà ati èdè kan. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò tún le mọ pàtàkì àṣà Yorùbá àti bí àwọn oríṣìíríṣìí èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá wọ̀nyí ṣe níyì tó ní àwùjọ àgbáyé gẹ́gẹ́ bí ó ṣe jẹyọ nínú àwọn onírúurú ìgbé ayé Yorùbá. A tún fẹ́ kí akẹ́kọ̀ọ́ mọ àwọn ìyàtọ̀ pẹ́ẹ́ pẹ̀ pẹ́ tí ó wà nínú onírúurú èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá wọ̀nyi àti ipa wọn láwùjọ Yorùbá

Àwọn akékọ̀ọ́ yóò tún mọ̀ nípa àwọn èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá tí ó níí ṣe pẹ̀lú ẹ̀sìn wọn àti èyí tí kò ní ohunkóhun ṣe pèlú ẹ̀sìn, a tún ṣe àgbéyẹ̀wò bí àwọ́n èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá wọ̀nyí ti gbilẹ̀ tó láàrin àwùjọ́ Yorùbá láti ìgbà ìwásẹ̀ títí di àkókò tí a wà yìí. Akẹ́kọ̀ọ́ yóò le mọ pé oríṣìíríṣìí èrò àti ìgbàgbọ́ ni àwọn Yorùbá ní àti pé àwọn èro àti ìgbàgbọ́ tí a ń sọ wọ̀nyí ní í ṣe pẹ̀lú ìdàgbàsókè àti ìgbé-ayé àwọn Yorùbá ni.

## OJÚṢE AKẸ́KỌ̀Ọ́

Bí olùkọ́ ṣe ní ojúṣe tirẹ̀ láti fi yé akẹ́kọ̀ọ́ yékéyéké, kí wọ́n sì ní ìmọ̀ tí ó péye lórí onírúurú èrò àtí ìgbàgbọ́ Yorùbá tí ó máa ń jẹyọ nínú ìwà àti ìṣe wọn, bẹ́ẹ̀ ni akẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ fi ara balẹ̀ láti gba ìmọ̀ kún ìmọ̀ lọ́dọ̀ àwọn aṣaájú wọn nínú ìmọ̀, àṣà àti ìṣe Yorùbá.

Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ múra láti ka àwọn ìwé tí olùkọ́ tọ́ka sí nínú ìwé ìléwọ́ yìí àti pé wọ́n ní láti máa wá ìdáhùn sí gbogbo àwọn ìbéèrè tí a gbé síwájú wọn. Akẹ́kọ̀ọ́ kò gbọdọ̀ ṣe ọ̀lẹ nínú akitiyan rẹ̀ láti ní ìtẹ̀síwájú nínú èrò àti ìgbàgbọ́ Yorùbá pàápàá ní àkókò ọ̀làjú tí a wà yìí.

Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ fi ara balẹ̀ láti gbọ́ ìtọ́sọ́nà àwọn olùkọ́ rẹ̀ kí o lè ṣe kóríyá nínú ẹ̀kọ́ rẹ̀. Akẹ́kọ̀ọ́ kò gbọdọ̀ rojú láti siṣẹ́, ó gbọdọ̀ jẹ́ ẹni tí ó setán láti wá ìmọ̀ kún ìmọ̀ kò sì gbọdọ̀ jí iṣẹ́ oníṣẹ́ wò tàbí kí ó da iṣẹ́ oníṣẹ́ kọ torí èyí kìí ṣe ìwà tó tọ̀nà.

Ojúṣe mìíràn ní pé akẹ́kọ̀ọ́ ni láti wá àwọn ìwé tí wọ́n kọ fún un, kí ó sì kà wọn dáadáa. Bí kò bá le fi owó rẹ̀ rà wọ́n, kí ó máa lọ sí ilé ìyáwèé-kàwé tí ó ti le rí àwọn ìwé wọ̀nyí kà. Torí Yorùbá bọ̀, wọ́n ní: “Ọgbọ́n ọlọ́gbọ́n ni kìí jẹ́ kí á pe àgbà ní wèrè”.

Akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ máa dá iṣẹ́ àmúrelé tàbí iṣẹ́ àmúṣe rẹ̀ padà ní àkókò tí ó yẹ, bẹ́ẹ̀ ni akẹ́kọ̀ọ́ gbọdọ̀ fi ara hàn ní àsìkò ìdánwò àṣekágbá láìṣe àwáwí kankan.

Ní ìparí, kí akẹ́kọ̀ọ́ máa bèèrè àwọn ìbéèrè tí kò yé e nípa bíbá olùkọ́ rẹ̀ sọ̀rọ̀ lóòrèkóòrè torí abéèrè kan kìí sìnà.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N**

Iṣẹ́ ṣíṣe ti olùkọ́ yóò fi ọwọ́ sí àti ìdánwò alákọsílẹ̀ jẹ́ àwọn oríṣìí ọ̀nà ìgbéléwọ̀n méjì ti ó wà, tí a ó sì máa ṣàmúlò rẹ̀ fún kóọ̀sì yìí. Iṣẹ́ àmúṣe níí ṣe pẹ̀lú iṣẹ́ tí yóò jẹ́ dídájọ ní ìbámu pẹ̀lú àsìkò àdápadà rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí olùkó bá ṣe lànà rẹ̀ sílẹ̀, ìdá ogbọ́n nínú ọgọ́rùn-ún ni iṣẹ́ àmúṣe yìí jẹ́. Ìgbàgbó wa ni pé ìmọ̀ tí o bá gbà nínú ẹ̀kọ́ yìí yóò wúlò gidigidi fún iṣẹ́ àmúṣe àti àṣeyege rẹ nínú ìdánwò.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N TÍ OLÙKỌ́ YÓÒ MÁÀKÌ (TMA)**

Iṣẹ́ ṣíṣe wà ní òpin ìpín kọ̀ọ̀kan, a ń fọkànsí pé kí akẹ́kọ̀ọ́ wá ìdáhùn sí gbogbo àwọn ìbéèrè tó wà níbẹ̀. Gbogbo àwọn iṣẹ́ ṣíṣe yìí ni a ó yẹ̀wò tí máàkì yóò sì wà fún mẹ́ta tí ó bá dára jùlọ. Yóò jẹ́ eyọ kan ni módù kan. Módù mẹ́ta ni a pín kọ́ọ̀sì yìí sí, bẹ́ẹ̀ ni a pín módù kọ̀ọ̀kan sí ìpín márùn-ún ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀.

Iṣẹ́ ṣíṣe àti ìgbéléwọ̀n yìí ni o máa fi ṣọwọ́ papọ̀ sí olùkọ́ ṣáájú ọjọ́ tí a bá dá. Bí ìdí pàtàkì bá wa láti má ṣe dá iṣẹ́ náà jọ kí ọjọ́ yìí tó pé, ó ní látí fi tó olùkọ́ létí ẹni tí ó le pinnu láti sún ọjọ́ náà síwájú. Ìdí pàtàkì ni ó lè mú kí olùkọ́ ṣe bẹ́ẹ̀.

**ÌDÁNWÒ ÀṢEKÁGBÁ ÀTI ÒṢÙNWỌ̀N**

Ìdánwò àṣekágbá fún kọ́ọ̀sì yìí 'Èrò àti Ìgbàgbọ́ Yorùbá' jẹ́ ààdọ́rin máàkì (70%) láàrin wákàtí méjì, àwọn iṣẹ́ ṣíṣe àti ìgbéléwọ̀n olùkọ́ yóò jẹ́ ìfòyegbe irú ìbéèrè tí o máa ba pàdé nínú ìdánwò.Gbogbo ìpín kọ̀ọ̀kan kọ́ọ̀sì yìí ló yẹ ní gbígbọ̀n yẹ́bẹ́yẹ́bẹ́. O lè lo àǹfààní àsìkò tó wà láàrin ìparí kọ́ọ̀sì yìí sí ìgbà tí ìdánwò yóò bẹ̀rẹ̀ láti ṣe àtúnyẹ̀wò ẹ̀kọ́, wíwá ìdáhùn sí àwọn ìbéèrè lábẹ́ iṣẹ́ ṣíṣe àti èyí tí olùkọ́ yóò yẹ̀wò yóò ṣe ìrànlọ́wọ́ dáadáa fún ọ gẹ́gẹ́ bí akẹ́kọ̀ọ́.

**ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ**

Àtẹ ìsàlẹ̀ yìí ṣàlàyé bí máàkì gbígbà yóò ṣe wáyé.

| **Ìgbéléwọ̀n** | **Máàkì** |
|---|---|
| Isẹ́ àmúṣe 1-3<br>Mẹ́ta tó ba dára jù ni a ó ṣe àkọsílẹ̀ máàkì rẹ̀. | Ogójì (30%) |
| Ìdánwò àṣekágbá | Ọgọ́ta (70%) |
| Àròpọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%) |

**MÓDÙ KÍNNÍ**

**Ìfáárà:**

Nínú módù yìí ni a o ti gbọ́ àlàyé nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá èyí tí ó níí ṣe pẹ̀lú ẹ̀sìn wọn. Ní ìpín kìnní a sọ̀rọ̀ nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa Olódùmare. Ní ìpín kejì, ní abẹ́ módù kííní yìí kan náà ni a ti tú iṣu dé ìsàlẹ̀ ìkòkò nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ìṣẹ̀dá ayé.Ìpín kẹta ni a ti walẹ̀jìn nípa àwọn òrìṣà ní ilẹ̀ Yorùbá. Ìpín kẹrin àti ìkarùn-ún ni a ti ṣe àlàyé kíkún nipa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀mí àìrí, àsẹ̀yìnwáyé àti abàmì ẹ̀dá.

**ÌPÍN ḰNNÍ: ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍPA OLÓDÙMARÈ**

**Ìfáárà:**

Nínú ìpín yìí ni a ó ti gbọ́ àlàyé nípa Olódùmarè. Akẹ́kọ̀ọ́ yóó ní òye kíkún nípa ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ orúkọ Olódùmarè láti inú àwọn ìtàn àtẹnudétí tí a máa ń gbọ́ lẹ́nú àwọn babańlá wa àti lẹ́nu àwọn àgbà àwùjọ Yorùbá lóde òní.

Bákan náà ni a ó sọ nípa oríṣìíríṣìí ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè jẹ́ a ó tún mẹ́nu ba díẹ̀ lára orúkọ Olódùmarè àti oríkì Rẹ̀.

Àkòónú

1.0 Ìfáárà

2.0 Èròǹgbà

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa Olódùmarè

4.2 Ìtàn ti ó rọ̀ mọ́ ìtumọ̀ orúkọ Olódùmarè

4.3 Ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè jẹ́

4.4 Díẹ̀ lára Orúkọ àti Oríkì Olódùmarè

5.0 Ìsọníṣøkí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Ǹjẹ́ Yorùbá gbà pé Olódùmarè wà? Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ó ti mọ̀ ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa Olódùmarè, ohun tí Olódùmarè jẹ́, orúkọ Olódùmarè àti oríkì Rẹ̀.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, èròǹgbà wa ni pé akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

- Ṣàlàyé ẹni tí Olódùmarè jẹ́
- Sọ oríṣirííṣi orúkọ àti oríkì Olódùmarè
- Ṣàlàyé àwọn ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ nípa Olódùmarè.

## 3.0 Ibéèrè Iṣaájú

i. Báwo ni Yorùbá ṣe mọ̀ pé Olódùmarè wà?

ii. Ṣàlàyé mẹ́rin lára ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè jẹ́

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa Olódùmarè

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹnìkan wà tí ó ń jẹ́ Olódùmarè àti pé Olódùmarè yìí ni ọba gbogbo ayé tí ó dá ohun gbogbo tí ó wà ní ayé àti ọ̀run. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá tún ni pé kò sí ohun tí Olódùmarè kò mọ̀, kò sí ohun tí kò rí, bẹ́ẹ̀ ni kò sì sí ohun tí kò le ṣe.

Lọ́nà átifí títóbi Olódùmarè hàn, àwọn Yorùbá fún Olódùmarè ní ẹgbàágbèje orúkọ àti ẹgbẹ̀fà oríkì èyí tí wọn fi máa ń bu ọla fún un, nínú àwọn orúkọ àti oríkì tí àwọn Yorùbá fún Olódùmarè yìí ní a ti máa ń rí ipá Rẹ̀, ìṣe Rẹ̀ àti ọlánlá Rẹ̀. Gbogbo àwọn

orúkọ Olódùmarè àti oríkì Rẹ̀ tí a ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ yìí jẹyọ láti inú ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa bí Olódùmarè ṣe jẹ́ àti bí ó ṣe tó, èyí fihàn dájúdájú pé àwọn Yorùbá gbà pé Olódùmarè wà.

### 4.2 Ìtàn tí ó rọ̀ mọ́ ìtumọ̀ orúkọ Olódùmarè

Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ̀ pé, kò sí orúkọ tí Yorùbá máa ń sọ ọmọ tí kò ní ìtumọ̀, gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀ ni Olódùmarè ní ìtumọ̀ láàrin àwọn ẹ̀yà Yorùbá.

Àwọn Yorùbá máa ń sọ orúkọ nípa àkíyèsí, ìhùwàsí, iṣẹ́ àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó bá ṣẹlẹ̀ lásìkò tí ọmọ bá wáyé, gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀ ni ọkanòjọ̀kan orúkọ tí àwọn Yorùbá fún Olódùmarè pẹ̀lú ní ìtumọ̀ tí ó fi bi Olódùmarè ṣe tó hàn.

Ìtàn atẹ́nudétí ti a gbọ́ láti ẹnu àwọn babańlá wá sọ pé orúkọ yìí pín si apá méjì tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àfòmọ́ ìbẹ̀rẹ̀ “oni”, tí ó ń fi ẹni tí ó ní nǹkan tàbí ẹni tí ó ń ṣe nǹkan hàn. Oní pẹ̀lú Odù di Olódù”. Odù nínú èdè Yorùbá túmọ̀ sí orí, tàbí olórí, ó sì tún lè túmọ̀ sí àṣẹ, gẹ́gẹ́ bí a ti rí àpẹẹrẹ Odù Ifá, a tún lè sọ pé Òdù túmọ̀ sí odidi, ẹ̀kúnrẹ́rẹ́, níńlá, tàbí títóbi, àpẹẹrẹ ni; Odù Ọ̀yà. Odù ọ̀yà ni ọ̀yà tí ó tóbi púpọ̀, àwọn Yorùbá tún máa ń lo odù fún ohun ti ó tóbi púpọ̀ bíi, ìkòkò omi, tàbí ohun tí ó wà ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ bí òdù ayò, nínú ọpọ́n ayò tí á ń ta.

Pẹ̀lú àlàyé tí a ṣe sókè yìí, ‘oní odù’ lè túmọ̀ sí aláṣẹ, tàbí ‘oni òdù’ tí ó túmọ̀ sí ẹni tí ó ní ohun gbogbo ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ tàbí ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́.

Abala kejì tí ó jẹ́ “MÀRÈ”, gẹ́gẹ́ bí a ti gbọ́ láti ẹnu àwọn babańlá wa, àwọn mìíràn ni “ỌMỌ ERÈ” ni a gé kúrú, tí ó di ‘màrè’. Yorùbá gbà pé erè ńlá kan tí ó wà láti ayébáyé tí ó máa ń ṣu imí (ìgbẹ́). Imí tí ó bá ṣu yìí ni a mọ̀ sí imí òṣùmàrè tí ó máa ń ṣe okùnfà òṣùmàrè tí ó máa ń fi ara hàn ní ojú ọ̀run. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹni tí ó bá rí imí òṣùmàrè yìí mú, ní àsìkò tí erè yìí bá ṣu imi yóò di olówó, yóò là, yóò sì lù. Imí òṣùmàrè tí a ń sọ̀rọ̀ nípa rẹ̀ yìí wọ́n púpọ̀, kì í ṣe ohun tí ènìyàn lè tètè rí. Ìdòwú (1962:34). Èyí ni pé àwọn kan gbà pé láti ara ‘ọmọ erè’ ni a ti rí ‘màrè’ tí a so pọ̀ mọ́ ‘Olódù’ tí ó di Olódùmarè.

Ìtàn mìíràn tún gbà pé ‘màrè’ túmọ̀ sí ‘má rè’ tí ó tún túmọ̀ sí ‘má lọ’. èyí ni pé bí Olódùmarè ṣe tóbi tó, kò yípadà, kì í re ibìkankan, kò ṣípò padà rí. Ìdí èyí ni Yorùbá fi ń pè É ní Olódùmarè.

Èyíkèyí tí a bá rò pé Olódùmarè túmọ̀ sí nínú àlàyé méjèèjì tí a ṣe lókè yìí, ohun tí ó dájú sáká ni pé, Olódùmarè jẹ́ alágbára tí ó ní ohun gbogbo lódù lódù, tí kò sì re ibì kankan, Olódùmarè kò yípadà ó wà bákan náà láti ayé dé ayé àti láti ìgbà dé ìgbà.

**4.3 Ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè jẹ́**

Àwọn Yorùbá máa ń ṣe àkíyèsí gbogbo ohun tí ó wà ní àyíká wọn, bíi igi igbó, odò, òkun, òkè ńlá ńlá, pẹ̀tẹ́lẹ̀, ewéko, ẹranko kéékèèké àti àwọn ẹranko ńlá abìjà, àti àwọn nǹkan mìíràn.

Bákan náà ni wọ́n kò sàìkíyèsí ìwàláàyè ọmọ ènìyàn. Bí ẹ̀dá ènìyàn ṣe rí, bí ẹ̀dá ènìyàn ṣe ń lóyún, bí wọ́n ṣe ń bímọ, bí ọmọ ṣe ń dàgbà, ìsọ̀rọ̀, ìjẹun àti gbogbo ohun tí ẹ̀dá ènìyàn lè ṣe pátá ni wọ́n máa ń kíyèsí. Èyí ló mú àwọn Yorùbá wá ronú jinlẹ̀ pé gbogbo nǹkan wọ̀nyí tí a tí sọ̀rọ̀ nípa wọn ló jẹ́ ìyanu tí ó sì kọja ọgbọ́n àti òye ẹ̀dá lásán, nítorí náà, wọ́n gbà pé ẹnìkan tí ó lágbára ló ṣe gbogbo nǹkan mèremère wọ̀nyí. Ẹni tí wọn sì gbà pé ó ṣe àwọn nǹkan wọ̀nyí náà ni Olódùmarè, èyí ni ó sì ṣe okùnfà ìgbàgbọ́ wọn nínú Olódùmarè.

Gbogbo ohun tí wọ́n gbà pé Olódùmarè jẹ́ ní ó fi ara hàn láti ara iṣẹ́ ọwọ́ Olódùmarè tí wọ́n rí, àwọn ohun tí ó wà ní àyíká tí wọ́n rí yìí náà ni ó jẹ́ kí àwọn Yorùbá fún Olódùmarè ni orúkọ ọ̀kanòjọ̀kan tí wọ́n fún Un.

**Díẹ̀ Lára Orúkọ Olódùmarè**

**Ẹlẹ́dàá**:

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Ẹlẹ́dàá ni Olódùmarè. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe sọ ṣáájú, èrò wọn ni pé Olódùmarè ní ó dá ọ̀run àti ayé pẹ̀lú ohun gbogbo tí à ń rí lórí ilẹ̀, nínú omi àti ní ojú

ọ̀run. Wọ́n tún gbàgbọ́ pe òun ni ó dá ènìyàn àti ẹranko sórí ilẹ̀, tí ó sì fún wọn ni ẹ̀mí. Ìgbà àti àkókò tí ó wà nínú ayé pẹ̀lú ní wọ́n tún gbà pé Olódùmarè ni ó ṣe wọ́n bẹ́ẹ̀. Wọ́n gbàgbọ́ pé ìgbà òjò wà, kí omi lè wà lórí ilẹ̀ àti fún fún gbígbìn ohun ọ̀gbìn kí ẹ̀dá ènìyàn lè rí oúnjẹ jẹ, bákan náà ni ó dá ìgbà ẹ̀rùn, òòrùn àti òṣùpá fún ànfààní ọmọ aráyé àti láti pààlà láàrin ọ̀sán àti òru. Àwọn Yorùbá gbà pé iṣẹ́ ọwọ́ Olódùmarè ni ohun gbogbo tí à ń rí, èyí ní wọ́n ṣe fi ìgbàgbọ́ wọn hàn nípa pípè é ní Ẹlẹ́dàá ohun gbogbo.

**Ọba**

Àwọn Yorùbá gbà pé Ọba ni Olódùmarè, kìí ṣe bẹ́ẹ̀ nìkan wọ́n tún gbàgbọ́ pé Ọba tó ju gbogbo ọba ayé lọ ní Olódùmarè, èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pé kò sí ẹni tí a lè fi Olódùmarè wé nínú gbogbo Ọba ayé. Wọ́n gbà pé Olódùmarè ni Ọba ọ̀run. Ìdí nìyìí tí wọn fi ń pè É ní Ọlọ́run, ẹni tí ó ní àṣẹ lórí ohun gbogbo Òun ni Ọba ti dandan rẹ̀ kì í yẹ̀ ọ̀run sì ni ó wà tí ó ti ń wo ìṣẹ́ àwọn ẹ̀dá rẹ̀ tí ó dá sáye..

**Alèṣelèwí**

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé kò sí ohun tí Olódùmarè kò lè ṣe, wọ́n máa ń sọ pé “Aṣòroóṣe bí ohun tí Olódùmarè kò lọ́wọ́ sí, adùn-ún ṣe bí ohun tí Olódùmarè bá ti parí”, bí ẹ̀dá ènìyàn ti lè ṣe ìlérí ní àkóko kan fún ẹ̀dá ènìyàn ẹgbẹ́ rẹ̀ ṣùgbọ́n tí ó lè kùnà láti mú irúfẹ́ ìlérí bẹ́ẹ̀ sẹ tí ó bá yá, Olódùmarè ní tirẹ̀ jẹ́ alèṣelèwí ẹni tí ó ń ṣe ohun gbogbo tí ó bá wí bí ó bá ti fẹ́, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódumarè kìí sọ̀rọ̀ kí ó má mú un sẹ.

**Arínúróde**

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé kò sí ohun tí Olódùmarè kò rí, kò sí ohun tí kò mọ̀. Gbogbo ohun tí ẹnìkọ̀ọ̀kan ń rò tí ó sì ń ṣe ní kọ̀rọ̀ ní Olódùmarè rí, èyí ni wọn ṣe máa ń sọ pé “ohun tí ó pamọ́ fún ẹ̀dá ènìyàn, kedere ni ó hàn sí Ọlọ́run. Èyí ní wọ́n ṣe tún máa ń pè é ní ọba abetílukára-bí-ajere, èyí túmọ̀ sí pé Ó mọ ohun gbogbo, kò si ohun kan tí ẹ̀dá ènìyàn kan lè se tí ó pamọ́ fún un. Àwọn Yorùbá pe ojú sánmọ̀ ní ojú Ọlọ́run, èyí ni o fi jẹ́ pé nígbà tí ètímọ́ ba ṣẹlẹ̀ ní ojú ọ̀run wọ́n á ní Ọlọ́run ń ṣẹ́jú (Ìdòwú 1962:41). Yorùbá gbàgbọ́ pé kò sí ibi tí ojú Olódùmarè kò tó, wọ́n gbà pé ohun gbogbo tí ẹ̀dá bá ń ṣe ní

kọ̀rọ̀, gbangba ni lójú Olódùmarè. Ѐyí ni ó tún jẹ́ kí wọ́n máa pe Olódùmarè ni Ọba Arínúróde, Olùmọ̀ràn ọkàn.

**Onídàájọ́**

Àwọn Yorùbá ka Olódùmarè sí adájọ́ tí kìí ṣègbé, èyí ni wọ́n ṣe máa ń pè é ni onídàájọ́ òdodo. Ѐgbàgbọ́ wọ́n tún ni pé Olódùmarè wà ni ọ̀run tí ó ń wo ìṣe ẹ̀dá, òun sì ni yóò sàn ẹ̀san fún ẹ̀dá ẹnìyàn kọ̀ọ̀kan. Gbogbo àwọn tí ó bá ń ṣe iṣẹ́ ibi ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé yóó jèrè ibi, nígbà tí ẹni tí ó bá ṣe rere yóó jèrè ire, gẹ́gẹ́ bí Olódùmarè tí ó jẹ́ onídàájọ́ òdodo yóó ṣe se é. Ѐyí ló mú kí àwọn Yorùbá máa pe Olódùmarè ní Adákẹ́dájọ́.

**Àìkú**

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè kì í kú, èyí ni wọ́n ṣe máa ń pè É ni Ọba Àìkú. Bí Olódùmarè ṣe wa kí ó tó dá ayé àti ọ̀run, bẹ́ẹ̀ náà ni ó wà títí di àkókò yìí. Bí ẹ̀dá ènìyàn kò ti lè wà láyé títí láì kú ló jẹ́ kí àwọn Yorùbá máa sọ pé “kò sí ẹni tí kò níí kú, kò sí ẹni tí oko bàbá rẹ̀ kò ní dìgbòrò”, ṣùgbọ́n àwọn Yorùbá máa ń pe Olódùmarè ní Òyígíyigì, Ọba Àìkú torí kò le ku, Ó ti wà kí ayé tó ó wa, yóó sì máa wà nígbà tí ayé kò ní sí mọ́ ( Ѐdòwú, 1962:43).

**4.4 Díẹ̀ nínú oríkì Olódùmarè**

Ẹlẹ́dàá
Ọlọ́jọ́ òní
Adániwáyé
Adánitán.
Olódùmarè
Atóbìjù
Alóhun gbogbo-lódù-lódù
Olú ọ̀run
Ààlà-funfungbòò
Atẹ́rẹrẹ kárí ayé

Ọba Àìkú

Àìṣá

Àìdíbàjẹ́

Ajípọjọ́-ikú-dà

Àwámárídìí

Onígbọ̀wọ́-ayé

Adákẹ́dájọ́

Ẹlẹ́rìí òdodo

Olùpèsè

Aṣèkanmákù

Adánimágbàgbé

Olúgbohùn

Alèwílèṣe

Elétíigbáròyé

Olùgbèjà

Agbani-lọ́jọ́-ogún le,

Olùgbébifò

Atóósádi lọ́jọ́ tó burú

Ààbò fẹ́ni-ẹ̀rù ń bà

Aláàánú

Ẹlẹ́yinjú-àánú

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín kínní módù kínní yìí ni a ti kẹ́kọ̀ọ́ pé:

- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹnìkan wà tí ó ń jé Olódùmarè àti pé Olódùmarè yìí ni ọba gbogbo ayé tí ó dá ohun gbogbo tí ó wà ní ayé àti ọ̀run.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé kò sí ohun tí Olódùmarè kò mọ̀, kò sí ohun tí kò rí, bẹ́ẹ̀ ni kò sì sí ohun tí kò le ṣe.

- Lọ́nà átifí títóbi Olódùmarè hàn, àwọn Yorùbá fún Olódùmarè ní ẹgbàágbèje orúkọ àti ẹgbẹ̀fà oríkì èyí tí wọn fi máa ń bu ọla fún un
- Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa bí Olódùmarè ṣe jẹ́ àti bí ó ṣe tó, fihàn dájúdájú pé àwọn Yorùbá gbà pé Olódùmarè wà.
- Gbogbo ohun tí wọ́n gbà pé Olódùmarè jẹ́ ní ó fi ara hàn láti ara iṣẹ́ ọwọ́ Olódùmarè tí wọ́n rí.
- a ti sọ ìtàn tí ó rọ̀ mọ ìtumọ̀ orúkọ Olódùmarè.
- a tún ti ṣe àfihàn díẹ̀ lára orúkọ àti oríkì Olódùmarè.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Báwo ni Yorùbá ṣe mọ̀ pé Olódùmarè wà?

ii. Ṣàlàyé mẹ́rin lára ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè jẹ́

iii. Sọ ìtumọ̀ orúkọ Olódùmarè.

iv. Sọ márùn-ún lára orúkọ Olódùmarè àti ìtumọ̀ rẹ̀

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adeoye, C.L. 2005. *Àṣà àti ìṣe Yorùbá*. Ibadan.University press plc.

Idowu, B. 1962. *Olódùmarè, God in Yorùbá belief*. Ikeja, Longman Nigeria Ltd.

## ÌPÍN KEJI: ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍPA ÌṢẸ̀DÁ AYÉ

### Ìfáàrà

Nínú Módù yìí ni a ó ti gbọ́ àlàyé kíkú́n nipa ìṣẹ̀dá ayé gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú ìtàn Yorùbá, akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yìí yóò ní òye kíkún nípa ìṣẹ̀dá ayé láti inú ìtàn Yorùbá tí a ti gbọ́ àti èyí tí àwọn onímọ̀ kọ.

Àkóónú

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Àwọn Yorùbá àti ìtàn ìṣẹ̀dá ayé

4.2 Ilẹ́-ifẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ibi tí ayé ti bẹ̀rẹ̀

4.3 Àkọsílẹ̀ àwọn onímọ̀ nípa ìṣẹ̀dá ayé

4.4 Àrídìmú nípa ìtàn ìṣẹ̀dá ayé

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Ìpín yìí bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìtàn tí a gbọ́ láti inú ìtàn àtẹnudẹ́nu àti àwọn ohun tí àwọn òǹkọ̀tàn kọ sílẹ̀ lórí àwọn ohun tí Yorùbá mọ̀ nípa ìṣẹ̀dá ayé, a ó wo ìtàn tó rọ̀ mọ́ ìṣẹ̀dá ayé tí àwọn baba-ńlá Yorùbá rí gẹ́gẹ́ bí ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá kí a lè rí òye tó dájú gbámú nípa ìtàn náà.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí akẹ́kọ̀ọ́ ó lè:

- Ṣàlàyé kíkún nípa ìtàn ìṣẹ̀dá ayé
- Ní ìmọ̀ nípa bí ìṣẹ̀dá ayé ṣe jẹmọ́ orírun Yorùbá

## 3.0 Ìbéèrè ìṣáájú

i. Kọ ìtàn ìṣẹ̀dá ayé bí ó ṣe yé ọ sí

ii. Ta ni ó ṣẹ̀dá ayé?

## 4.0 Ìbẹ̀ẹ̀rẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### Ìtàn Ìṣẹ̀dá Ayé

Ilé- Ifẹ̀ ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ó jẹ́ ibi tí ojúmọ́ ti mọ́ wá, ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé ibẹ̀ ni ilé-ayé ti bẹ̀rẹ̀. Ìtàn àtẹnudẹ́nu Yorùbá fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ní ìgbà ìwáṣẹ̀, ayé wà ní júujùu, ó sì kún fún omi tàbí òkun, èyí tí ó wà lábẹ́ òfúrufú níbi tí Olódùmarè àti àwọn òrìṣà tó kù ń gbé. Nígbà tí àsìkò tò fún Olódùmarè láti dá ibùgbé ènìyàn, ó pe Ọbàtálá láti wá bá òun dá ibùgbé àwọn ènìyàn sójú alagbalúgbú omi, àmọ́ a gbọ́ pé Ọbàtálá kùnà láti mú àṣẹ Olódùmarè ṣẹ nítorí pé ó mu ẹmu yó.

Nígbà tí Ọbàtálá kùnà láti mú àṣẹ Olódùmarè ṣẹ, ó rań Odùduwà ní iṣẹ́ náà, Olódùmarè fún un ní ìkarahun ìgbín tí ó kún fún erùpẹ̀, ó sì tún fún un ní adìyẹ ọlọ́mọ ìka márùn-ún àti ẹyẹlé. Ìtàn àtẹnudẹ́nu kan tilẹ̀ fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ẹ̀wọ̀n ni Odùduwà fi rọ̀ láti ìkọ̀lé òrun wá sí orí omi nígbà náà, ó da erùpẹ̀ náà sórí alagbalúgbú omi, ó sì kó àwọn ẹran abìyẹ́ méjèèjì sórí erùpẹ̀ náà láti bẹ̀rẹ̀ sí ní fi ẹsẹ̀ wọn fẹ erùpẹ̀ orí omi náà, ilẹ̀ yìí sì bẹ̀rẹ̀ sí ní borí omi. Iṣẹ́ takuntakun tí Odùduwà ṣe yìí ló mú kí ó sáré lọ jíṣẹ́ fún Olódùmarè lájùlé ọ̀run pé iṣẹ́ náà ti yọrí sí rere, lọ́nà kí Olódùmarè lè ri dájú pé Odùduwà jẹ́ iṣẹ́ náà, ó rán alágẹmọ láti lọ wo ilé ayé wá, nígbà tí alágẹmọ rí iṣẹ́ náà, ó pada lọ jíṣẹ́ fún Olódùmarè pé iṣẹ́ náa yọrí sí rere àti pé ó ti dára fún ènìyàn láti gbé. Ìtàn fi ìdí rẹ̀

múlẹ̀ pé ibi tí àwọn ẹran abìyẹ́ méjèèjì tí a ti dárúkọ ṣáájú ti fẹ erùpẹ̀ ni à ń pè ní Ilé-ifẹ̀ di òní olónìí.

Àwọn ìran Yorùbá rí Ilé-ifẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ibi tí ojú ti mọ́ wá tí ó túmọ̀ sí pé ibẹ̀ ni ìṣẹ̀dá ayé ti bẹ̀rẹ̀. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ìtàn ìṣẹ̀dá ayé fara jọ ìtàn orírun Yorùbá, síbẹ̀, ó yàtọ̀ sí ìtàn àtọ̀húnrìnwá tó fi Mọ́kà hàn bí ìlú Lámúrúdu tíí ṣe baba Odùduwà, tó jẹ́ baba-ńlá àwọn Yorùbá. Àmọ́ ṣáá o, ìtàn àtẹnudẹ́nu nípa orírun Yorùbá ṣe rẹ́gí pẹ̀lú ìtàn ìṣẹ̀dá ayé bí Ìdòwú (1963) ṣe sọ pé yẹ̀pẹ̀ àti àwọn ẹranko abìyẹ́ ni ó ran Odùduwà lọ́wọ́ láti dá ayé àti pé alágẹmọ ni ẹranko tí Olódùmare rán láti wá wò bóyá Odùduwà jẹ́ iṣẹ́ tí ó rán an.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín kejì módù kínní yìí ni a ti kẹ́kọ̀ọ́ pé:

- Ilé- Ifẹ̀ ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ó jẹ́ ibi tí ojúmọ́ ti mọ́ wá
- Ọbàtálá láti wá bá òun dá ibùgbé àwọn ènìyàn sójú alagbalúgbú omi, àmọ́ a gbọ́ pé Ọbàtálá kùnà láti mú àṣẹ Olódùmarè ṣẹ nítorí pé ó mu ẹmu yó.
- Nígbà tí Ọbàtálá kùnà láti mú àṣẹ Olódùmarè ṣẹ, ó rań Odùduwà ní iṣẹ́ náà
- Ìkarahun ìgbín tí ó kún fún erùpẹ̀, adìyẹ ọlọ́mọ ìka márùn-ún àti ẹyẹlé ní Olódùmarè fún ọbàtálá láti wá dá ilé ayé.
- Ibi tí àwọn ẹran abìyẹ́ méjèèjì tí a ti dárúkọ ṣáájú ti fẹ erùpẹ̀ ni à ń pè ní Ilé-ifẹ̀ di òní olónìí.
- A kò lè sọ ìtàn ìṣẹ̀dá ayé láì mẹ́nuba ìtàn àtẹnudẹ́nu nípa orírun àwọn Yorùbá.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Ìjọra wo ló wà láàárín ìtàn ìṣẹ̀dá ayé àti ìtàn orírun àwọn Yorùbá?

ii. Ipò wo ni agẹmọ wà nínú ìtàn ìṣẹ̀dá ayé?

iii. Ṣe ọ̀rínkínniwín àlàyé nípa ìṣẹ̀dálẹ̀ Yorùbá

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoyè, C.L. 1979. *Àṣà Àtìṣe Yoruba*. Ibadan: University Press Limited.

Àtàndá, J.A. 1996. *The Yoruba People: Their Origin, Culture and Civilization* in Ọdúnjọ. J.F Memorial Lecture, Series 5. Ibadan: I.U.P

Johnson, S. 2001. *History of the Yorubas from the Earliest Times to the Beginning of the British Protectorate*. Lagos: CSS Limited.

**ÌPÍN KẸTA: ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍNÚ ÀWỌN ÒRÌṢÀ**

**Ìfáàrà:**

Ní ìpín yìí, a ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá. Akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yóò ní òye kíkún nípa ipò tí òrìṣà wà gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe hàn nínú ìtàn ìwásẹ̀ Yorùbá.A ó ṣe àfihàn bí òrìṣà ṣe jẹ́ alágbàwí láààrin àwọn ènìyàn àti Olódùmarè. Bákan náà, a wó oríṣìíríṣìí òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá, nínú ìpín yìí náà ni a ó ti ṣàlàyé ipò tí àwọn àṣàyàn òrìṣà wà, lẹ́yìn èyí ni a ṣe àyẹ̀wò àwọn nǹkan tí ó jẹ́ èèwọ̀ àwọn òrìṣà tí a yẹ̀wò.

**Àkóónú:**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    4.1 Òrìṣà
    4.2 Òrìṣà ilẹ́ Yorùbá
    4.3 Oríṣìíríṣìí Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá
    4.4 Díẹ̀ Nínú Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá
    4.5 Ipò òrìṣà lóde òní
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Ìpín yìí ṣe àfihàn ipò tí àwọn òrìṣà wà gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe hàn nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe àfihàn bí òrìṣà ṣe jẹ́ òlùránṣẹ́. A wo oríṣìíríṣìí ìpín tí òrìṣà wà nípa wíwo bí wọ́n ṣe di òrìṣà náà. A tún ṣe àyẹ̀wò díẹ̀ lára àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá. Lẹ́yìn èyí ni a wo ipò tí àwọn òrìṣà wà lóde oní.

## 2.0 Èròngbà àti Àfojúsùn

Èròngbà lẹ́yìn tí a bá parí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni pé àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yóò:

- Lè ṣàlàyé ohun tí ó ń jẹ́ òrìṣà gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe hàn nínú ìtàn ìwáṣẹ̀ àti ìgbàgbọ́ Yorùbá.
- Ní òye nípa ọ̀nà tí àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá pín sí
- Lè tọ́ka sí àwọn òrìṣà Yorùbá
- Fi ìyàtọ̀ hàn láàárín Olódùmarè àti àwọn òrìṣà

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

i. "Ọ̀kan náà ni òrìṣà àti Olódùmarè" Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.

ii. Dárúkọ òrìṣà márùn-ùn ti ó mọ̀.

iii. Òrìṣà wo ló gbajúmọ̀ ní ìlú rẹ?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Kíni ń jẹ́ Orìṣà?

Òrìṣà jẹ́ ìṣẹ̀dá tí Olódùmarè ṣà lẹ́ṣà láti wà nípò tí ó ga ju ti àwọn ènìyàn lọ, yálà ó jẹ́ òrìṣà tí o tẹ́wọ̀n rọ̀ tàbí akọni-tó-di-òrìṣà. Káàkiri ilẹ̀ Afíríkà ni a ti rí oríṣìíríìṣí òrìṣà tí ó ń fi ìgbàgbọ́ àwọn ènìyàn  hàn. Nínú ètò ìṣàkóso ìṣẹ̀dá ilé-ayé, àwọn òrìṣà ni ó pawọ́lé Olódùmarè. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn olùsìn máa ń bọ òrìṣà lóòrèkóòrè, síbẹ̀ wọn ní òye pé Olódùmarè ní àṣẹ àti agbára tí ó ju ti òrìṣà lọ. Oríṣìíríṣìí orukọ ni àwọn àwùjọ tí ó wà ní ilẹ̀ Afíríkà n pe ohun tí Yorùbá ń pè ní òrìṣà; '*Akan*' ti ilẹ̀ "*Gánà*" ń pè é ní "*abosom*", àwọn "*Ewe-Fon*" orílẹ̀-èdè Bẹ̀nẹ̀ sì ń pe òrìṣà ní "vudu".Ojú ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni àwọn olùsìn fi ń wo orìṣà, bí àpẹẹrẹ, àwọn Akan gbà pé àwọn "abosom" jẹ́ ọmọ "Onyame" tí jẹ́ Olódùmarè. Bákan náà ni àwọn Edó rí "Olokun" gẹ́gẹ́ bí ọmọ "Osanobwa". Bi ó ṣe jẹ́ pé gbogbo àwọn òrìṣà Akan ni wọ́n rí bí i ọmọ Ọlọrun, Òrìṣà-Ńlá nìkan ni àwọn Yorùbá rí gẹ́gẹ́ bí ọmọ Olódùmarè.

Òrìṣà kọ̀ọ̀kan ni ó ní àwòrò òrìṣà tirẹ̀, èèwọ̀, ohun tí wọ́n yọ́nú sí, ọ̀nà tí wọ́n gbọ́dọ̀ gbà sìn ín, ojúbọ, orin ìbọ́, àmì idànimọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí a ṣe ní òrìṣà tí ó jẹ́ akọ náà ni a ni òrìṣà tí ó jẹ́ abo. Bí àpẹẹrẹ, Ọbàtálá, Eṣù àti Ṣangó jẹ́ akọ nígbà tí Ọya, Ọ̀ṣun àti Yemọja jẹ́ abo.

## 4.2 Àwọn Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá

Ìpo ńlá ni àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá wà pàápàá ní ọkàn àwọn tí ó ń bọ àwọn òrìṣà náà. Yorùbá ka àwọn òrìṣà wọ̀nyí sí púpọ̀ nítorí wọ́n gbà pé ìbáṣepọ̀ tó dán mọ́rán wà láàárín Olódùmarè àti àwọn òrìṣà wọ̀nyí. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé “alágbàwí” ni àwọn òrìṣà jẹ́. Wọ́n dúró gẹ́gẹ́ bí i “Olùránṣẹ́” tí wọ́n lè rán sí Olódùmarè yálà nígbà tí wọ́n bá ń tọrọ nǹkan tàbí nígbà tí wọ́n bá ń ṣe ìdúpẹ́. Àwọn òrìṣà súnmọ́ àwọn ènìyàn, wọ́n ní àǹfààní láti ma lọ sí ọ̀run kí wọ́n sì máa bọ̀. Èyí ló ṣe rọrùn fún àwọn ènìyàn lati bẹ̀ wọ́n níṣẹ́ sí Olódùmarè. Àwọn òrìṣà yìí kò lè dá ṣe ohunkóhun fún àwọn olùsìn ṣùgbọ́n wọ́n ní àǹfààní láti bèèrè ohun tí wọ́n bá ń fẹ́ lọ́wọ́ Olódùmarè.

Àwọn olùsìn máa ń ní ojúbọ òòṣà tí wọ́n ti máa ń pàdé láti bọ irúfẹ́ òrìṣà tí wọ́n yàn láàyò. Wọ́n lè lo igi, irin, èrè tàbí amọ̀ láti fi sàmì òrìṣà wọn. O ṣe ẹ ṣe kí wọ́n kọ́lé fún un, wọ́n sì lè má kọ́lé.

## 4.3 Oríṣìíríṣìí Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá

Oríṣìíríṣìí ni àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá. Ìwádìí fihàn pé àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá pọ̀. Àwọn kan ní igbàgbọ́ pé òòṣà Yorùbá tó igba, bákan náà ni àwọn mìíràn gbà pé wọ́n tó ọ̀kànlénú. Lára àwọn òòṣà yìí ni a ti rí àwọn tí ó rọ̀ wá láti òde ọ̀run. Àwọn wọ̀nyí ni Olódùmarè rán láti wá dá ilé ayé tàbí ṣètò kan tàbí òmíràn. Àpẹẹrẹ àwọn irúfẹ́ òrìṣà yìí ni Ọbàtálá, Ọ̀rúnmìlà, àti Ògún. Yàtọ̀ sí àwọn wọ̀nyìí, àwọn òòṣà kan wà tí ó jẹ́ pé ènìyàn ni wọ́n kí ó tó di pé wọ́n di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ. Àpẹẹrẹ irúfẹ́ èyí ni Ṣàngó, Ọya, Ọbà, Ọ̀ṣun àti àwọn mìíràn.

Ó ní iṣẹ́ tí Olódùmarè fi rań àwọn òrìṣà kọ̀ọ̀kan. Bí àpẹẹrẹ, Ọbàtálá ni ó mọ ẹ̀dá kí ó tó di pé Olódùmarè wá fi ẹ̀mí sí i lára. Iṣẹ́ ààbó ni ti Ògún, Ọ̀rúnmìlà ni ó ṣe àmójútó ọgbọ́n ilé ayé, Ọ̀sányìn bójútó iṣẹ́ ìṣègùn. Òrìṣà-oko ni ìtàn sọ pé ó ń ṣàkóso iṣẹ́ àgbẹ̀, Ọ̀ṣun ni alákóso ìbísí (èyí ni wọ́n ṣe máa ń pè é ní òrìṣà ọlọ́mọ yọyọ).

Ẹnu kò kò lórí iye tí àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá jẹ́ ní pàtó. Àwọn òmíràn gbà pé ẹ̀rùnlọ́jọ́ irúnmọlẹ̀ (700) ni ó wà. Nígbà mìíràn wọ́n máa ń sọ pé “igba irúnmọlẹ̀ ojùkọ̀tún, igba irúnmọlẹ̀ ojúkòsì". Àpapọ̀ èyí jẹ́ irinwó (400). A tún rí ọ̀kànlénù irúnmọlẹ̀ (401). Yàtọ̀ sí èyí, a máa ń gbọ́ òjìlélégbèje irúnmọlẹ̀.

## 4.4 Díẹ̀ Nínú Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá

- **Ọbàtálá/Òrìṣà-Ńlá**

Ìtàn fi yè wa pé ipò Ọbàtálá ga nínú gbogbo òrìṣà. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè fún Ọbàtálá ní àṣẹ láti ran Òun lọ́wọ́ nínú iṣẹ́ rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Ẹlẹ́dàá. Wọ́n máa ń pe é ní “Alámọ̀ rere” nítorí pé ó máa ń lo amọ̀ rere fún mímọ ẹ̀dá ènìyàn. Nígbà tí Ọbàtálá bá ti mọ ẹ̀dá tán ni Olódùmarè yóò wá fi ẹ̀mí sí i lára. Ìtàn jẹ́ kí a mọ̀ pé nígbà tí Ọbàtálá mu ẹmu tán ni ó mọ àwọn ẹ̀dá bí i arọ, afọ́jú, àfín, amúkùn, àti abuké. Wọ́n máa ń pe àwọn wọ̀nyí ní ẹni òrìṣà.

Ẹfun ni wọ́n fi máa ń kun ojúbọ Ọbàtálá. Iyán àti ọbẹ̀ funfun (ọbẹ̀ ẹran ìgbín) tí wọ́n dé sínú igbá funfun ni oúnjẹ rẹ̀. Ojúde ni wọ́n ń kọ́lé Ọbàtálá sí. Aṣọ funfun ni àwọn Olórìṣààlá máa ń wọ̀, bákan náà ni wọ́n máa ń dá ìlẹ̀kẹ̀ funfun (ṣẹ́ṣẹ́-ẹfun) sọ́rùn. Ó hàn nínú àlàyé òkè yìí pé Ọbàtálá jẹ́ òrìṣà tí ó kórira ìdọ̀tí torí funfun nini ni nǹkan Olóòṣàálá. Ojoojúmọ́ ní kùtù hài ni wọ́n ń pọn omi fún Ọbàtálá nítorí kì í mu omi ìkàsì. Ajípọn-omi òrìṣà gbọ́dọ̀ jẹ́ ẹni tí kò tíì bàlágà. Bí ẹni yìí bá ti ń lọ sódò, á máa mi ààjà kí àwọn ènìyàn baà le mọ̀ pé ó ń bọ̀ kí wọ́n lè yà lọ́nà fún un. Ìgbìn ni ìlù Ọbàtálá.

Àwọn àgàn, aláìsàn, àti àwọn tí ó ní ìṣòro kan tàbí òmíràn máa ń tọ̀ ọ́ lọ fún ìrànlọ́wọ́. Wọ́n máa ń lo omi ìdí òrìṣà yìí fún ìwòsàn.

- **Èèwọ̀ Ọbàtálá**

Ọbàtálá kì í mu ẹmu, kì í jẹ iyọ̀, bákan náà ni kì í rí ewé tàbí igi ajádẹ lójú. Ẹ̀ẹ̀kan ni wọ́n fi ń kọ́lé rẹ̀. Àwọn adósù Ọbàtálá kì í mẹmu, bákan náà ni wọn kì í jẹ iyọ̀. Èèwọ̀ ni láti gbé epo sún mọ́ ìdí òrìṣà Ọbàtálá.

**ORÍKÌ ỌBÀTÁLÁ**

Ikú tí í ba ni gbé ilé f'ọlá ranni
Aláṣẹ! O sọ ẹnìkan soso di igbà ènìyàn
Sọ mí di'run, Sọ mí d'igba
Sọ mi d'ọ̀tàlé-légbèje ènìyàn
Òrìṣà eti ẹni ọlá
O fi gbogbo ọjọ́ t'obi
Ó tóbi láìṣeégbé
Bàǹtà banta nínú àlà
Ó sùn nínú àlà
Ó jí nínú àlà
Ó ti inú àlà dìde
Baba ńlá, oko Yémowó!
Òrìṣà wù mí ní ibùdó
Ibi rere l'òrìṣà kalẹ̀
Òrìṣà ńlá, Ọ̀ṣẹ̀rẹ̀màgbò
Ẹni tí wọn bí l'óde Ìgbò
Tó lọ jọba l'óde Ìrànje
Òrìṣà ńlá alàbàláṣẹ
Òrìṣà ńlá atẹ́rẹrẹ k'áyé
Ò gbe ọmọ rẹ̀, ó sọ ọ́ dàjẹ́

Òrìṣà ńlá Àdìmúlà
Olójú kára bí ajere
Òbàba arúgbó
Òrìṣà gbìngbinnìkìn

- **Ọ̀rúnmìlà**

Itàn fi yé wa pé Olódùmarè rán Ọ̀rúnmìlà wá sí ilé ayé láti wá ṣe igbákejì Òun. Àwọn èniyàn máa ń béèrè oríṣìíṣíìrí nǹkan lọ́wọ́ Ọ̀rúnmìlà nítorí wọ́n gbà pé "akéré-finú-ṣọgbọ́n" ni, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pe gbogbo ọgbọ́n ilé ayé wà ní ìkáwọ́ Ọ̀rúnmìlà. Ìtàn ìwáṣẹ̀ jẹ́ kí a mọ̀ pé Ọ̀rúnmìlà wà níbẹ̀ nígbà tí Olódùmarè dá gbogbo ohun tí ó wà nínú ilé ayé àti nígbà tí ẹ̀dá èniyàn ń yan ìpín rẹ̀ lóde ọ̀run kí wọ́n tó wá sí ilé ayé. Ìdí nìyí tí wọ́n fi ń pè é ní "Ẹlẹ́rìí Ìpín".

Bákan náà, wọ́n máa ń pe Ọ̀rúnmìlà ní "Òbìrìkítí a pa ọjọ́ ikú dà". Ìdí èyí nipé àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Ọ̀rúnmìlà mọ bí ó ṣe lè bá Olódùmarè sọ̀rọ̀ tí yóò sì gbà sí i lẹ́nu. Ọ̀rúnmìlà ni Olódùmarè máa ń lò láti jẹ́ kí àwọn èniyàn mọ ohun tí yóò ṣẹlẹ̀ ní ọjọ́ iwájú.Ó dúró bí i alátìlẹ́yìn tàbí aláàbò fún àwọn babaláwo.Ó máa ń tọ́ wọn sọ́nà lórí ewé àti egbò tí wọ́n lè lò fún ìwòsàn.

Àwọn Babaláwo máa ń bọ Ọ̀rúnmìlà ní ojoojúmọ́ kí ó lè tọ́ wọn sọ́nà. Obì ni wọ́n ń lò fún ètùtù tí wọ́n máa ń ṣe láràárọ̀ yìí. Yàtọ̀ sí èyí, wọ́n máa ń ṣe àjọ̀dún Ọ̀rúnmìlà. Bí wọ́n bá fẹ́ bọ Ọ̀rúnmìlà wọ́n máa ń ki ifá báyìí:

Tí a bá jí, a wẹ́wọ́ tọ́ní, á wẹsẹ kàsìn òwúrọ̀
Tí a bá jí, a tún wá fi aṣọ tòkí bora
Mo ní Ọ̀rúnmìlà, o jí ire lónìí
Ẹ̀là, o jí ire lónìí

Ọ̀sànyìn ni Ọ̀rúnmìlà máa ń sábà rán níṣẹ́ pàápàá tí ó bá níṣe pẹ̀lú oògùn. Yàtọ̀ sí èyí, Èṣù náà máa ń ṣe ìrànwọ́ fún un.  Ọ̀rúnmìlà ni ó máa ń ṣàkoso ifá, àwọn kan tilẹ̀ máa

ń pè é ni Ifá. Nítorí pé ó jẹ́ élẹ́rìí-ìpín, gbogbo àṣírí ilé ayé wà ní ọwọ́ rẹ̀. Àwọn àmì tàbí ohun ìdámọ̀ olùsìn Ọ̀rúnmìlà ni ọpọ́n ifá, ikin, ọ̀pẹ̀lẹ̀, àti ẹbọ.

**Oríkì Ọ̀rúnmìlà**

Ẹlẹ́rìí ìpín

Akéréfinúsọgbọ́n

Akọ́nilọ́ràn bí ìyekan ẹni

Òpìtàn ile e fẹ̀

- **Èṣù**

Ó ṣe pàtàkì láti jẹ́ kí a mọ̀ pé Sátánì inú Bíbélì yàtọ̀ sí Èṣù tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá. Èṣù jẹ́ òrìṣà tí o ní ìgboyà àti ọgbọ́n àrékérekè tí ó sì ní akìnkanjú pẹ̀lú. Àwọn ènìyàn àti àwọn òrìṣà yòókù bẹ̀rù Èṣù nítorí ìwà àti iṣẹ́ búburú tí ó wà ní ọwọ́ rẹ̀. Èṣù ni ó máa ń kọ́kọ́ gba ẹbọ kí àwọn òrìṣà yòókù tó gbà. Ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn òrìṣà tí Ọ̀rúnmìlà máa ń rán níṣẹ́.

Ojúbọ Èṣù máa ń wà ní odi ìlú lábẹ́ àgọ̀ tí wọn fi ikin kọ́. Àwọn mìíràn ma ń gbẹ́ ère Èṣù sí ìta gbangba. Yorùbá gbà pé ẹni tí kò bá fi ti Èṣù ṣe yóò rí ìjà rẹ̀.

Lára ohun tí wọ́n fi ń bọ Èṣù ni òbúkọ, epo, ajá, àkùkọ, ìgbín, ẹ̀kọ àti obì. Wọ́n máa ń da epo tàbí ẹ̀jẹ̀ ẹran tí wọ́n bá fẹ̀ fi bọ ọ́ lórí ère rẹ̀. Èṣù kórira àdí. Orúkọ mìíràn tí wọ́n ń pè é ni Ẹlẹ́gbẹ́ra, Ọba Ọ̀dàrà, Onílé oríta, Olóògùn Àjísà, Láàlú Ògiri Òkò àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn mìíràn máa ń tọrọ agbára búrubú lọ́wọ́ Èṣù láti ṣe ìjàǹbá fún ẹ̀dá ẹgbẹ́ wọn. Àwọn mìíràn gbàgbọ́ pé Èṣù lè fún ènìyàn ní ọmọ nípa báyìí ni a ṣe rí àwọn tó ń jẹ́ Èṣùbíyì, Èṣúdọlá, Èṣútósìn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Oríkì Èṣù**

Èsù láàlú,

Esù òdàra
O lé sońsó sórí ẹṣẹ̀ ẹlẹ́ṣẹ̀
Kò jẹ, kò jẹ́ kí ẹni ń jẹ gbé e mì
A kì í lówó làì mú tèṣù kúrò
A kì í láyọ̀ láì mú tèsù kúrò
Asọ̀tún-sòsì láì nítìjú
Èsù a pata sọ́mọ ọlọ́mọ l'ẹ́nu
A fòkúta dípò iyọ̀
Paapa-warà, A túká máṣe í sà
Èsù má ṣe mí, ọmọ ẹlòmíràn ni kó se

- **Ògún**

A kà á nínú ìtàn ìwásẹ̀ pé Ògún ni ó lànà fún àwọn òrìṣà yòókù nígbà tí wọ́n ń bọ̀ láti ìkọ̀lé ọ̀run wá sí ìkọ̀lé ayé nítorí pé irin ni àdá rẹ̀. Ìdí nìyí tí àwọn òrìṣà yòókù fi jẹ oyè Ọ̀sìn-imọlẹ̀. Ògún fẹ́ràn iṣẹ́ ọdẹ, èyí ló mu kúrò ní  Ilé-ifẹ̀ tí tí ó fi dé Irè ní agbègbè Èkìtì. Ìdí níyìí tí wọ́n fi ń pè é ní "Ògún Onírè". Ògún ló ni gbogbo irin. Àwọn tí ó bá ń lo irin tàbí nǹkan tí wọ́n fi irin ṣe gbọ́dọ̀ júbà Ògún. Gbẹ́nàgbẹ́nà ni Ògún. Ó fẹ́ràn òtítọ̀ àti òdodo. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé a kò gbọdọ̀ dalẹ̀ Ògún, bí bẹ́ẹ̀ kọ́, irúfẹ́ ọ̀dàlẹ̀ bẹ́ẹ̀ yóò fi ẹ̀jẹ̀ wẹ̀.

Àwọn nǹkan tí wọ́n fi ń bọ Ògún ni ajá, iyán, epo, adìyẹ, obì àti ẹmu. Àárín ìlú ni ojùbọ Ògún máa ń wà ṣùgbọ́n àwọn olùbọ rẹ̀ lè ní ojúbọ ní ìdílé wọn. Àwọn ìlú mìíràn ma ń fi aja méje bọ Ògún tí ó sì jẹ́ pé ẹ̀kan ṣoṣo ni wọn yóò bẹ́ orí ajá náà.

Kálákolo àti bẹ̀mbẹ́ ni ìlú Ògún. Ọjọ́ méje ni wọ́n fi máa ń ṣe ọdún Ògún. Lárá oríkì Ògún nìyí:

Onílé kángunkàngun ọ̀nà ọ̀run
Olómi nílé fẹ̀jẹ̀ wẹ̀

Ò lásọ nílé, fimọ̀kímọ̀ bọra
Ògún méje lògún mi
Ògún alárá ni gbajá
Ògún Onírè a gbàgbò
Ògún Ìkọla a gbàgbín
Ògún Ẹlẹ́mọnà n ií gba ẹ̀sun iṣu
Ògún Akírun a gba ìwo àgbò
Ògún gbẹ́nàgbẹ́nà oje igi ní í jẹ
Ògún Mákindé ti dògún lẹ́yìn odi
Bí kò bá gba Tápà a gb'Àbòókí
A gba Úkù-úkù, a gba Kemberí
Ǹjẹ́ níbo la ti pàdé ògún?
A pàdé ò gún níbi ìjà
A pàdé ògún níbi ìta
A pàde rẹ̀ níbi ẹ̀jẹ̀ ń sàn
Òrìṣà tó ní tògún kò tó pọ́n
A fọwọ́ jẹṣu rẹ̀ nígbà àìmọye
Bọ́mọdé bá dalẹ̀ kó máse da ògún
Ọ̀rọ̀ ògún léèwọ̀
Ẹ má bá ògún fìjà seré
Ara ògún kan gó-gó-gó

- **Ṣàngó**

Ìtàn sọ fún wa pé ènìyàn ni Ṣàngó kí ó tó di òrìṣà. A gbọ́ pé ọmọ Ọ̀rànmíyàn ni Ṣàngó, ó sì fẹ́ Ọya, Ọ̀ṣun, àti Ọbà. Ọmọ líle ni Ṣàngó láti òde ọ̀run wá, bí ìyá rẹ̀ ṣe bí i ló kú, tí a sì jù ú sínú ìgbẹ́. Ẹ̀dá líle ni Ṣàngó, iná máa ń sẹ́ jáde lẹ́nu rẹ̀ tó bá ń sọ̀rọ̀. Ẹ̀rù ni Ṣàngó jẹ́ fún ẹnikẹ́ni, òǹrorò sì ni pẹ̀lú. Ṣàngo lágbára, ó lóògùn, ó fẹ́ràn àti máa fi agbára rẹ̀ hàn. Tí Ṣàngó bá ń sọ̀rọ̀, iná máa ń yọ lẹ́nu rẹ̀ bùlàbùlà.Ọba ni Ṣàngo jẹ́ lóde Ọ̀yọ́-ilé ní Kátúngá, ṣùgbón ó dá wàhálà sílẹ̀ láàrin ìjòyè rẹ̀ méjì tí ọ̀kan sì pa èkejì, èyí ló mú kí wọ́n

dìtẹ̀ mọ́ Ṣàngó tí ó sì bínú kúrò lóde Ọ̀yọ́, Ọya, Ọ̀sun àti Ọbà ìyàwó rẹ̀ tẹ̀lé e ṣùgbọ́n Òsùmàre àti Òru ìránṣẹ́ rẹ̀ padà lẹ́yìn rẹ̀. Ṣàngó so sí orí igi àyàn ní kòso nítòsí Ọ̀yọ́, inú bí àwọn ènìyàn Ṣàngó wọ́n sì gba òògùn ní ìbàrìbá láti bá àwọn Ọ̀yọ́ jà lọ́pọ̀lọpọ̀, àwọn ará Ọ̀yọ́ padà lọ bẹ Ṣàngó wọ́n sì pa ẹnu dà pé “Ọba kò so”, lẹ́yìn ikú Ṣàngó ó di òrìṣà àkúnlẹ̀bọ Àwọn àwòrò Ṣàngó ni a mọ̀ sí Adóṣù-Ṣàngó, ọkùnrin ni awọn adóṣù Ṣàngó ṣùgbọ́n wọ́n máa ń dirun wọn ni. Aṣáájú nínú olùsìn Ṣàngó jẹ́ obìnrin tó ti kúrò lọ́wọ́ ìbímọ, Ìyá-Magbà ni a sì ń pè é. A kò gbọdọ̀ fi ọwọ́ gbe òjò tabi fẹ̀yiǹ ti ògiri ìgànná tí òjò bá ń rọ̀ bí a kò bá fẹ́ rí ìbínú Ṣàngó, torí àrá máa ń sán lákòókò tí òjò bá ń rọ̀. Àwọn olùsìn Ṣàngó gbàgbọ́ pé ó máa ń fi òkúta jà, ìdí nìyí tí wọ́n ṣe ń pè é ní Jàkúta, àwọn oníṣàngó ló máa ń sin òkú ẹni tí àárá bá pa ní ilẹ̀ Yorùbá. Ọ̀yọ́ ni ọdún Ṣàngó ti wọ́pọ̀ jùlọ ní ilẹ̀ Yorùbá

Orógbó, adìyẹ àti àgùntàn bọ̀lọ̀jọ̀ ni wọ́n máa fi n bọ Ṣàngó. Bákan náà ni ọkà jẹ́ oúnjẹ rẹ̀. Àwọn ènìyàn tí ó ní ìgbàgbọ́ nínú Ṣàngó máa ń tọrọ ọmọ lọ́wọ́ rẹ̀. Èyí ni a ṣe rí àwọn tí ó ń jẹ́ Ṣàngótóyè, Ṣàngógbèmí, Ṣàngówánwá, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Díẹ̀ lára oríkì Ṣàngó ni ó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

> Ṣàngó Oníbọn Ọ̀run
> Àjàlájì Ọba Kòso
> Ọkùnrin alágbára inú afẹ́fẹ́
> Tí í ti ibi gegele
> Bá òkè jà

**5.0 Ìsọnísókí**

Nínú ìpín kẹta módù kínní yìí ni a ti kẹ́kọ̀ọ́ pé:

- Ìpo ńlá ni àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá wà pàápàá ní ọkàn àwọn tí ó ń bọ àwọn òrìṣà náà.

- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé “alágbàwí” ni àwọn òrìṣà jẹ́ láàrin àwọn àti Olódùmarè.
- Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn olùsìn máa ń bọ òrìṣà lóòrèkóòrè, síbẹ̀ wọn ní òye pé Olódùmarè ní àṣẹ àti agbára tí ó ju ti òrìṣà lọ.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Olódùmarè fún Ọbàtálá ní àṣẹ láti mọ ẹ̀dá ènìyàn. Nígbà tí Ọbàtálá bá ti mọ ẹ̀dá tán ni Olódùmarè yóò wá fi ẹ̀mí sí i lára.
- Ọ̀rúnmìlà wà níbẹ̀ nígbà tí ẹ̀dá ènìyàn ń yan ìpín rẹ̀ lóde ọ̀run kí wọ́n tó wá sí ilé ayé, ìdí nìyí tí wọ́n fi ń pè é ní “Ẹlẹ́rìí Ìpín”
- Sátánì inú Bíbélì yàtọ̀ sí Èṣù tí ó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá. Èṣù jẹ́ òrìṣà tí o ní ìgboyà àti ọgbọ́n àrékérekè tí ó sì ní akíkanjú pẹ̀lú.
- Ògún ni ó lànà fún àwọn òrìṣà yòókù nígbà tí wọ́n ń bọ̀ láti ìkọ̀lé ọ̀run wá sí ìkọ̀lé ayé pẹ̀lú àdá irin rẹ̀.
- Ènìyàn ni Ṣàngó kí ó tó di òrìṣà. Ẹ̀dá líle ni, iná máa ń sẹ́ jáde lẹ́nu rẹ̀ tó bá ń sọ̀rọ̀. Ẹ̀rù ni Ṣàngó jẹ́ fún ẹnikẹ́ni, òǹrorò sì ni pẹ̀lú. Ṣàngo lágbára, ó lóògùn, ó fẹ́ràn àti máa fi agbára rẹ̀ hàn.

**Iṣẹ́ Síṣe**

i. Ṣàlàyé kíkún lórí òrìṣà kan tí wọ́n ń sìn nílùú rẹ.

ii. Pààlà láàrin Èṣù àti Sátánì

iii. Jìròrò lóri òrìṣà Ṣàngó

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adeoye, C. L. 1979. *Àṣà ati Ìṣe Yorùbá*. Ibadan: Oxford University Press

Daramola, O. Àti Jeje, A. 1975. Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá. Ibadan: Onibon-Oje Press

Falola, T. ati Akinyemi, A. (ed.) 2016. "Deities: The Òrìṣà" nínú *Encyclopedia of the Yorùbá.* Bloomington: Indiana University Press

**ÌPÍN KẸRIN: ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍPA ÀWỌN Ẹ̀MÍ ÀÌRÍ**

Nínú Módù yìí, ni a ó ti gbọ́ àlàyé nípa àwọn ẹ̀mí àìrí, akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yìí yóò ní òye kíkún nípa àwọn ẹ̀mí àìrí tí ó yí àwọn ènìyàn ká nílé ayé. A ówo àwọn ẹ̀dá tí à ń pè ní ẹ̀mí àìrí àti iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe.

**Àkóónú:**

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

5.0 Ìsọnísókí

6.0 Iṣẹ́ Síṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáàrà

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí a o sọ̀rọ̀ lórí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀mí àìrí. Béẹ̀ ni a ó pín àwọn ẹ̀mí àìrí yìí sí ìsọ̀rí.

## 2.0 Èròǹgbà

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

1. Jíròrò lórí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀mí àìrí.
2. Ṣe ìpínnsísọ̀rí àwọn ẹ̀mí àìrí.
3. Ṣàlàyé kíkún nípa àwọn ajogun gẹ́gẹ́ bí o ṣe farahàn nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀mí àìrí.

**3.0 Ìbéèrè Ìsaájú**

1. Ṣe àgbéyẹ̀wò ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀mí àìrí.

2. Àwọn ọ̀nà wo ni a le pín àwọn ẹ̀mí àìrí sí ní ilẹ̀ Yorùbá.

3. Jíròrò lórí àwọn ẹ̀mí àìrí tí a mọ̀ sí ajogun.

**4.0 Igbàgbọ́ Yorùbá Nípa Àwọn Ẹ̀mí Àìrí**

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé oríṣìí ẹ̀mí àìrí méjì ló wà. Àwọn náà sì ni ni ẹ̀mí àìrí rere àti ẹ̀mí àìrí búburú.

**Ẹ̀mí Àìrí Rere**

Ọ̀nà méjì gbòòrò ni a le pín ẹ̀mí àìrí rere sí: Òrìṣà, ìbọ/ alásekù/òkú Ọ̀run. Àwọn ẹ̀mí àìrí rere wọ̀nyí ni wọ́n máa ń ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn ènìyàn nígbà gbogbo àti lójoojúmọ́, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n le bínú sí ènìyàn, pàápàá ẹni tí ó bá kọ̀ láti ṣe ojúṣe rẹ̀ sí ẹlẹ́gbẹ́ rẹ̀ tàbí sí àwọn òrìṣà mìíràn. Láti ọ̀dọ̀ Ọ̀rúnmìlà tí ó jẹ́ agbẹnusọ fún àwọn òrìṣà àti àwọn òkú ọ̀run wọ̀nyí ni ènìyàn tí ń mọ̀ tí wọ́n bá ń bínú. Ẹbọ sì ni ètùtù tí a fi máa ń bẹ̀ wọ́n. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé àwọn òrìṣà wọ̀nyí kì í sábà bínú sí ènìyàn ṣùgbọ́n wọ́n wà láti dáàbòbò ènìyàn kúrò lọ́wọ́ àwọn ẹ̀mí àìmọ́ búburú yòókù.

**Ẹ̀mí Àìrí Búburú**

A tún le pín àwọn ẹ̀mí àìmọ́ búburú sí ọ̀nà méjì pẹ̀lú: Eníyán/Àjẹ́/Ẹlẹyẹ àti Ajogun, àwọn ẹ̀mí àìmọ́ búburú wà láti gba ire ọmọ ènìyàn tàbí láti yí kádàrá dáadáa tí ọmọ ènìyàn múwá sí ayé pada sí búburú. Àwọn ajogun ni ikú, àrùn, òfò, ẹ̀gbà, ẹ̀sẹ̀, èpè àti ẹ̀wọ̀n.

Ẹbọ ni a lè fi tu àwọn ajogun yìí lójú. Ní tí àwọn ẹlẹyẹ, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹbọ àti àlọ̀ kò ran àwọn ẹlẹyẹ, orí ẹni nìkan ló lè gbani lọ́wọ́ wọn. Òrìṣà tí a mọ̀ sí èṣù ni ó jẹ́ alágàta láàrin àwọn ẹ̀mí àìmọ́ búburú wọ̀nyí àti ọmọ ènìyàn, bákan náà, èṣù wà láti gba ènìyàn sílẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ènìyàn àti ajogun. Ní ti àwọn ìbọ, nígbà mìíràn tí a kò bá ṣe ohun tí o yẹ ki a ṣe fún àwọn aláṣekù, wọn le bínú. Ní báyìí, a ti mọ̀ pé onírúurú ni àwọn ẹ̀mí àìrí tó wà nílé-ayé àti pé iṣẹ́ wọn kò ṣe é fọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nítorí pé gbogbo wọn ni wọ́n fọwọ́-so-wọ́pọ̀ to ilé-ayé àti láti ṣàkóso ẹ̀dá ènìyàn.

**5.0 Ìsọnísókí**

Nínú ìpín kẹrin, módù kínní yìí ni a ti kẹ́kọ̀ọ́ pé:

- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹ̀mí àìrí méjì ló wà, ẹ̀mí àìrí rere àti búburú
- Ọ̀nà méjì gbòòrò ni a le pín ẹ̀mí àìrí rere sí: Òrìṣà, ìbọ/ alásekù/òkú Ọ̀run.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé àwọn òrìṣà wọ̀nyí kì í sábà bínú sí ènìyàn
- A tún le pín àwọn ẹ̀mí àìmọ́ búburú sí ọ̀nà méjì pẹ̀lú: Eníyán/Àjẹ́/Ẹlẹyẹ àti Ajogun
- Àwọn ajogun ni ikú, àrùn, òfò, ẹ̀gbà, èṣe, èpè àti ẹ̀wọ̀n.
- Ní ìgbà tí a lè fi ẹbọ tu àwọn ajogun, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹbọ àti ààlọ̀ kò ran àwọn ẹlẹyẹ, orí ẹni nìkan ló lè gbani lọ́wọ́ wọn.

**6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe**

i. Ṣe àgbéyẹ̀wò ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀mí àìrí.

ii. Àwọn Ọ̀nà wo ni a lè pín àwọn ẹ̀mí àìrí sí ní ilẹ̀ Yorùbá.

iii. Jíròrò lórí àwọn ẹ̀mí àìrí tí a mọ̀ sí ajogun.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoye, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Awólálu, J. O. 1973. *Yorùbá Sacrificial Practice. Journal of Religion in Africa*. Netherland: Brill Vol 5: issue 2. Pp. 172.

Ìdòwú, E.B. 1963. *Olódùmarè: God in Yorùbá Belief*. London: Longman.

Johnson, S. 2001. *History of the Yorubas from the Earliest Times to the Beginning of the British Protectorate*. Lagos: CSS Limited.

**ÌPÍN KARÙN-ÚN:ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍPA ÀSẸ̀YÌNWÁYÉ ÀTI ÀWỌN ABÀMÌ Ẹ̀DÁ**

Àkóónú

1.0 Ìfáárà

2.0 Èròǹgbà

3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa Àsẹ̀yìnwáye

4.2 àsẹ̀yìnwayé nípasè orúkọ

4.3 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ Àkúdààyà

4.4 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ àwọn Ayọ́runbọ̀

4.5 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ ìṣẹ̀run tó ti kú

4.6 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ àwọn Abàmì Ẹ̀dá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Nínú ìpín yìí, ni a ó ti máa sọ̀rọ̀ nípa àsẹ̀yìnwáyé, a ó tún mẹ́nuba àwọn abàmì ẹ̀dá. A ó sì ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ọ̀nà tí Yorùbá fi gbà pé àsẹ̀yìnwáyé wà.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn akẹ́ọ̀ọ́ yóó lè:

- Sọ ìtumọ̀ àsẹ̀yìnwáyé
- Ṣàlàyé bí Yorùbá ṣe mọ̀ pé àsẹ̀yìnwáyé wà
- Ṣàlàyé nípa àwọn abàmì ẹ̀dá

## 3.0 Ìbéèrè ìṣàájú

i. Ṣàlàyé ohun tí Yorùbá ń pè ní àsẹ̀yìnwáyé

ii. Sọ oríṣìríṣìí ohun tí ó fihàn pé àsẹ̀yìnwáyé wà ní àwùjọ Yorùbá

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa Àsẹ̀yìnwáyé àti Abàmì Ẹ̀dá

Yorùbá jẹ́ ẹ̀yà tí ó máa ń wo ṣàkún, tí wọn sì máa ń ṣe àkíyèsí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ àyíká wọn. Èyí ló fà á tí wọ́n fi ní ìmọ̀ tí ó gbòòrò lórí gbogbo ohun tí ó wà ní àyíká wọn, tí wọ́n sì ní ìrírí tí ó jinlẹ̀ nípa ìṣẹ̀lẹ̀ ojoojúmọ́, lára àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ìrírí wọ́n ń sọ nípa rẹ̀ ní àsẹ̀yìnwáyé àti àwọn abàmì ẹ̀dá. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ikú kìí ṣe òpin ẹ̀dá, èyí túmọ̀ sí pé tí ènìyàn bá kú kò parí síbẹ̀, wọn ní ìgbàgbọ́ pé ẹni tí ó bá ti kú máa ń wẹ̀yìn wò. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé òkú ọlọ́mọ kìí sùn gbàgbé. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé lẹ́yìn ti ẹnìkan tí ó ti dàgbà bá kú, ó ṣẹ̀ṣẹ̀ bẹ̀rẹ̀ láti máa mojútó àwọn ẹbí àti ọmọ tí ó fi sílẹ̀ lákọ̀tun ni, wọ́n máa ń sọ pé 'òkú ọlọ́mọ kìí sùn kó rọ̀ mọ́ igi ìgbàgbé'. Láti ìgbà ìwásẹ̀ kí ẹ̀sìn àjòjì tóó dé ni Yorùbá ti gbàgbọ́ pé ikú kìí ṣe òpin ẹ̀dá, èyí sì máa ń farahàn ní ìgbà tí àwọn ẹlẹ́sìn ifá bá ń sun ìyẹ̀rẹ ifá, wọ́n máa ń sọ pé:

> Awo kìí kú
> Awo kìí rùn
> Awo íí papò dà ni.

Èyí fihàn pé ikú awo kìí ṣe òpin ẹ̀mí rẹ, pé awo lọ sí ibòmíràn ni, èyí túmọ̀ sí ìsípòpadà. Síwájú síi, Yorùbá nínú ìrírí wọn, wọ́n gbàgbọ́ pé ẹni yòówù kí ó jẹ́, yálà ọkùnrin tàbí obìnrin tí ó ti dàgbà, tí ó bá kú, kìí fi ilé sílẹ̀, yóò máa wá bẹ ilé wò láti tọ́jú ilé. Ìdí nìyìí tí àwọn Yorùbá kìí fii sin òkú sí ẹ̀yìn odi, àfi inú ilé, ní àárín ọ̀ọ̀dẹ̀ tàbí yàrá ni

wọn máa ń sin òkú sí láyé àtijọ́. Ìdí ni pé, wọn gbà pé ẹni tí ó kú náà yóó ṣì máa wà láàárín wọn.

Bákan náà ni àwọn Yorùbá ni ìgbàgbọ́ nínú àwọn ẹ̀dá kan bíí iwin, ọ̀rọ̀, àbíkú àti àwọn mìíràn, pé wọn ń gbé láàárín àwọn ọmọ ènìyàn, wọ́n gbàgbọ́ pé ènìyàn ni púpọ̀ nínú àwọn abàmì ẹ̀dá yìí tẹ́lẹ̀, kí wọ́n tó padà di irú ẹ̀dá ti wọn dì. Èyí nìkan kọ́, àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé kò sí ẹ̀dá ohun tí àwọn ẹ̀dá yìí kò lè ṣé, nítorí irú ẹ̀dá ti wọn jẹ́. Àwọn akíyèsí wọ̀nyí ni ó sì mú kí àwọn Yorùbá gbàgbọ́ nínú àṣẹ̀yìnwáyé.

## 4.2 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ orúkọ

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ní pé bí ẹnìkan bá dàgbà, tí ó dògbó, tí o fi ọwọ́ rọrí kú, ó tún lè padà wá sí ayé nípa yíyà sọ́dọ̀ ọmọ bíbí inu rẹ̀, tàbí sọ̀dọ̀ ọmọọmọ rẹ̀, bí ó bá fẹ́. Tí wọ́n bá ti ń sin òkú náà ni àwọn àgbà tí ó wà níbẹ̀ yóó ti máa sọ fún òkú pé kí ó tètè dẹ́yìn bọ sí ilé ayé, kí ó wa yà lọ́dọ̀ ọmọ rẹ̀. Èyí ni pé tí òkú kan bá kú, tí ọmọ òkú yìí, tàbí ọmọọmọ rẹ̀ bá bímọ̀ lẹ́yìn tí ìyá tàbí bàbá tí ó ti darúgbó náà bá kú, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ọmọ ti a bí yìí ni bàbá tàbí ìyá tí ó kú náà. Ìgbàgbọ wọn tún ni pé ìyá tàbí bàbá náà ni ó padà wá sí ọ̀dọ̀ ọmọ rẹ̀. Orúkọ tí Yorùbá máa ń sọ irú ọmọ tí a bí náà tí ó bá jẹ́ obìnrin ni Ìyábọ̀, Yétúndé, Yéwándé, tàbí tí ó bá jẹ ọkùnrin, wọ́n a sọ orúkọ ọmọ náà ni Babátúndé tàbí Babájídé. Èyí ni láti fihàn pé òkú tí ó kú náà ló dẹ̀yìnbọ̀ tí ó sì yà sí ọ̀dọ̀ àwọn ọmọ rẹ̀.

## 4.3 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ Àkúdàáyà

Àkúdàáyà ni àwọn Yorùbá mọ̀ sí òkú òròjú, tí ó fi ọjọ́ ọlọ́jọ́ lọ, èyí ni àwọn tí ó kú láìtọ́jọ́, tí o sì gba omijé lójú ènìyàn. Tí irú ẹni bẹ́ẹ̀ bá kú, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé irú òkú bẹ́ẹ̀ kì í lọ sí ọ̀run tààrà, wọ́n á máa rìn káàkiri. A tilẹ̀ gbọ́ pé irú òkú bẹ́ẹ̀ tún lè lọ sí ibòmíràn láti lọ lo ìyókù ọjọ́ ayé rẹ̀ pé níbẹ̀, irú àwọn òkú báyìí ni à ń pè ni Àkúdàáyà.

Nígbà mìíràn òkú tí ó bá kú ikú òjijì lè lọ fi ara hàn mọ̀lẹ́bí tàbí ọ̀rẹ́ tí kò tíí mọ̀ pé ó ti kú, tí ó bá ríi pé ẹni náà tún ti mọ̀ yóó tún gba ibòmíràn lọ. Tí Àkúdàáyà mìíràn bá lọ sí ìlú mìíràn, ó lè máa ṣòwò, kí ó gbéyàwó kí ó sì tún bímọ, níwọ̀n ìgbà tí kò bá ti si ẹni tí

ó mọ̀ ọ́n, ó lè wà níbẹ̀ di ọjọ́ ogbó rẹ̀, ṣùgbọ́n ní kété tí ó bá tún ti rí ẹni tí ó mọ̀ ọ́n tí wọ́n sì tú àṣírí rẹ̀, àìròtẹ́lẹ̀ ní yóó di àwátì, tí ẹnikẹ́ni kò sì tún ní rí i mọ́.

Púpọ̀ ìgbà ni àwọn obìnrin máa ń kó ọmọ òkú wá fún òbí ọkùnrin bẹ́ẹ̀, nígbà ti ìyàwó bá ń yọ ọkọ lẹ́nu pé, àfi dandan kí òun mọ àwọn òbí rẹ̀, ó lè ni kí wọ́n nìsó òun fẹ́ ya ibìkan, yóó nàka ilé fún wọn. Nígbà tí ìyàwó àti ọmọ bá yọjú sílé, tí wọ́n sì fi ojú orórì ọkọ rẹ̀ hàn an ni yóó tó mọ̀ pé, òkú ni òun fẹ́. Irú ọkùnrin bẹ́ẹ̀ kò níí yọjú sílé, obìnrin náà kò sì tún níí gbúròó ọkọ rẹ mọ́.

## 4.4 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ Ayọ́runbọ̀

Tí àwọn òkú kan bá kú, yalà nípa àìsàn tàbí ìjàǹbá, wọ́n tún lè jí padà sáyé lẹ́yìn bíi wákàtí díẹ̀ tàbí ọjọ́ díẹ̀, irú àwọn wọ̀nyí ni àwọn Yorùbá ń pè ní ayọ́runbọ̀. Púpọ̀ ìgbà ni àwọn tí wọn bá kú tí wọn sì jí sáyé padà máa ń sọ ìrírí wọn nígbà tí wọn kú, wọ́n máa ń sọ oríṣìríí̀ṣìí nǹkan tí wọ́n rí ni ọ̀run tàbí lẹ́nu bodè ọ̀run, nígbà tí wọ́n bá padà jí sáyé, ẹlòmíràn máa ń lo àìmọye ọdún lẹ́yìn náà, kí ó tó pàpà kú, èyí túbọ̀ ń fi ìdí ìgbàgbọ́ Yorùbá nínú àsẹ̀yìnwáyé múlẹ̀ sí i.

## 4.5 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ Ìṣẹ̀run tó ti kú

Àwọn òbí ẹni ni Yorùbá máa ń pè ní ìṣẹ̀run ẹni. Tí òkú bá kú ní ayé àtijọ́, àwọn ọmọ máa ń gbé òkú yí ilé po. Ìdí ni pé kí ó lè rántí láti máa ṣe alàábò ilé. Ní ọjọ́ keje tí òkú bá kú, èyí ni à ń pè ní ọjọ́ ìje tàbí ọjọ́-ìkóje. Ọjọ́ yìí ni egúngún òkú yóó jáde pẹ̀lú àwọn egúngún mìíràn. Ẹni tí ó gà, tàbí rí bákan náà pẹ̀lú ẹni tó kú ni yóò wá nínú àgọ́, ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ẹni tó kú gan-an ló tọ̀run wáyé láti wá dúpẹ́ lọ́wọ́ àwọn ọmọ rẹ̀, fún ẹ̀yìn òun tí wọ́n ti ń túnṣe láti ìgba tí òun ti di ará ọ̀run. Eégún náà yóó sì máa ṣàdúrà fún gbogbo àwọn ọmọ. Àwọn èèyàn yóó máa rán eégún léti pé kí ó má gbàgbé àwọn ọmọ tí ó fi sílẹ̀, eégún náà yóó máa wí pé ‘kò sí nǹkan, ẹ ṣáà má jà, ẹ ṣeun, nǹkan kò nìí ṣe yín”.

Ará ọ̀run ni à ń pe àwọn egúngún tẹ̀lẹ̀ nítorí náà gbogbo ọmọ àti ẹbí ló gbà pé òbí wọ́n ni ó wá láti bẹ̀ wọ́n wò.Ọ̀pọ̀ ọmọ ló máa ń lọ sí ojú oórì bàbá tàbí ìyá wọn láti lọ ṣàdúrà, tàbí rán wọ́n létí pé kí wọ́n má gbàgbé ilé o àti àwọn ọmọ, nígbà tí ó bá ti di pé

ọ̀kan wọn ń fá sí òbí náà, gbogbo àwọn ìgbésẹ̀ ọlọ́kanòjọ̀kan wọ̀nyí ń fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ síwájú sí í pé àwọn Yorùbá gbàgbọ nínú àsẹ̀yìnwáyé.

## 4.6 Àsẹ̀yìnwáyé nípasẹ̀ àwọn abàmì ẹ̀dá

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé abàmì ẹ̀dá ni àwọn àbíkú, nítorí wọ́n máa ń kú tí a ó sì tún bi wọ́n padà láìmọye ìgbà, èyí fihàn pé ó ṣee ṣe kí òkú kú, kí ó tún padà wá sí ayé. Ìrírí àwọn Yorùbá ni ó jẹ́ kí wọ́n gbàgbọ́ pé àwọn ọmọ kan wà tí ó jẹ́ pé àbíkú ni wọn, kò sí bí a ṣe tọ́jú wọn tó, láìròtẹ́lẹ̀ ni wọn yóó tún padà sọ́run. Tí ọmọ bá kú àwọn òbí rẹ̀ lè gé ìka rẹ̀ kàn kúrò, tàbí kí wọ́n sún un jóná, ti irú òbí bẹ́ẹ̀ bá tún padà bí ọmọ, ọmọ náà kò níí ni ìka rẹ̀ pé, èyí tí wọ́n gé kò níí sí ni ọwọ́ rẹ̀. Ọmọ ti wọn sun jóná pẹ̀lú yóó dúdú kirikiri ni, èyí ló jẹ́ kí àwọn Yorùbá gbà pé abàmì ọmọ ni àwọn àbíkú jẹ́. Wọ́n tún máa ń pè wọ́n ní emèrè tàbí elérèé ọmọ, tí ó ni ẹgbẹ́ ọ̀run, torí ṣe ni wọ́n máa ń dajọ́ sí àsìkò ti wọ́n yóó padà lọ sí ààrín àwọn ẹgbẹ́ wọn ọ̀run.

Àwọn abàmì mìíràn bíi, ọ̀rọ̀, iwin, egbére àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ni àwọn Yorùbá tún gbà pé ẹ̀dá ènìyàn ni wọ́n, kí wọn tó yípadà di ẹ̀dá mìíràn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín karùn-ún lábẹ́ módù kínní yìí a ti kékọ̀ọ́ pe:

- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ikú kìí ṣe òpin ẹ̀dá, èyí túmọ̀ sí pé tí ènìyàn bá kú kò parí síbẹ̀, wọn ní ìgbàgbọ́ pé ẹni tí ó bá ti kú máa ń wẹ̀yìn wò
- Àwọn Yorùbá ni ìgbàgbọ́ nínú àwọn ẹ̀dá kan bíí iwin, ọ̀rọ̀, egbére àti àbíkú
- Àsẹ̀yìnwáyé máa ń jẹyọ nípasẹ̀ orúkọ
- Àsẹ̀yìnwáyé máa ń jẹyọ nípasẹ̀ àkúdààyá
- Àsẹ̀yìnwáyé máa ń jẹyọ nípasẹ̀ ayọ́runbọ̀
- Àsẹ̀yìnwáyé máa ń jẹyọ nípasẹ̀ ìṣẹ́run
- Àsẹ̀yìnwáyé máa ń jẹyọ nípasẹ̀ àwọn abàmì ẹ̀dá

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i.Kíni àsẹ̀yìnwáyé

ii. Sọ ohun tí o mọ̀ nípa Àkúdàáyà àti ìṣẹ̀run

iii. Kí ni ìyàtọ̀ tí ó wà láàrin ayọ́runbọ̀ àti Àkúdàáyá

iv. Ṣàlàyé bi àbíkú ṣe jẹ́ abàmì

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Ladele, et al. 2006. *Àkójọpọ̀ ìwádìí ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ibadan Gavima Press Ltd.

Owolabi, et. Al. 2001. *Ìjìnlẹ̀ Èdè àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá. Ibadan*; Evans publishers Ltd.

Ẹgbẹ́ Akọ́mọlédè Àti Àṣà Yorùbá Nàìjíríà, 1999. *Ẹ̀kọ́ Èdè Yorùbá Òde òní*. Ibadan. Macmillan: Nigeria publishers Ltd.

**MÓDÙ KEJÌ**

**Ìfáàrà**

Nínú módù kejì yìí ní a ó ti máa jíròrò nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá tí kò níí ṣe pẹ̀lú ẹ̀sìn wọn. Ní ìpín kínní, a sọ bí ọmọ ṣe jẹ́ pàtàkì tó láwùjọ Yorùbá, a ó tún ṣàlàyé nípa ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ọmọ. Ìpín kejì, a ṣe àgbéyẹ̀wò pàtàkì ẹwà ní ilẹ̀ Yorùbá àti ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ẹwà. Nínú ìpín kẹta a ṣàlàyé kíkún nípa èrò Yorùbá nípa owó àti ihà tí wọ́n kọ sí níní àti àìní owó ènìyàn. Ní ìpín kẹrin, a ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣìíríṣìí ọ̀rẹ́ tí ó wà, ipa tí ọ̀rẹ́ ń kó nínú ayé ẹ̀dá àti èrò àwọn Yorùbá nípa ọ̀rẹ́ yíyan. Ìpín karùn-ún, ní a ti sọ̀rọ̀ nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀san.

**ÌPÍN KÌÍNÍ: ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍPA ỌMỌ**

Àkòónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè ìsáájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    4.1 Pàtàkì ọmọ nínú ẹ̀yà Yorùbá
    4.2 Aájò ọmọ
    4.3 Díẹ̀ lára ohun tí Yorùbá fi ọmọ wé
    4.4 Díẹ̀ lára orúkọ tí ó fi èrò Yorùbá nípa ọmọ hàn
    4.5 Ìtọ́jú ọmọ
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé ìtọ́kasí

**Ìfáárà**

**1.0** Ní ìpín kìnní, módù kejì yìí a ó sọ bí ọmọ ṣe jẹ́ pàtàkì tó láwùjọ Yorùbá. A mọ ohun tí ó lè ṣe okùnfà àìrọ́mọbí a sì mọ aájò tí àwọn baba ńlá wa máa ń ṣe láti dènà àìrọ́mọbí. A tún ṣàlàyé àwọn ohun tí àwọn Yorùbá fi ọmọ wé, tí ó fi pàtàkì ọmọ àti èrò Yorùbá nípa ọmọ hàn. Bákan náà ni a sọ díẹ̀ lára orúkọ tí Yorùbá máa ń sọ ọmọ èyí ní àwọn orúkọ tí o fi èrò àti ìgbàgbọ́ wọn nípa ọmọ hàn. Ní ìparí, a ṣe àlàyé lórí ìtọ́jú ọmọ ní àwùjọ Yorùbá.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yìí yóó lè sọ:

Pàtàkì ọmọ láàárín àwọn Yorùbá.

Ṣàlàyé ìdí àti bí Yorùbá ṣe ń ṣe aájò ọmọ

Sọ díẹ̀ lára ohun tí Yorùbá fi ọmọ wé.

Dárúkọ díẹ̀ lára orúkọ Yorùbá tí ó fi èrò Yorùbá nípa ọmọ hàn

**3.0 Ìbéèrè ìṣáájú**

i. Sọ ìdí tí ọmọ fi jẹ́ pàtàkì nínú ẹ̀yà Yorùbá

ii.Ṣàlàyé bí Yorùbá ṣe máa ń ṣe aájò ọmọ

iii.Sọ méjì lára ohun ti Yorùbá fi ọmọ wé

**4.0 Ìbẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Pàtàkì Ọmọ Láarin Àwọn Ẹ̀yà Yorùbá**

Nínú gbogbo ẹ̀yà àti orílẹ̀èdè lágbàáyé, ẹ̀yà Yorùbá jẹ ọ̀kan nínú àwọn tí ó ka ọmọ sí púpọ̀, wọ́n sì gbàgbọ́ pé ẹni tí kò bá bí ọmọ kò rí ayé wá rárá, wọ́n tilẹ̀ máa ń sọ nípa ẹni tí kò bímọ tí ó fi kú pé, ó dàbí ejò tí ó kọjá lórí àpáta tí kò ní ipa kankan, àwọn Yorùbá ka ọmọ kún ẹ̀bùn pàtàkì láti ọ̀dọ̀ Olódùmarè. Tí ènìyàn bá ti gbéyàwó ni gbogbo

ẹbí ará àti ọ̀rẹ́ yóó ti máa gbàdúrà pé ẹ̀yìn ìyàwó kò níí mọ ẹní, èyí tí ó túmọ̀ sí pé, ní kété tí ìyàwó bá ti ń dé ilé ọkọ ni yóó fi inú soyún, ìrètí gbogbo ènìyàn ni pé, lẹ́yìn oṣù mẹ́sàn-án, kí wọ́n kí tọkọtaya kú ewu ọmọ. Ohun ayọ̀ àti ìdùnnú ni pé ìyàwó tí a ṣẹ̀ṣẹ̀ gbé kò mú oṣù tí ó wọlé ọkọ jẹ tí ó fi lóyún. Tí ìyàwó bá wọ ilé ọkọ tí ó tó bíi ọdún kan, ọdún méjì tí ìyàwó kò lóyún ìbànújẹ́ ni ó máa ń jẹ́ fún tọkọ tìyàwó àti ẹbí, pàápàá jùlọ ẹbí ìyàwó.

Kí ìdádúró láti bí ọmọ má báa ṣẹlẹ̀ ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń ṣe gbogbo ìwádìí àti ètùtù tí ó bá yẹ, kí á tó sin ìyàwó fún ọkọ rẹ̀ nílẹ̀ Yorùbá, nítorí wọ́n gbà ọmọ gẹ́gẹ́ bí èrè ìgbéyàwó. Lárá irú àwọn ètùtù wọ̀nyí ni **ifá ìyàwó** láti wádìí bí ìbágbépọ̀ tọkọtaya yóó ṣé rí, bóyá ìgbéyàwó wọ́n yóó ní oore nínú, tí yóó sì san wọ́n sówó, sọ́mọ, àlàáfíà àti àìkú tíí ṣe baálẹ̀ ọrọ̀.

Tí tọkọtaya kan bá ní ìdádúró ọmọ bíbí, oríṣìíríṣìí aájò ni àwọn Yorùbá máa ń ṣe fún irú tọkọtaya bẹ́ẹ̀ láti yanjú ìṣòro àìrọ́mọbí.

### 4.2 Aájò Ọmọ

Ó jẹ́ àṣà àti ìṣe àwọn babańlá Yorùbá láti máa ṣe aájò fún tọkọtaya tí ó bá ní ìdádúró ọmọ bíbí, aájò bẹ̀rẹ̀,nípa òògùn ṣíṣe, ẹbọ rírú tàbí ètùtù ṣíṣe. Bí wọ́n tí ń lọ sí ilé babaláwo ni wọ́n yóò máa wọ ilé adáunṣe tàbí oníṣègùn. Bí tọkọtaya ti ń jẹ jíjẹ, ni wọ́n yóó máa mu mímu, kò sí iye owó tàbí ohun-ìní tí ó lè ro wọ́n lójú láti fi sílẹ̀ kí wọ́n lè rí ọmọ bí.

Àwọn àyẹ̀wò ti àwọn oníṣègùn yóó ṣe ni láti wádìí bóyá àrùn wà lára ìyàwó tàbí ọkọ lára àwọn àrùn tí ó lè fa ìdádúró tàbí àìrọ́mọbí ni, àtọ̀sí, oyún ìju, ẹ̀yọ̀ọ, ṣọmúròrò àti ẹ̀dà.

Ọkùnrin ni ó sábà máa ń ni àrùn àtọ̀sí nípa ìbálòpọ̀ pẹ̀lú oríṣìíríṣìí obìnrin, àwọn adáhunṣe le ka àgbo fún ọkùnrin náà ti yóó mú àrùn yìí kúrò.

Ẹ̀yọ̀ọ; ni kìí jẹ́ kí nǹkan ọkùnrin dúró ní ìdí obìnrin. Àgúnmu tí obìnrin yóó máa mu àti ọṣẹ tí yóó fi máa fọ ìdí (taábà) ni a máa ń lò fún àrùn yìí.

Ṣọmúròrò: ni ó má ń mú kí ọmú obìnrin tóbi láìtíì jẹ́ pé ó lóyún. Àgbo-kíkà ni òògùn èyí, lẹ́yìn náà ni a ó gún oṣẹ fún un, tí yóò máa fi fọ ọmú sí inú igbá ìsúsẹ̀. Oríta ni yóò sì lọ máa da omi tí ó bá fi fọ ọmú náà sí.

Yàtọ̀ sí àwọn àrùn tí a dárúkọ yìí, òògùn mìíràn wà tí àwọn adáhunṣe yóó lò láti tọ́jú ọkọ àti ìyàwó, èyí ni láti dénà àrùnkárùn mìíràn tí ó bá tún fẹ́ yọjú.

Ìwádìí tún fihàn pé bí ayé tàbí àwọn àgbà (oṣó àti Àjẹ́) bá ń bínú, ó ṣeéṣe kí ọkọ àti aya má lè bímọ lásìkò, èyí ni pé wọ́n lè ní ìdádúró. Ó sì lè jẹ́ òbí ọkọ tàbí ìyàwó ni àwọn àgbà ń bínú sí, tí ó sì mu kí àwọn ọmọ máa jìyà àìmọ̀dí. Èyí yòówù tí ó lè jẹ́, àwọn adáhunṣe ni ó máa ń ka nǹkan ètùtù tí wọn yóò ṣe kí wọ́n lè rí ojúrere àwọn àgbà, kí wọ́n sì lè rí ọmọ bí.

Òmíràn ni, ṣíṣe àkíyèsí ifá ìdílé ọkọ, èyí túmọ̀ sì pé, ìyàwó lè ti ṣe aṣemáṣe tí ó lòdì sí ohun tí ọkọ fẹ́, bíí àgbèrè. Àfi ti obìnrin náà bá jẹ́wọ́ ẹni tí wọ́n jọ ṣe àgbèrè tí inú ọkọ sì yọ́ sí i; lẹ́yìn èyí ni wọn yóó ṣe àṣèjẹ fún obìnrin yìí wọn yóó sì ta àlè náà lójì (èyí túmọ̀ sí pé yóò san owó ìtanràn) kí obìnrin yìí lè rí ọmọ bí.

Ohun mìíràn ti ó tún yẹ láti mẹ́nù bà ni kí oyún obìnrin máa bàjẹ́, àwọn babańlá wa ní ọ̀nà tí wọ́n ń gbà so oyún kọ́, tàbí de oyún tí kò sì níí wálẹ̀ tàbí jábọ́ tití àsìkò àti bímọ yóó fi tó.

### 4.3 Díẹ̀ lára ohun tí Yorùbá fi ọmọ wé

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú pé ọmọ ṣe pàtàkì, ó ṣe kókó láwùjọ Yorùbá, àwọn Yorùbá fi ọmọ wé oríṣìíríṣìí nǹkan láti fi ìwúlò ọmọ àti bí ọmọ ṣe ṣe pàtàkì hàn.

**Àwọn ohun tí àwọn Yorùbá fí ọmọ wé:**

(i) **Aṣọ**: Yorùbá sàbá máa ń sọ pé, ọmọ láṣọ. Wọ́n gbàgbọ́ pé gẹ́gẹ́ bí aṣọ ṣe máa ń bo ìhòhò ẹ̀dá, bẹ́ẹ̀ náà ni ọmọ ṣé bo ìhòhò òbí. Ọmọ ni aṣọ tí kò jẹ́ kí a rí ìhòhò ẹni (òbí). Àwọn ènìyàn sì máa fi ń gba àdúrà pé ‘ayé kó níí já ọ sí ìhòhò”. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé, ẹni tí ọmọ rẹ̀ bá kú lójú ẹ̀mí rẹ̀, ayé ni ó já irúfẹ́

ẹni bẹ́ẹ̀ sí ìhòhò. Èyí ni ó fà á tí Yorùbá fi máa ń pé ọmọ ni aṣọ, wọ́n a máa sọ pé “Ọmọ laṣọ”.

(ii) **Adé**: Gẹ́gẹ́ bí a ti mọ pé ohùn pàtàkì ní adé jẹ́ fún àwọn ọba aládé. Èyí ni àmì ògo ti ó máa ń wà lórí ọba ti ọba bá gúnwà sí orí ìtẹ́. Ọba aládé kan kìí ṣe kí ó ma dé adé lórí ìtẹ́. Bí á bá sì ti rí adé ní orí ọba, ògo ọba náà yóó yọ, ìyí ni fún ọba, ọlá àti ọ̀wọ̀ sì ni fún ọba bẹ́ẹ̀, gbogbo ènìyàn ni yóó mọ̀ pé ọba aláṣẹ ni ti wọn yóó sì máa ké kábíyèsí wọ́n á máa kí irú ọba bẹ́ẹ̀ tọ̀wọ̀tọ̀wọ̀. Tí a bá wá ṣí adé kúrò lórí ọba àbùkù ni èyí túmọ̀ sí, èyí já sí pé a yẹpẹrẹ irú ọba bẹ́ẹ̀, kò sí iyì mọ́. Ògo ọba náà ti kúrò. Èyí ni Yorùbá fi gbà pé ọmọ ni adé orí fún òbí. Ọmọ ni ó ń gbé iyì àti ògo fún òbí. Ọmọ ni ó ń gbé iyì àti ògo fún ènìyàn. Ọmọ jẹ́ àpẹẹrẹ iyì, ọlá, ẹ̀yẹ àti ògo lára òbí. Bí ọmọ bá kú lọ́wọ́ òbí, ó túmọ̀ sí pé adé òbí bẹ́ẹ̀ ṣí dánù nìyẹn. Ọmọ ni ó ń gbé òbí nìyí, tí òbí fí ń ṣe bí ọba.

(iii) **Ìlẹ̀kẹ̀ ọrùn**: Bí ìlẹ̀kẹ̀ ṣe jẹ́ ohun àmúṣọ̀ṣọ̀ọ́, tí ó sì máa ń bu iyì àti ẹwà kún ẹni tí ó bá lò ó, bẹ́ẹ̀ ni ọmọ rí fún òbí. Ọmọ jẹ́ àmúyangàn fún òbí. Wọ́n tilẹ̀ máa ń sọ pé ọmọ ni <u>iyùn</u>. Iyùn jẹ́ ilẹ̀kẹ̀ ti ó wọ́n púpọ̀ tí ó sì jẹ́ pé láàárín àwọn gbajúmọ̀ obìnrin tí ó lówó lọ́wọ́ ni a ti lè rí ìlẹ̀kẹ̀ iyùn láyé àtijọ́. Ìlẹ̀kẹ̀ iyùn kìí ṣe ohun tí ó wọ́pọ̀ tàbí ohun tí a lè rí lọ́wọ́ ẹni tí kò jẹun kánú rárá. Àwọn olówó, ọlọ́rọ̀ tàbí àwọn olorì ọba ni ó máa ń sábà lo ìlẹ̀kẹ̀ iyùn. Ìdí nìyìí ti Yorùbá fi  fí ọmọ wé ìlẹ̀kẹ̀ iyebíye yìí, nítorí ó wọ́n púpọ̀, láti fihàn pé ọmọ ṣọ̀wọ́n fún òbí.

(iv) **Idẹ**:Yorùbá máa ń sọ pé ọmọ nidẹ, kí ni ìdí èyí? Ìdí ni pé ní ayé àtijọ́ idẹ wọ́n púpọ̀ láti rí. Ní ayé àtijọ́, idẹ, bàbà, òjé àti másúfù (irin gidi) wọ́n púpọ̀, kò rọrùn láti ṣe alábàápàdé wọn ní ọjà, àwọn olówó, ọlọ́rọ̀ àti ọlọ́lá ni wọ́n sábà máa ń ní wọn nílé (Adeoye, 2005:43). Nítorí pé idẹ wọ́n púpọ̀ láti rí ni Yorùbá ṣe máa ń fi ọmọ wé idẹ. Wọ́n gbà pé olówó kò lè rí ọmọ rà. Ọmọ jẹ́ ẹ̀bùn láti ọ̀dọ̀ Olódùmarè. Ọmọ ṣọ̀wọ́n púpọ̀, nítorí ẹni tí Ọlọ́run bá fún ni. Ìdí nìyìí tí Yorùbá fi ọmọ wé idẹ tí ó wọ́n púpọ̀ lásìkò ìgbà náà.

(v) **Díígí tàbí Jíígì:** Díígí jẹ́ ohun tí ènìyàn fi máa ń wo bi ènìyàn ṣe rí, tí a bá múra tán, tàbí ohun tí a lè fi yẹ ara wò bí a ṣe rí nígbàkúùgbà tí a bá fẹ wo àwòrán ara wa. Yorùbá gbà pé kò sí bí a ṣe lé wo ara wa nínú díígí tó, tí a lè mọ̀ bí a ṣe rí, àfi tí a bá bímọ. Ọmọ ni a fi lè mọ bí a ṣe rí nítorí, kò sí ni, ọmọ gbọ́dọ̀ jọ òbí ní ìwà àti ìṣe. Yorùbá tilẹ̀ máa ń pa òwe pé, bí ọmọ o jọ ṣòkòtò, yóó jọ kíjìpá. A lo ṣòkòtò àti kíjìpá gẹ́gẹ́ bíi àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ fún ọkùnrin àti obìnrin. Ṣòkòtò ni bàbá, kíjìpá sì ni ìyá. Ọkùnrin ní ó máa ń wọ ṣòkòtò, tí obìnrin sì máa ń sán kíjìpá ni ayé àtijọ́. Èyí túmọ̀ sí pé ọmọ gbọ́dọ̀ jọ ìyá tàbí bàbá rẹ̀, nígbà mìíràn ọmọ lè pín àwọn méjèèjì jọ. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé, nígbà tí a bá bí ọmọ sílẹ̀ àwòrán ara wa ni à ń rí. Ìdí èyí ni wọ́n fi máa ń pé ọmọ ni dîìígí. Orin ìbílẹ̀ Yorùbá kan fi ìdí èyí múlẹ̀:

> "Káyé ma fọ gíláasì mi o
> Ọmọ mi ni gílaàsí ti mo fi ń wojú
> Ọmọ mi ni gíláàsì ti mo fi ń ríran o
> Káyé ma fọ gílaàsí mi o.

(vi) **Ògo ọ̀la:** Yorùbá gbà pé ọmọ ni ògo ọjọ́ ọ̀la (ọjọ́ iwájú) òbí. Èyí ni pé, nígbà tí a bá dàgbà darúgbó, ọmọ ẹni ni yóó máa gbé ògo ìdílé, ìlú, àti orílẹ̀èdè ga. Tí ènìyàn bá ti dàgbà, ó lójú ohun tí ó lè ṣe tàbí ibi tí ó lè lọ, nítorí agbára yóó ti dínkù, ṣùgbọ́n ẹni tí ó bá ni ọmọ láyé, gbogbo ohun yòówù tí ó lè fẹ́ ṣe ọmọ ni yóó máa bá a ṣe. Èyí ni pé ọjọ́ iwájú irú ẹni bẹ́ẹ̀ tàbí òbí bẹ́ẹ̀ dára, nítorí ó rí ọmọ rán níṣẹ́.

(vii) **Àwòrán Èrè**: Yorùbá bọ̀ wọ́n ní:

> Iná kú ó feérú bojú
> Ọ̀gẹ̀dẹ̀ kú ó fọmọ rọ́pò
> Bí Aládi ó bá sí nílé
> Ọmọ níí jogún ẹbu

Ohun tí à ń sọ ni pé ọmọ ni ó máa ń gbèyìn òbí, nígbà tí òbí bá dàgbà darúgbó, tí ó sì re ibi àgbà ń rè, àwọn Yorùbá máa ń pa òwe pé ènìyàn kò sunwọ̀n láàyè, ọjọ́ a bá kú là á dère. Ère ni àwòrán tí a fi igi, amọ̀ tàbí irin gbẹ́ sílẹ̀ tí kò lè kú tàbí bàjẹ́. Ìtumọ̀ rẹ̀ ni pé, tí ènìyàn bá ṣì wà láyé púpọ̀ ènìyàn ni kìí mọ rírì irú ẹni bẹ́ẹ̀, ṣùgbọ́n ní kété tí ó bá ti kú, ní àwọn ènìyàn yóó máa sọ ohun rere tí ẹni náà ti ṣe. Wọ́n máa ń mọ rírì ènìyàn nígbà tí ó bá kú ju ìgbà tí ó wà láyé lọ. wọ́n á bẹ̀rẹ̀ sí níí ki oríkì, wọ́n á sì máa sọ nípa gbogbo iṣẹ́ rere tí ó gbé ilé ayé ṣe, ohun ti Yorùbá ń pè ni 'èrè' ni pé, irú ẹni bẹ́ẹ̀ nígbà mìíràn a di ohun ti gbogbo ayé ń fẹ wo àwòrán rẹ̀, tàbí gbọ́ nípa ohun tí ó ti gbé ilé ayé ṣe. Ní Yorùbá fi máa ń sọ pé ọjọ́ a bá kú làá dère. Tí ọmọ bá gbèyìn òbí, irú ọmọ bẹ́ẹ̀ ni àwọn ẹbí, ará àti ọ̀rẹ́ yóó máa rí tí wọn yóó sì máa fi rántí ẹni tí ó kú náà. Tí ó bá tilẹ̀ jẹ́ pé irúfẹ́ ọmọ bẹ́ẹ̀ jọ òbí rẹ̀ bíí ìmumu, àwọn ènìyàn kò níí lè gbàgbé ẹni tí ó kú náà bọ̀rọ̀, nítorí bí wọ́n ṣe ń rí ọmọ tí ó jọ bàbá tàbí ìyá rẹ̀ tí ó kú, ní wọn yóó máa rántí òbí rẹ tí ó ti kú.

## 4.4 Díẹ̀ Lára Àwọn orúkọ tí ó fi Èrò Yorùbá nípa ọmọ hàn

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ ṣáájú pé, Yorùbá ka ọmọ sí ẹ̀bùn pàtàkì láti ọ̀dọ̀ Olódùmarè, wọn gbìyànjú láti fí bí ọmọ ṣe ṣe pàtàkì tó hàn nínú àwọn orúkọ tí wọ́n ń sọ ọmọ, àwọn orúkọ yìí fi ìgbàgbọ́ àti èrò Yorùbá nípa ọmọ múlẹ̀ sí i ni. Àwọn orúkọ bíi:

Ọmọ́wùmí - Èyí ni pé ọmọ jẹ́ ohun tí ó wu ènìyàn

Ọmọ́yẹmí - Kò sí ẹni tí ó bímọ, tí a sì ń fi orúkọ ọmọ náà pè é ti inú rẹ̀ kò níí dùn, nítorí náà gbogbo òbí ni ọmọ yẹ

Ọmọ́yalé - Tí àwọn òbí bá ń retí àti bí ọmọ tí wọn sì jàjà rí ọmọ náà bí, wọn a máa sọ orúkọ rẹ̀ ní Ọmọ́yalé.

Ọmọ́boríowó - Èyí ni orúkọ tí ó fi ìgbàgbọ́ Yorùbá hàn nípa pàtàkì owó àti ọmọ, orúkọ yìí túmọ̀ sì pé ọmọ ju owó lọ.

Ọmọ́tóóyọ̀sí - Orúkọ yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé nǹkan ayọ̀ ni ọmọ bíbí jẹ́, àti pé àrídunnú ni ọmọ́ jẹ́ fún òbí

Ọmọ́làjà - Tí ìjà bá ń ṣẹlẹ̀ láààrín ẹbí, tàbí ọkọ àti aya, tí aboyún bá bímọ lásìkò ìgbà náà, Ọmọ́làjà ni a ó sọ irú ọmọ bẹ́ẹ̀, nítorí pé kò sí bí ìjà ṣe le wà, tí àwọn ènìyàn sì ń yan ara wọn ni odì, tí ẹnìkan nínú wọn bá bímọ, ọmọ ni yóó parí rẹ̀, wọ́n gbọ́dọ̀ yọ̀ fún ọlọ́mọ.

Ọmọladé - Bí adé ṣe jẹ́ ohun pàtàkì sí ọba, tí ó sì ń fi ọba hàn bíi olórí àti aláṣẹ, bẹ́ẹ̀ ni, ó n fi iyì àti ẹ̀yẹ fún ọba, tí ó bá dé e. Adé jẹ́ àmì pàtàkì tí ó fi ọba hàn láààrin ẹgbẹlẹ́gbẹ̀ ènìyàn. Gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀ ni ọmọ fi iyì àti ẹ̀yẹ fún òbí.

Ọmọ́tánbàjẹ́ - Tí wọ́n bá ti ń fi ojú agan wo ẹnìkan, tí ó bá sì bí ọmọ, wọn a sọ ọmọ náà ni Ọmọ́tán ìbàjẹ́. Èyí ni pé ọmọ máa ń gbọn ẹ̀sín, àbùkù tàbí ìbàjẹ́ kúrò ní ara òbí.

Ọmọ́gbémga - Yorùbá gbà pé ọmọ ni ó máa ń gbé òbí rẹ ga, tí ó sì máa ń bu iyì kún òbí.

Ẹ̀bùnlọmọ - Orúkọ yìí fihàn pé, Ẹ̀bùn láti ọ̀dọ̀ Olódùmarè ni ọmọ jẹ́.

Ọmọlẹwà - Èyí fihàn pé, ọmọ ni ó jẹ ẹwà fún òbí, ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ọmọ ni ẹwà ara òbí.

## 4.5 Ìtọ́jú Ọmọ

Yorùbá ka ọmọ sí pàtàkì, nítorí ìdí èyí, wọ́n máa ń ṣe ìtọ́jú ọmọ, nítorí wọn ka ikú ọmọ sí àdánù tí ó ga jùlọ. Kí àìsàn tàbí ikú ọmọ má baà ṣẹlẹ̀ ni wọn ṣe ka ìtọ́jú ọmọ sí púpọ̀. Kété ti obìnrin bá ti bí ọmọ, pàápàá tí ó bá jẹ àkọ́bí ọmọ, irú obìnrin bẹ́ẹ̀, ìyá-ìyáwó ni ó máa ń ṣe ìtọ́jú ọmọ ní ilẹ̀ Yorùbá. Tí ìyá-ìyáwó bá ti kú nìkan ní ìyá ọkọ lè máa tọ́jú ọmọ, ìya-íyá ọmọ ni yóó máa rọ ọmọ ni àgbo, gbé ọmọ pọ̀n, já ewé àti egbò tí yóó sì máa fi rọ ọmọ, láti dènà àìsàn, yálà gìrì tàbí jẹ̀wọ́jẹ̀wọ́ àti àwọn àìsàn mìíràn tí ó lè fẹ́ ṣe ọmọ.

Tí àìsàn bá ń ṣe ọmọ, onísègùn, babaláwo, òrìṣà àti ìyá-ìyá ọmọ níí bá ni wo ọmọ ní ayé àtijọ́ ara ìtọ́jú ọmọ ní kí ìyá ìyá ọmọ lo gbogbo egbògi àti òògùn fún ọmọ ní àkókò àìsàn gẹ́gẹ́ bí oníṣègùn tí là á kalẹ̀. Yàtọ̀ sí pé àìsàn ń ṣe ọmọ ìkókó, oríṣìíríṣìí agbo ni ọmọ yóó máa mu. Ní ayé àtijọ́ àgbo wọ̀bọ́, àgbo jẹ̀dí, àgbo eyín, àgbo gìrì, àgbo ikọ́, àgbo ibà àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ, ní àwọn babańlá wa fi ń tọ́jú ọmọ. Bí ọmọ bá ti ń tó ọmọ ọdún márùn-ún sí mẹ́fà ni wọ́n yóó máa dín àgbo lílò fún ọmọ kù.

Ohun tí ó tún ṣe pàtàkì fún ìtọ́jú ọmọ ni oúnjẹ aṣara lóore fífún ọmọ lásìkò.Òògùn amọ́mọdàgbà ni oúnjẹ jẹ́. Lẹ́yìn tí ọmọ bá ti fi ọmú mímu fún bíi oṣù mẹ́fà, ẹ̀kọ mímu tún ní oúnjẹ mìíràn fún ọmọ ọwọ́ ní ilẹ Yorùbá láyé àtijọ́. Pípò ni wọ́n máa ń po ẹ̀kọ fún ọmọ mu. Kẹ̀rẹ̀ kẹ̀rẹ̀ wọ́n a máa fọ́ ẹ̀kọ pẹ̀tẹ̀ (ẹ̀kọ jíjẹ) láti fi nu ọmọ, tí ó bá fi máa di bí oṣù mẹ́sàn-án sí ọdún kan, wọ́n a máa nu ọmọ ni ọkà pẹ̀lú ọbẹ̀ àti àwọn oúnjẹ òkèlè mìíràn.

Ìwúlò aṣọ kò kéré lára ohun tí Yorùbá fi ń tọ́jú ọmọ, aṣọ tí ó bo ara àti orí ọmọ ni a máa ń wọ fún ọmọ ìkókó, aṣọ yòówù tí ọmọ bá sì ń wọ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí ó mọ́.

Àyíká tí ó mọ ni ń ṣe atọ́kùn fún àlàáfíà, nítorí náà àyíká tí a bá ti ń ṣe ìtọ́jú ọmọ gbọ́dọ̀ mọ́ tónítóní. Ìbáwí ní àsìkò tí ó yẹ jẹ ọ̀nà kan pàtàkì tí Yorùbá ńgbà láti tọ́jú ọmọ. Yorùbá kì í fa ọwọ́ ìbáwí sẹ́yìn fún ọmọ, èyí gan-an ni àmójúto tí ó ṣe pàtàkì fún ọmọ. Bí ọmọ bá ṣe ń dàgbà ni yóó máa kọ́ ẹ̀kọ́ tíí sọ ènìyàn di ọmọlúàbí. Àkókò tí ọmọ bá ń dàgbà ni wọn yóó máa kọ́ ọ bí a ti ṣe ń bọ̀wọ̀ fún àgbàlagbà. Bí a ṣe ń kí àgbàlagbà láàárọ̀ tí a bá jí àti ìkíni lóríṣìrííṣi fún ìgbà, àkókò àti onírúurú ìṣẹ̀lẹ̀. A ó kọ́ ọmọ pé ọmọdé kìí dá sí ọ̀rọ̀ àgbàlagbà, àti pé, ọmọdé ní láti yẹra bí àwọn àgbà bá wà ní ìjókòó tí wọ́n ń sọ̀rọ̀. Bí a bá

pàdé àgbàlagbà tí ó gbé ẹrù, ọmọdé gbọ́dọ̀ ran àgbà lẹ́rù, kí ó bá a gbé ẹrù náà. Kíkọ́ bí a ṣe ń jókòó, tí ó bájẹ́ ọmọbìnrin pé, kò gbọdọ̀ fẹ ojú ara sílẹ̀. Tí ọmọ bá fẹ́ jẹun, a kìí kọ́kọ́ mú ẹran jẹ, ẹran ni ọmọdé máa ń jẹ gbẹ̀yìn, ọmọdé kò gbọ́dọ̀ wo àgbà lójú tí a bá ń jẹun tàbí nígbà ti àgbà bá ń bá ọmọ wí.

Yorùbá kóríìra kí ọmọ jẹ́ olójúkòkòrò tàbí olè. Ìdí nìyìí ti wọ́n fi gbà pé, ti ọmọ bá ń jẹun, òkèlè rẹ̀ kò gbọdọ̀ tóbi, kò gbọdọ̀ ṣáájú àgbà jẹ ẹran, bẹ́ẹ̀ ni kò gbọdọ̀ jẹ ẹran, àfi tí ó bá jẹun tán. Gbogbo èyí ń kọ ọmọ ni ìtẹ́lọ́rùn, kí ó má jẹ wọ̀bìà tàbí olè; nítorí ẹni bá jalè ló ba ọmọ jẹ́.

Ẹ̀kọ́ iṣẹ́ ṣíṣe fún ọmọ ṣe pàtàkì, Yorùbá máa ń fi iṣẹ́ ṣíṣe kọ́ ọmọ, láti ìgbà tí ọmọ bá ti kéré ni yóó ti máa ba ìyá rẹ ṣe iṣẹ́ kéékèèké ni inú ilé, tí ó bá jẹ́ ọmọbìnrin tí ó bá sì jẹ ọkùnrin láti bí ọmọ ọdún márùn-ún ni yóó ti máa tẹ̀lé bàbá ìyá rẹ̀ lọ sí oko. Yorùbá korò ojú sí ọ̀lẹ, wọ́n máa ń sọ pé ẹni bí ọ̀lẹ kò rí ọmọ bí àti pé ìṣẹ́ kìí pa ni àìṣe rẹ̀ ni àbùkù.

Gbogbo àwọn ẹ̀kọ́ wọ̀nyí ni ó ń sọ ọmọ di ọmọlúàbí tí yóó jẹ́ kí ọmọ wúlò fún ara rẹ̀, òbí àti àwùjọ ni ọjọ́ iwájú, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ọmọ tí a kò bá kọ́ ni yóò gbé ilé tí a bá kọ́ tà bí ó bá di ọ̀la èyí ni wọn kò ṣe fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ìtọ́jú àti ìbáwí ọmọ, kí ọmọ lè jẹ́ ẹni tí ó ṣe é fi ẹ̀yìn sílẹ̀ fún nítorí wọ́n gbàgbọ́ pé ọmọ ni ìgbẹ̀yìn ọlà.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín kìnní lábẹ́ módù kejì yìí a ti kékọ̀ọ́ pe:

- àwọn ẹ̀yà Yorùbá jẹ ọ̀kan nínú àwọn ẹ̀yà tí ó ka ọmọ sí púpọ̀
- àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹni tí kò bá bí ọmọ kò rí ayé wá rárá
- àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹni tí kò bímọ tí ó fi kú kò ní ipa kankan
- àwọn Yorùbá ka ọmọ kún ẹ̀bùn pàtàkì láti ọ̀dọ̀ Olódùmarè.
- àwọn Yorùbá máa ń fí pàtàkì ọmọ hàn nínú àwọn orúkọ tí wọ́n ń sọ ọmọ
- Díẹ̀ lára ohun tí àwọn Yorùbá ń fi ọmọ wé ni aṣọ, ìlẹ̀kẹ̀, iyùn àti dííg í
- Ìgbàgbọ́ àwon Yorùbá pé ọmọ ni ìgbẹ̀yìn ọ̀la ni wọn kò ṣe fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ìtọ́ju àti ìbáwí ọmọ.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Kí ni àwọn ohun tí ó lè ṣe okùnfà àìrọ́mọbí fún obìnrin.

ii. Yàtọ̀ sí àwọn orúkọ tí a mẹ́nubà, sọ orúkọ márùn-ún mìíràn tí ó fi èrò Yorùbá nípa ọmọ hàn.

iii. Ṣàlàyé ìtọ́jú ọmọ ni àwùjọ Yorùbá.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adeoye, C.L. 2005. *Àṣà àti ìṣe Yorùbá.* Ibadan University Press Plc.

Ládélé et al. 2006. *Àkójọpọ̀ ìwádìí ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ibadan Gavima Press Ltd.

Johnson 1921. *History of the Yorùbá*. Lagos C.M.S

Ganiyu, W. 2009. *Bawò Àṣà àti Litíréṣọ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn. Graville publishers.

**ÌPÍN KEJÌ: ÌGBÀGBỌ́ ÀWỌN YORÙBÁ NÍPA ẸWÀ**

**Ìfáàrà**

Nínú ìpín yìí, a ṣe àgbéyẹ̀wò pàtàkì ẹwà ní ilẹ̀ Yorùbá. Akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yóò ní òye kíkún nípa ìbáṣepọ̀ tí ó wà láàárín ẹwà àti ìwà, oríṣìí ọ̀nà tí a lè gbà gbé ẹwà yọ. Bákan náà, a wó ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ẹwà nípa ṣíṣe àlàyé ojú tí wọ́n fi ń wo ẹni tí ó bá lẹ́wà. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe àyẹ̀wò oríṣìíríṣìí ìpèdè tí ó jẹmọ́ ẹwà.

**Àkóónú**


1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

- 4.1 Ẹwà Ṣíṣe
- 4.2 Aájò Ẹwà Ṣíṣe
- 4.3 Oríṣìí Ẹwà Gẹ́gẹ́ bí Ìgbàgbọ́ Yorùbá
- 4.4 Díẹ̀ Lára Àwọn Ìpèdè Tí ó Jẹmọ́ Ẹwà
- 4.5 Ẹwà Ṣíṣe Lóde Òní

5.0 Ìsọnísókí

6.0 Iṣẹ́ Síṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 Ìfáàrà

Ìpín yìí ṣe àfihàn ẹwà ṣíṣe gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe hàn nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe àyẹ̀wò ọ̀nà tí à lè gbà ṣe aájò ẹwà. A ó tọ́ka sí oríṣìíríṣìí ọ̀ṣọ́ ara èyí tí àwọn Yorùbá ń lò láti fi gbé ẹwà wọn laruge. A ó tún ṣe àyẹ̀wò díẹ̀ nínú àwọn ìpèdè tí ó jẹmọ́ ẹwà.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- Ṣàlàyé ẹwa ṣíṣe láààrín àwọn Yorùbá
- Tọ́ka sí ìbáṣepọ̀ tí ó wà láààrí ẹwà àti ìwà
- Lè dárúkọ ohun tí Yorùbá ń ṣe láti bu ẹwà kún ara

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

a) Kíni ẹ̀wà?
b) Dárúkọ oríṣìí ọ̀nà mẹ́ta ti àwọn obìnrin lè gbà bu ẹwà kún ara wọn.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ẹwà Ṣíṣe

Ẹ̀yà Yorùbá jẹ́ ẹ̀yà tí ó gbáfẹ́ tí ó sì gbádùn kí ènìyàn tún ara ṣe kí ó sì ṣe é rí ní àwùjọ. Yorùbá gbà pé ẹ̀bùn ni ẹwà. Wọ́n gbà pé tí ènìyàn bá ní ẹwà àtọ̀runwá kò ní nira láti ṣe aájò tí yóò gbé ẹwà náà yọ. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ìfẹ́ Olódùmarè ni láti jẹ́ kí obìnrin lẹ́wà ju ọkùnrin lọ. Èyí ló ṣe ṣe pàtàkì fún obìnrin láti tọ́jú ara dáadáa. Yorùbá ka obìnrin tí kò bìkítà láti ṣe ìtọ́jú ara rẹ̀ lọ́nà tí ó lè gbé ògo ẹwà yọ sí ọ̀bùn.

Ẹwà nínú ìṣe àwọn Yorùbá níṣe pẹ̀lú Òrìṣà-ńlá nítorí wọ́n gbà pé òun ni ó mọ ẹ̀dá tí ó sì bu ẹwà kún wọn. Bákan náà ni wọ́n ní ìgbàgbọ́ pé àwọn tí ó bá burẹ́wà jẹ́ ẹ̀dá tí Òrìṣà-ńlá fẹ́ràn, èyí ni wọ́n fi ń pè wọ́n ní “Ẹni Òrìṣà”.

Ẹwà nínú èrò Yorùbá kọjá kí ènìyàn dùn ún wò lójú. Kí Yorùbá tó lè gbà pé ẹnì kan ní ẹwà, irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ gún régé ní gbogbo ọ̀nà. Ìṣesí, ìsọ̀rọ̀sí àti ìrísí rẹ̀ gbọ́dọ̀ dáyàtọ̀. Ẹwà láìsí ìwà rere ni àwọn Yorùbá korò ojú sí, èyí sì jẹyọ nínú ìpèdè ìsàlẹ̀ yìí:

Ìwà lẹwà
Mórí lọ má mẹ́wà lọ

Òòjọ́ lẹwà á bọ̀
Orí níí bá ni gbélé ọkọ
Ikú ẹwà níí pọ̀kín
Ikú ara ríre ní podídẹ
Ọmọ dára ó dẹjọ́
Ọmọ tí kò sunwọ̀n
Ọ̀dẹ̀dẹ̀ ìyá rẹ̀ níí pẹ́ sí          (Akínyẹmí 1989:116)

Tọkùnrin tobìnrin ni ó máa ń ṣe aájò ẹwà nílẹ̀ Yorùbá ṣùgbọ́n àwọn obìnrin ni ó ń káràmásìkí ẹwà ṣíṣe jù lọ. Bí àpẹẹrẹ, ni àtijọ́, tọkùnrin tòbìnrin ni ó ń lé tìíró kí ojú wọn lè gún régé.

## 4.2 Aájò Ẹwà Ṣíṣe

Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọkùnrin gbọ́dọ̀  dùn ún wò, wọn kò gbọdọ̀ tẹpẹlẹ mọ́ ẹwà ṣíṣe. Èrò Yorùbá ni pé alágbèrè ni ọkùnrin tí ó bá kára mọ́ aájò ẹwà bí i obìnrin. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn Yorùbá ǹ gbà láti bu ẹwà kún ara kí wọ́n sì gbé ẹ̀wà náà yọ. Ipa àtiṣe aájò ẹwà ló bí ìtọ́jú orí, etí, eyín, ọrùn, ẹ̀rẹ̀kẹ́, oríṣìíríṣìí aṣọ wíwọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

- **Ìtọ́jú Orí**

Ní àtijọ́ àwọn ọkùnrin máa ń fá orí ni. Àtọmọdé àtàgbà ni ó ń fá orí. Fífá orí kodoro jẹ́ àṣà àdáyèbá fún àwọn àgbàlagbà ọkùnrin kí ó tó di pé oríṣìíríṣìí àrà mìíràn bẹ̀rẹ̀ sí í gbilẹ̀. Yàtọ̀ sí orí fífá, ọkùnrin ń gẹ jòǹgọ̀rì. Jòǹgọ̀rì yìí ni kí ọkùnrin gẹ ẹ̀gbẹ́ orí méjèèjì ní kodoro kí irun sì wà ní ààrín orí láti ìpàkọ́ dé iwájú. Àwọn ọkùnrin máa ń dá ààsó bákan náà. Irúfẹ́ irun yìí máa ń dà bí òṣùpá mẹ́tá ní orí. Ọ̀kan yóò wà ní iwájú, èkejì yóò wà ní ààrín nígbà tí ẹ̀kẹta yóò sì wà lẹ́yìn.

Fífá orí apákan náà jẹ́ ọ̀nà ṣíṣe ẹwà fún ọkùnrin. Àwọn ìlàrì ọba àti àwọn ọmọ Ààgberí ní wọ́n sáábà ń fá orí apákan ní àtijọ́. Irun gígẹ̀ tún gbilẹ́ láàrin àwọn ọkùnrin. Àpẹẹrẹ irun tí àwọn ọkùnrin ń gẹ̀ ní àtijọ́ ni Bọ́mà (Burma), Kùǹbà, Kọ̀síkóòmù (cockscomb) tàbí Tógò (Togoland), Bítù (Beetle), Òǹbọ́ọ̀dù (on-board), àti Ṣọ́bíṣẹkà (chubby-checker).

Bí àwọn ọkùnrin ṣe ń tọ́jú orí wọn láti bù kún ẹwà náà ni àwọn obìnrin kò gbẹ́yìn. Ọ̀nà mẹ́ta ni obìnrin ń gbà ṣe èyí. Wọ́n lè ba irun, dì í tàbí kí wọ́n kó o. Irun gígẹ̀ kò wọ́pọ̀ láàárín àwọn obìnrin ní àtijọ́ nítorí Yorùbá ka obìnrin tí ó ń gẹ irun sí aláṣejù.

Bí obìnrin kò bá ní àyè láti ṣe irun rẹ̀ ni ó ń ba á. Obìnrin lè ba irun sí ẹyọ kan, méjì tàbí mẹ́ta. Irúfẹ́ irun bíba yìí kì í pẹ́ kí ó tó di pé obìnrin náà dì í tàbí kó ó. Oríṣìí ọ̀nà ni obìnrin lè gbà di irun. Ó lè di kòlẹ́sẹ́, ìpàkọ́ ẹlẹ́dẹ̀, ṣùkú, panumọ́, ọlọ́pọ́n ayò, òjò kò pa etí, àti mọrèmi.

Lẹ́yìn tí àṣà irun dídì àti bíba bẹ̀rẹ̀ ni a tó rí irun kíkó. Àwọn ọmọdé ni ó saábà ń kó irun tẹ́lẹ̀. Lára àwọn irun tí wọ́n ń kó ni ogún parí, afuró, aláké-wàjà, láyípo, kẹ̀hìnsọ́kọ, àti onílé gogoro.

- **Ìtọ́jú Etí**

Obìnrin nìkan ni ó ń lu etí nítorí ẹwà. Kékeré ni wọ́n sì ti ń lu etí yìí nítorí kí ó má bà á dùn wọ́n. Òwú lásán ni wọ́n kọ́kọ́ ma fi sí ihò yìí kí ó tó san. Obìnrin lè sín oríṣìíríṣìí ìlẹ̀kẹ̀ láti fi ṣe ẹ̀ṣọ́ sí etí.

- **Ìtọ́jú Eyín**

Yorùbá gbà pé ènìyàn lè tun eyín ṣe nítorí ẹwà. Èrò yìí ló bí eyín pípá pàápàá fún ẹni tí kò ní èjí. Àwọn ọ̀dọ́mọkùnrin ni ó saábà ń pá eyín iwájú méjèèjí. Àwọn obìnrin kì í saábà pá eyín àyàfi àwọn tí ó wà ní Igbó-Ègùn àti Ìdàhọ̀mì. Àwọn Yorùbá máa ń run oríṣìíríṣìí orín láti mú kí eyín wọn funfun. Ní ìgbà tí àwọn obìnrin máa ń run orín pupa, tàbí orín ìdí àwọn ọkùnrin ní tiwọn máa ń run orín funfun àti gbòǹgbò igi ààyìn, àwọn orín wọ̀nyí máa ń mú eyín mọ́ ṣákáṣáká, ó sì máa ń pa àwọn kòkòrò tó lè mú ẹnu mẹ́ṣẹ̀rì.

- **Ìlà Kíkọ**

Yàtọ̀ sí pé Yorùbá ń kọ ilà láti fi ibi tí ènìyàn ti wa hàn, wọ́n ka ilà kíkọ sí aájò ẹwà. Oríṣìíríṣìí ilà ni àwọn Yorùbá máa ń kọ ọ̀pọ̀ ìgbà ni èyí sì máa ń ṣàfihàn ibi tí àwọn

ènìyàn ti wá. Díẹ̀ lára ìlà ti àwọn Yorùbá máa ń kọ nìwọ̀nyí: Àbàjà jẹ́ ilà tí àwọn ọmọ Aláàfin máa ń kọ. Oríṣìí àbàjà méjì ló wà, èkínní ni àbàjà ọmọ ọ̀ba tàbí àbàjà olówu, kẹ́kẹ́ tàbí gọ̀ǹbọ́ jẹ́ oríṣìí ilà mìíràn tí ó máa ń gba gbogbo ẹ̀rẹ̀kẹ́ tán, a lè wọ́ gọ̀ǹbọ́ pẹ̀lú tọwọ́bojú, bàràmú àti kẹ́kẹ́ olówu.

**Tùre:** Ilà tí a ń pè ni tùre fara jọ gọ̀ǹbọ́ ṣùgbọ́n tí òòró rẹ̀ a máa ju èyí tí a kọ fún ẹni tí o wa gọ̀ǹbọ́ lọ.

**Pélé:** Ìlú Ìlọrin ni pélé ti bẹ̀rẹ̀ láàrin àwọn mùsùlùmí tí ó kórìíra kí ẹ̀rẹ̀kẹ́ àwọn ọmọ wọn ṣe ṣọ̀bọ̀rọ́ bí ti Ifẹ̀.

**Ẹwà Ara àti Ohun Ẹ̀ṣọ́ Mìíràn**

Àwọn obìnrin máa ń lo ẹ̀gbà ọwọ́ àti ọrùn láti fi ṣe ẹ̀ṣọ́ èyí tí ó lè bù kún ẹwà wọn. Bákan náà ni wọ́n ń lo òrùka ọwọ́.

Ara fífín àti sọjú sísọ jẹ́ ọ̀nà tí àwọn obìnrin ń gbà bu ẹwà kún ara wọn. Ọkùnrin kì í saábà ṣe èyí àyàfi onífáàrí tàbí òǹrayè nínú wọn. Ọ̀lẹ ni Yorùbá ń ka irúfẹ́ ọkùnrin bẹ́ẹ̀ sí. Ìlọrin, Ọ̀yọ́, Tápà, Ọ̀fà àti Èkìtì ni ọkùnrin àti obìnrin wọn kúndùn ara fífín. Àwọn ibi tí àwọn Yorùbá máa ń fín lára ni igbá àyà, ẹ̀yìn, apá, pọpọlọ itan, ètìpá ẹsẹ̀, àti ẹ̀gbẹ́ etí. Abẹ ni wọ́n máa ń lò láti fín ara.

Abẹ́rẹ́ ọ̀pọ̀ọ̀rọ̀ tí wọ́n dipọ̀ ni wọ́n fi ń sọ sọjú sí apá, pọnpọlọ itan, gìgísẹ̀, ẹ̀gbẹ́ etí, odò ikùn, àyà àti ẹ̀yìn. Wọ́n lè fi sojú kọ orúkọ tàbí kí wọ́n fi ya ohun tí ó bá wù wọ́n. Tìróò lílé àti làálì lílé náà kò gbẹ̀yìn nínú ẹwà ṣíṣe fún àwón obìnrin. Ṣùgbọ́n ọkùnrin náà ń lé tìírò ní àtijọ́ kí ojú wọn lè gún régé. Bí obinrin bá ń ló sí ilé ọkọ, ó lè lé làálì sí ọwọ àti ẹsẹ.

- **Aṣọ wíwọ̀**

Aṣọ wíwọ̀ jẹ́ ọ̀nà kan gbòógì tí àwọn Yorùbá fi máa ń ṣàfihàn ẹwà wọn. Wọ́n gbà pé aṣọ ni ó ń bo àṣíri ara. Tọkùnrin tobìnrin Yorùbá ni ó ní oríṣìíríṣìí aṣọ tí wọ́n ń wọ̀ láti fi fáàrí

hàn. Ṣùgbọ́n aṣọ àwọn ọkùnrin pọ̀ ju ti obìnrin lọ. Àwọn Yorùbá ní aṣọ iṣẹ́, aṣọ ìyílẹ̀, àti aṣọ ìmúròde. Àpẹẹrẹ aṣọ ti ọkùnrin ni dàńdógó, gbárìyẹ̀, agbádá, sapará, ọ̀yàlà elérí àti oníkànnì, dàǹṣíkí, bùbá, súlíá, kafutáànì, jálááàbù. A sì rí ṣòkòtò bí i dígò, latan tàbí abìdán, sọ́rọ́, kẹ̀ǹbẹ̀, kámù, àgbàntan, nàǹgúdù. Bákan náà ni Yorùbá ní fìlà adiro, ìkòrì, abetí ajá àti fìlà onídẹ.

Aṣọ àwọn obìnrin ni ìró, ẹ̀wù bùbá, gèlè, ìdikù. Bákan náà ni wọ́n ní tòbì àti yẹ̀rì. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé aṣọ àwọn obìnrin kò pọ̀ síbẹ̀ aṣọ olówó ńlá ni wọ́n fi ń dá àwọn aṣọ náà. Àwọn aṣọ tí àwọn obìnrin fi ń rán aṣọ wọn ni aṣọ-òkè, àǹkárá, gínnì borokéèdì, àti léèsì.

### 4.3 Oríṣìí Ẹwà Gẹ́gẹ́ bí Ìgbàgbọ́ Yorùbá

Yorùbá gbà pé ọ̀nà méjì ni ẹwà pín sí. Èyí ni ẹwà òde àti ẹwà inú. Yorùbá rí ẹwà òde gẹ́gẹ́ bí ẹ̀bùn láti ọwọ́ Olódùmarè. Ẹwà òde níṣe pẹ̀lú ìrísí ènìyàn. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹwà ènìyàn á máa ṣá. Lára àwọn ohun tí ó lè mú kí ẹwà ṣá ni àìsàn, ìṣẹ́, tàbí tí àgbà bá dé.

Ẹwà inú níí ṣe pẹ̀lú ìwà. Yorùbá máa ń sọ pé ‘ìwà ni ẹwà’. Wọ́n gbà pé ẹni tí ó bá gún régé tí kò níwà rere kò ní ẹwà. Bákan náà, wọ́n rí ìwà dáadáa bí ẹ̀ṣọ́ ènìyàn, pàápàá àwọn obìnrin.

Ẹwà ọkùnrin kò ní íṣe pẹ̀lú ìrísí tàbí ẹ̀ṣọ́ ara bíkòṣe bí ọkùnrin náà ṣe ń ṣiṣẹ́ tó àti bí ó ṣe ní akínkanjú sí.

### 4.4 Díẹ̀ lára àwọn ìpèdè tí ó níṣe pẹ̀lú ẹwà ni:

- Adúmáadán
- Apọ́nbéporẹ́
- Ẹlẹ́yinjú ẹgẹ́
- Eyínfúnjowó
- Funfun niyì eyín
- Gígúnrégé niyì ọrùn

- Irun lẹwà obìnrin
- Ẹ kú ẹwà
- Ìbàdí àrán
- Ìdí ìlẹ̀kẹ̀
- Arẹwà
- Ó dára bí egbin
- Ọmọ́dára ó lẹ́wà
- Ọmọ́dára ó dẹjọ́

## 4.5 Ẹwà Ṣíṣe Lóde Òní

Ẹwà ṣiṣe lóde òní ti tayọ èyí tí àwọn Yorùbá ń ṣe ní ayé àtijọ́. Púpọ̀ nínú àwọn àṣà ayé àtijọ́ wọ̀nyí ló sì ti ń kásẹ̀ nílẹ̀. Àwọn ènìyàn kìí sáábà fín ara tàbí sọ ọjú mọ́, dípò èyi wọ́n á ya tàtúù sí ara, oríṣìíríṣìí àrà sì ni wọ́n ń fi èyí dá. Bákan náà, ọ̀nà àrà ni irun ṣíṣe. Àwọn obìnrin máa ń fi irun kún irun wọn, òmíràn sì lè dé wîìgì. Tọkùnrin tobìnrin ni ó ń ṣe irun lóde òní fún ẹwà tàbí fáàrí. Irun gígẹ̀ wọ́pọ̀ láàárín àwọn obìnrin ìwòyí. Ọ̀pọ̀ obìnrin àti ọkùnrin ni ó sì ń pa irun ní aró lóde òní.

Àrà ọ̀tọ̀ ni ojú kíkùn fún àwọn obìnrin lóde òní tí ó fi jẹ́ pé tí wọ́n bá kun ojú, tọ́ ètè, lẹ irun ojú tán tipátipá ni a lè fi dá irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ mọ̀ látàrí bí ẹni náà yóò ṣe rẹwà. Yàtọ̀ sí èyí, àwọn ènìyàn pàápàá jùlọ obìnrin ń ṣe iṣẹ́ abẹ nítorí ẹwà. Wọ́n á ṣe àtúnṣe sí imú, ìpèńpé ojú, ẹ̀rẹ̀kẹ́, àti àgbọ̀n. Àwọn òmíràn ń fọn ọyàn àti ìdí wọn kí ó lè tóbi sí i. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, níní ẹwà jẹ àwọn ènìyàn lógún nítorí kò sí ẹni tí ó fẹ́ bá òbùrẹ́wà ṣe. Akitiyan àtimú kí ẹwà yìí hàn sí àwùjọ kí wọ́n lè fi yẹ́ wọn sí ni ó bí oríṣìíríṣìí aájò ẹwà tí àwọ́n Yorùbá yàn láàyò. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀ nínú àwọn ọ̀nà ẹwà ṣíṣe yìí ló ti ń kásẹ̀ nílẹ̀, síbẹ̀ ọpọ́n ẹwà níní àti aájò rẹ̀ ń tẹ̀síwájú. Bákan náà, Yorùbá ka ìwà ọmọlúàbí, ìṣesí dáadáa, àti níní akínkanjú sí ẹwà ṣíṣe tí ènìyàn gbọ́dọ̀ yàn láàyò.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín keji lábẹ́ módù kejì yìí a ti kẹ́kọ̀ọ́ pe:

- Ẹwà ṣíṣe jẹ àwọn Yorùbá lógún púpọ̀.
- Ẹ̀yà Yorùbá jẹ́ ẹ̀yà tí ó gbáfẹ́ tí ó sì gbádùn kí ènìyàn tún ara ṣe kí ó sì ṣe é rí ní àwùjọ.
- Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ìfẹ́ Olódùmarè ni láti jẹ́ kí obìnrin lẹ́wà ju ọkùnrin lọ.
- Òrìṣà-ńlá nítorí wọ́n gbà pé òun ni ó mọ ẹ̀dá tí ó sì bu ẹwà kún wọn.
- ìgbàgbọ́ pé àwọn tí ó bá burẹ́wà jẹ́ ẹ̀dá tí Òrìṣà-ńlá fẹ́ràn, èyí ni wọ́n fi ń pè wọ́n ní "Ẹniòrìṣà.
- Ẹwà nínú èrò Yorùbá kọjá kí ènìyàn dùn ún wò lójú.
- Kí Yorùbá tó lè gbà pé ẹnì kan ní ẹwà, irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ gún régé ní gbogbo ọ̀nà. Ìṣesí, ìsọ̀rọ̀sí àti ìrísí rẹ̀ gbọ́dọ̀ dáyàtọ̀.
- Ẹwà láìsí ìwà rere ni àwọn Yorùbá korò ojú sí.
- Ipa àtiṣe aájò ẹwà ló bí ìtọ́jú orí, etí, eyín, ọrùn, ẹ̀rẹ̀kẹ́ àti oríṣìíríṣìí aṣọ wíwọ̀.
- Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹwà ènìyàn á máa ṣá. Lára àwọn ohun tí ó lè mú kí ẹwà ṣá ni àìsàn, ìṣẹ́, tàbí tí àgbà bá dé.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

a) Kí ni ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín aájò ẹwà ṣíṣe ní àtijọ́ àti lóde òní?

b) Ṣe lóòótọ́ ni pé ẹwà a máa sá?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adeoye, C. L. 1979. *Àṣà ati Ìṣe Yorùbá*. Ibadan: Oxford University Press

Ajayi, B. 2001.“Ìṣẹ̀ṣe Yorùbá”nínúAjayi, B (ed.) *Ẹ̀kọ́ Ìjìnlẹ̀ Yorùbá: Ẹ̀dá-Èdè, Lítíréṣọ̀ Àti Àṣà*.Ijebu-Ode: Shebiotimo Publications

Daramola, O. Àti Jeje, A. 1975. *Àwọn Àṣà àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá*. Ibadan: Onibon-Oje Press

## ÌPÍN KẸTA: ÌGBÀGBỌ́ YORÙBÁ NÍPA OWÓ

**Ìfáàrà:**

Nínú ìpín yìí, a ṣe àyẹ̀wò ohun tí Yorùbá ń lò fún owó ṣáájú kí àwọn Òyìnbó tó dé. Akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yóò ní òye kíkún nípa èrò Yorùbá nípa owó àti ihà tí wọ́n kọ sí níní àti àìní owó ènìyàn. Bákan náà, a wó ọ̀nà tí wọ́n ń gbà yá owó àti bí wọ́n ṣe le rí owó.

**Àkóónú:**

1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
 4.1 Ìpìlẹ̀ owó nílẹ̀ Yorùbá
 4.2 Èrò Yorùbá nípa owó
 4.3 Owó yíyá
 4.4 Ọ̀nà Àtirówó
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Ìpín yìí ṣe àfihàn ipò tí àwọn Yorùbá fi owó sí látàrí bí wọ́n ṣe ri bí i kòṣe-é-mánìí fún ènìyàn ní àwùjọ.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- Ṣàlàyé ohun tí Yorùbá ń lò gẹ́gẹ́ bí owó kí àwọn Òyìnbó tó dé.
- Ṣe àlàyé nípa ihà tí Yorùbá kọ sí owó gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe hàn nínú èrò wọn.
- Ṣe àpèjúwe bí a ṣe ń yáwó nílẹ̀ Yorùbá.
- Tọ́ka sí bí ènìyàn ṣe lè gbà rí owó.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

i. Kí ni àwọn Yorùbá ń lò bí owó kí àwọn Òyìnbó tó dé?

ii. Ṣe àgbéyẹ̀wò ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa owó.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìpìlẹ̀ Owó Nílẹ̀ Yorùbá

Àwọn Yorùbá máa ń sọ pé ọ̀rọ̀ gbogbo lórí owó, ohun èyí túmọ̀ sí ni pé owó ṣe pàtàkì nínú ìgbésí ayé ẹ̀dá nítorí àìsí owó ń mú ìdàmú àti ìyà bá ènìyàn. Ọ̀rọ̀ owó lágbára púpọ̀. Kò sí bí ènìyàn sè lè lẹ́wà tó bí kò bá ní owó, ènìyàn yẹpẹrẹ ni wọn yóò kà á sí. Ẹbí tí ó tòrò lè dàrú nígbà tí wàhálà bá ṣẹlẹ̀ látàrí àìsí owó. Owó máa ń fa rògbòdìyàn lááárín bàbá àti ọmọ, ọkọ àti aya, ọ̀rẹ́ tímọ́tímọ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Yorùbá kì í lo wúrà (gold) tàbí fàdákà (silver) gẹ́gẹ́ bí i owó kí àwọn Òyìnbó tó kó owó irin (coin) wọ̀lú. Owó-ẹyọ ni wọ́n ń lò fún òwò àti gbogbo ohun tí ó níṣe pẹ̀lú owó. Àmọ́, ṣáájú àwọn Òyìnbó yìí, owó ni wọ́n kọ́kọ́ ń pe owó-ẹyọ, ṣùgbọ́n ìyípadà dé bá orúkọ yìí nígbà tí iyì rẹ̀ lọ sílẹ̀ tí wọ́n sì nílò láti pàlà lááárín owó irin (coins) àwọn Òyìnbó àti owó-ẹyọ. Àwọn tí àwọn Òyìnbó  kó wọ̀lú ni Kọ́bọ̀ (Penny), Tọ́rọ́ (Pence), Sísì (Six Pence), Ṣílè (Shillings). Ìjọba Nàìjíríà gbé ètò owó tuntun jáde ní ọdún 1973. Láti ìgbà yìí ni a ti ń lo Náírà àti Kọ́bọ̀.

Owó-ẹyọ ni Yorùbá ń lò ní àtijọ́ láti fi dípò owó kí ó tó di pé àwọn Gẹ̀ẹ́sì dé. Lẹ́yìn èyí ni ìjọba Nàìjíríà gbé ètò owó Náírà àti Kọ́bọ̀ jáde.

Gẹ́gẹ́ bí ó ti ṣe wọ́pọ̀ láàárín àwọn gbajúmọ̀ káàkiri àgbáyé, àwọn olówó ma ń fi owó de nǹkan mọ́lẹ̀ tí wọn yóò sì sa gbogbo agbára wọn láti ri pé owó náà gbérí si yálà nípa ọ̀nà ẹ̀tọ́ tàbí ọ̀nà èrú.

Ní àtijọ́, àwọn ènìyàn lè rí owó nínú ṣíṣe òwò ẹrú, tàbí kí wọ́n dáwọ́lé kárà-kátà. Owó tí wọ́n bá rí yìí ni wọ́n yóò fi ra ohun ìní bíi ẹrú, ìwọ̀fà, nǹkan ọ̀sìn bíi ewúrẹ́, àgùntàn, adìyẹ, ẹṣin, ẹlẹ́dẹ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

## 4.2 Èrò Yorùbá Nípa Owó

Ní àwùjọ Yorùbá, owó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ohun mẹ́ta tí ó ṣe pàtàkì ní ìgbesí ayé ẹ̀dá. Àwọn ohun tí ó kù ni ọmọ àti ẹ̀mí gígùn pẹ̀lú àlááfíà. Kì í ṣe gbogbo ènìyàn ni ó ní àǹfààní láti ní owó tẹ́lẹ̀ láàrín àwọn Yorùbá. Lára ohun tí ó fa èyí ni pé nígbà tí ìlò owó-ẹyọ ṣì wọ́pọ̀, oríṣìíríṣìí ìtan àràmàdà ni wọ́n fi ṣàlàyé orísun rẹ̀. Ọ̀kan lára àwọn ìtàn yìí ni pé Olódùmarè fi àṣírí owó-ẹyọ han àwọn tí ó ṣà yàn. Àrídìmú Irúfẹ́ ìtàn báyìí ni pé ìwọ̀nba àwọn tí ó lówó kò fẹ́ kí gbogbo ènìyàn ní àǹfààní sí owó-ẹyọ.

Yorùbá máa ń ka ẹni tí ó lówó sí ènìyàn pàtàkì. Irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń pè ní “Olówó”. Tálákà tàbí mẹ̀kúnnù ènìyàn ni wọ́n máa ń pe ẹni tí kò lówó. Olówó nìkan ni ó ní àǹfààní láti sọ̀rọ̀ nígbà tí ó bá di ọ̀rọ̀ owó tàbí ní àárín ìgbìmọ̀.

Èrò Yorùbá ni pé owó kì í hù nílẹ̀. Ẹni tí ó bá máa lówó tí yóò sí là ní láti ṣiṣẹ́ kárakára kí ó lè rówó ná ní àwùjọ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ènìyàn lè jogún owó, síbẹ̀ wọ́n gbà pé iṣẹ́ ni oògùn ìṣẹ́. Òwe Yorùbá kan ní a-sáré-lówó ń bẹ lọ́nà ogun; a-pọ̀ṣẹ̀ṣẹ̀ ń bẹ lọ́nà èrò; bó-pé-tító-ń-ó-là ń bẹ lábà, ó ń jẹ ẹ̀sun iṣu. Èyí fi hàn pé ẹ̀dá tí ó bá máa lówó gbọ́dọ̀ gbé ìgbésẹ̀ kan tàbí òmíràn. Kò gbọdọ̀ jókòó tẹtẹrẹtẹ lái wá nǹkankan ṣe. Bí a ṣe lè ṣiṣẹ́ ọwọ́ náà ni a ṣe lè ṣiṣẹ́ oṣù tí tọ́rọ́ kọ́bọ̀ yóò sì ma wàpò. Lára àwọn iṣẹ́ tí wọ́n ń ṣe ni iṣẹ́ àgbẹ̀dẹ, iṣẹ́ àgbẹ̀, káràkátà tàbí òkòwò.

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé “Owó ni gbòǹgbò ẹ̀ṣẹ̀” nítorí pé owó ní agbára láti gun ènìyàn kí ó ṣe ìjàǹbá fún ẹlòmíràn. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé níní ìfẹ́ owó jù máa ń ba ìwà rere jẹ́. Ọ̀rẹ́ àtìgbà pípẹ́ lè pínyà nítorí owó, èyí ni wọ́n fi ń sọ pé “owó ni í bojú ọ̀rẹ́ jẹ́”. Nítorí ìdí èyí,

wọ́n gbà pé èniyàn kò gbọdọ̀ fi wàdùwàdù wá owó torí èyí lè mú kí èniyàn dáwọ́lé ìwà ọ̀daràn bíi olè jíjà, jìbìtì ṣíṣe, tàbí kí irú ẹni bẹ́ẹ̀ tilẹ̀ gbèrò oògùn owó, abbl.

Ìgbàgbọ̀ àwọn Yorùbá ni pé, ẹni tó fowó lògbà ló káyè já. Kòṣe-é-mánìí ni owó jẹ́. Owó ṣe kókó fún ìgbéga ẹ̀dá. Ó fẹ́rẹ̀ má sí ohun tí èniyàn fẹ́ dáwọ́lé tí kò ní nílò owó. Nígbà tí èniyàn bá fẹ́ gbéyàwó owó ni yóò ná, ẹni tí ó fẹ́ ṣòwò yóò nílò owó, bákan náà tí èniyàn bá ṣàìsàn owó ni yóò fi ra ohun tí yóò fi ṣe ìtọ́jú ara rẹ̀.

A lè fi owó ṣe ìpín sọ́wọ̀ọ̀ àwọn èniyàn tí ó wà ní àwùjọ. Èyí ni a ṣe rí ọ̀wọ̀ olówó àti ọ̀wọ̀ mẹ̀kúnnù tàbí tálákà. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé owó kò mẹ̀gbọ́n, ó sì máa ń sọ àbúrò dẹ̀gbọ́n nígbà mìíràn. Wọ́n ní ìgbàgbọ́ pé owó máa ń fi àjùlọ hàn. Owó ń fi èniyàn sí ipò ọlá ní àwùjọ. Wọ́n ma ń sọ pé olówó ṣe ohun gbogbo tán, ìyà jẹ ọmọ tálákà. Kò ṣe é ṣe láti rẹ́ olówó jẹ ní àwùjọ. Dípò èyí, olówó ni yóò fi owó rẹ̀ ra ìjìyà fún ẹni tí kò ní tàbí kí ó lo owó rẹ̀ láti fi tẹ tálákà mẹ́rẹ̀.

Ju gbogbo rẹ̀ lọ, olówó gbọ́dọ̀ mọ bí wọ́n ṣe ń náwó. Yorùbá gbàgbọ́ pe olówó kò gbọdọ̀ ná owó rẹ̀ ní ìnákúnàá kí owó náà ba lè pẹ́. Èyí ni Yorùbá fi ń ní ká ṣiṣẹ́ ká lówó lọ́wọ́ kò dàbí i ká mọ̀ ọ́ ná.

Àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé owó kọ́ ni òpin ohun gbogbo. Èyí túmọ̀ sí pé ẹ̀dá kò gbọdọ̀ rawọ́ lé ohun tí apá rẹ̀ kò ká nítorí owó, yàtọ̀ sí èyí, ìgbàgbọ́ Yorùbá tún ni pé ẹni tí ó lówó tí kò níwà, owó olówó ló ní. Bákan náà ni wọ́n gbà pé bíbí ire kò ṣé fowó rà.

Látàrí ipò tí Yorùbá fi owó sí, wọ́n máa ń ṣe àpèjúwe rẹ̀ bí nǹkan abẹ̀mí. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n á ní owó ya ilé rẹ̀, owó yarọ, owó yapa, owó ti dé, owó ṣiṣẹ́ fun, owó káàbọ̀ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Owó ni Yorùbá fi ń mọ èniyàn pàtàkì. Oríṣìíríṣìí ìpèdè ni wọ́n ń lò láti fi pàtàkì owó hàn. Díẹ̀ nínú rẹ̀ ni ìwọ̀nyí:

- Owó ní bí òun kò bá sí nílé, kí ẹnikẹ́ni máṣe dámọ̀ràn lẹ́yìn òun
- Ọ̀rọ̀ gbogbo lórí owó
- Àìlówó lọ̀rẹ́ ò sí bí a lówó tán, tajá tẹran ní í bá ní i tan

- Òsì níí jẹ́ taní mọ̀ ọ́ ri, owó ní í jẹ́ mo bá ọ tan
- Àgbá òfìfo ní í pariwo, àpò tó kún fówó kì í dún
- Olówó ṣe ohun gbogbo tán iyà ní í jẹ ọmọ tálákà

## 4.3 Owó yíyá

Bí owó yíyá ṣe wà ní òde òní náà ni ó wà ní àtijọ́. Ẹni tí ó bá nílò owó lè yá lọ́wọ́ ẹni tí kò ní kí àṣírí rẹ̀ lè bò. Bí ènìyàn bá fẹ́ yá owó ní àtijọ̀, ó gbọ́dọ̀ ní onídúró tí yóò sọ̀rọ̀ rẹ̀ dáadáa fún olówó kí ó lè rí owó náà gbà. Olówó àti ẹni tí ó yá owó lè ṣe àdéhùn láti dá owó padà lọ́jọ́ tí wọ́n bá fẹnu kò sí, olówó sì lè ní kí ẹni tó yáwó mú ọmọ rẹ̀ wá láti ṣiṣẹ́ tí yóò fi rí owó san padà, èyí ní a mọ̀ sí ọfà ṣíṣe. Ẹni tí ó yáwó bákan náà sìle dúró láti ṣiṣẹ́ fún bí i ọdún méjì, mẹ́ta tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ tí yóò fi san owó náà tán. Èyí sábà máa ń wáyé nígbà tí ènìyàn bá ṣàìsàn ti kò sí rí owó san fún onísègùn tí ó tọ́jú rẹ̀. Ní òde òní, oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn ènìyàn ń gbà yáwó. A lé yáwó ní báńkì, lọ́dọ̀ ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù, ọwọ́ ọ̀rẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Onírúurú ni ohun tí ó ń mú ènìyàn yá owó, a lè yá owó láti ṣe ìnáwó, ṣe ìtọ́jú aláìsàn tàbí láti ṣòwò.

## 4.4 Ọ̀nà Àtirówó

Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn ènìyàn ń gbà rí owó. Bí ènìyàn ṣe ń rí owó ní ọ̀nà ẹ̀tọ́ bẹ́ẹ̀ ni ó ṣe é ṣe kí ènìyàn gba ọ̀nà ẹ̀bùrú rí owó, ṣùgbọ́n Yorùbá gbà pé tí ènìyàn bá gba ọ̀nà ẹ̀bùrú wá owo yóò gbẹ̀san ìwà bẹ́ẹ̀.

Ìgbọ̀nrìrì àti akitiyan àwọn ènìyàn láti lówó láìṣe wàhálà ni ó bí oògùn owó ṣíṣe. Nípa báyìí, àwọn tí ó fẹ́ ṣẹ́só lè lo ènìyàn tàbí nǹkan mìíràn láti fi wá ajé, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀ ìgbà ni irúfẹ́ owó gbígbóná báyìí ń lẹ́yìn tí àtubọ̀tan rẹ̀ kò sì ní dára fún tẹbí tará ẹni náà.

Ní òde òní, owó níní ti gba ọ̀nà àrà tí ó fi jẹ́ pé àwọn ajínigbé yóò gbé aláìṣẹ̀ tí wọn yóò sì ní kí àwọn ẹbí rẹ̀ wá owó gọbọi wá. Àwọn ìgárá ọlọ́ṣà náà á máa jálé, dánà, tàbí kí wọ́n

fọ́ ilé ìfowópamọ́ nítorí kí wọ́n lè rówó jayé. Ọ̀pọ̀ ènìyàn ni ó ń ṣe owó tí ó wà ìkapá rẹ̀ ní mọ́kun-mọ̀kun. Àwọn mìíràn tilẹ̀ ń ṣe *yàhóò* nítorí àtilówó. Èyí kò túmọ̀ sí pé ẹ̀dá kò lè là láìṣe iṣẹ́ aburú. Oríṣìíríṣìí iṣẹ́ ló wà tí ó lè sọ ènìyàn di ẹni ńlá ní àwùjọ.

## 5.0 Ìsọnísókí

Nínú ìpín kẹta lábẹ́ módù kejì yìí a ti kékọ̀ọ́ pe:

- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé owó ṣe pàtàkì nínú ìgbésí ayé ẹ̀dá nítorí àìsí owó ń mú ìdààmú àti ìyà bá ènìyàn.
- Owó-ẹyọ ni Yorùbá ń lò ní àtijọ́ láti fi dípò owó kí ó tó di pé àwọn Gẹ̀ẹ́sì dé.
- owó jẹ́ ọ̀kan lára àwọn ohun mẹ́ta tí ó ṣe pàtàkì ní ìgbesí ayé ẹ̀dá.
- Èrò Yorùbá ni pé owó kì í hù nílẹ̀. Ẹni tí ó bá máa lówó tí yóò sí là ní láti ṣiṣẹ́
- Ìgbàgbọ́ wọn ni pé níní ìfẹ́ owó jù máa ń ba ìwà rere jẹ́
- Ìgbàgbọ̀ àwọn Yorùbá ni pé, ẹni tó fowó lògbà ló káyè já.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pe ènìyàn kò gbọdọ̀ fi ọ̀nà ẹ̀bùrú wá owó tabí ná owó ní ìnákúnàá kí owó náà ba lè tọ́jọ́.
- Oríṣìíríṣìí ìpèdè ni àwọ́n Yorùbá máa ń lò láti fi pàtàkì owó hàn.
- A lé yáwó ní báńkì, lọ́dọ̀ ẹgbẹ́ alájẹṣẹ́kù tàbí ọwọ́ ọ̀rẹ́

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Kí ni ihà tí Yorùbá kọ sí wíwá owó lọ́nà ẹ̀bùrú?

ii. Jíròrò lórí ìgbagbọ́ Yorùbá nípa owó.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adebayo, A.G. 1994. "Money, Credit, and Banking in Precolonial Africa: the Yoruba Experience" *Anthropos* 89 pp. 379-400

Adeoye, C. L. 1979. *Àṣà ati Ìṣe Yorùbá*. Ibadan: Oxford University Press

Falola, T. ati Akinyemi, A. (ed.) 2016. "Money" nínú *Encyclopedia of the Yorùbá.* Bloomington: Indiana University Press

## IPIN KẸRIN: ÌGBÀGBỌ́ ÀWỌN YORÙBÁ NÍPA Ọ̀RẸ́

### Ìfáàrà

Ní ìpín yìí, a ó ṣe ṣàlàyé nǹkan tí ń jẹ́ ọ̀rẹ́ àti oríṣìíríṣìí ọ̀rẹ́ tí ó wà. A ṣe àgbéyẹ̀wò ipa tí ọ̀rẹ́ ń kó nínú ayé ẹ̀dá. Bákan náà ni a ṣe àfìhán èrò àwọn Yorùbá nípa yíyan ọ̀rẹ́ àti irúfẹ́ ọ̀rẹ́ tí a gbọ́dọ̀ gbà láàyé. Ìpín yì í ṣàfihàn àbùdá ọ̀rẹ́ àti bí kò ṣe yẹ kí a nífẹ̀ẹ́ ọ̀rẹ́ ju ẹbi.

### Àkóónú:

1. Ìfáàrà
2. Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3. Ìbéèrè Ìṣáájú
4. Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    - 4.1 Ta ni ọ̀rẹ́?
    - 4.2 Àbùdá Ọ̀rẹ́ Gidi
    - 4.3 Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ọ̀rẹ́.
5. Ìsọnísókí
6. Iṣẹ́ Síṣe
7. Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Iṣẹ́ yìí ṣàfihàn ojú tí àwọn Yorùbá fi ń wo ọ̀rẹ́ ní àwùjọ. Níbí ni a ti wo ẹni ti ń jẹ́ ọ̀rẹ́, àbùdá ọ̀rẹ́ gidi, bí ọ̀rẹ́ ṣe rí ní àtijọ́ àti lóde òní.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Èròǹgbà àti àfojúsùn wa lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yì í ni pé akẹ́kọ̀ọ́ àti oǹkàwé yóò le

Ṣàlàyé ìtumọ̀ ọ̀rẹ́

Pàlà láàárín ọ̀rẹ́ gidi àti ọ̀rẹ́ burúkú

Tọ́ka sí àbùdá ọ̀rẹ́ gidi

Ṣàlàyé ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ọ̀rẹ́

## 2.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

i. Kí ni ìyàtọ̀ tí ó wà láàárín ọ̀rẹ̀ àti ọ̀tá?

ii. Ṣàlàyé kíkún nípa irúfẹ́ ọ̀rẹ́ tí ó wà ní ilẹ̀ Yorùbá

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ta ni Ọ̀rẹ́?

Ohun tí ó ń jẹ́ ọ̀rẹ́ ti wà ní àwùjọ Yorùbá tipẹ́tipẹ́. Níní ọ̀rẹ́ kì í ṣe ohun bàbàrà tàbí nǹkan àjèjì, ó jẹ́ ohun àtayébáyé nínú ìgbé-ayé ẹ̀dá. Ó ṣòro fún ẹ̀dá láti wà láìní alábárìn tàbí alábàárò nítorí níní àjọṣe àti ìrẹ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn ènìyàn ni àwùjọ ṣe pàtàkì.

Ọ̀rẹ́ túmọ̀ sí níní ìbáṣepọ̀ tó dán mọ́ràn láàárín ènìyàn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àwọn ènìyàn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ bá jẹ́ ọ̀rẹ́, wọ́n máa ń sún mọ́ ara wọn pẹ́kí láti finú fẹ́dọ̀ ran ara wọn lọ́wọ́, láti jẹ́ alábárìn àti olùbánidárò. Irúfẹ́ àwọn ènìyàn báyìí máa ń nífẹ̀ẹ́ ara wọn, wọn yóò sì ka ara wọn sí ní gbogbo ìgbà. Ọ̀rẹ́ sábà ń jẹ́ ohun tí ó ti inú ènìyàn wá, àjọṣe tí ó jẹ́ déédé láàárín àwọn tí kì í sábà jẹ́ ẹbí.

Yíyan ọ̀rẹ́ lè wáyé láàárín àkójọpọ̀ ọkùnrin, àgbájọ àwọn obìnrin tàbí àpapọ̀ ọkùnrin àti òbínrin. Àjọṣepọ̀ máa ń sábà wáyé láàárín àwọn tí wọ́n jẹ́ ọgbà, tí òye wọn jẹ́ bákan náà, tí ipò wọn sì jẹ́ bákan. Bí eǹìyàn bá yan ọ̀rẹ́, dandan ni kí ó mọ ìwà ẹnìkejì, ohun tí ó fẹ́ àti ohun tí ó lòdì sí. Àwọn tí ó bá ríra gẹ́gẹ́ bí ọ̀rẹ́ gbọ́dọ̀ mọ̀ nípa ara wọn. Èyí ni yóò fi hàn pé ọ̀rẹ́ ni wọ́n jẹ́ lóòótọ́.

Ohun burúkú ni kí ọ̀rẹ́ lo agbára àti ipò ọlá rẹ̀ láti ṣáátá tábí sọ̀rọ̀ ìbànújẹ́ sí ara wọn bí ó bá tilẹ̀ jẹ́ pé ipò àti ọlá wọn yàtọ̀ síra. Àwọn tí ó bá ríra gẹ́gẹ́ bí ọ̀rẹ́ kò gbọdọ̀ dalẹ̀ tàbí ṣokùnfà àkóbá fún ara wọn.

Písọ òdodo àti fífi ọkàn tán ara ẹni se pàtàki lááàrín ọ̀rẹ́. Èyí ni ó máa ń jẹ́ kí àjọṣẹ wọn pẹ́ tí wọn yóò sì dàbí ọmọ ìyá. Ọ̀pọ̀ ọ̀rẹ́ ni ó ti ṣe àkóbá fun ara wọn látàrí ìlara àti àìṣòótọ́ pẹ̀lú ara wọn.

Oríṣìíríṣìí ọ̀rẹ́ ló wà. Bí ọ̀rẹ́ dáadáa ṣe wà ni ọ̀rẹ́ burúkú wà. Ọ̀rẹ́ dáadáa yì í jẹ́ ọ̀rẹ́ òtítọ́ tí wọ́n ń wá ìlọsíwájú fún ara wọn. Wọ́n máa ń fi ojú fo àbùkù tàbí àléèbù ara wọn. Ọ̀rẹ́ burúkú máa ń mú ìfàsẹ́yìn bá ẹnìkejì. Irúfẹ́ àwọn wọ̀nyí máa ń lara ọ̀rẹ́ tí wọ́n ó sì ma wá ìṣubú rẹ̀. Ọ̀rẹ́ ojú tàbí orí ahọ́n ni àwọn wọ̀nyí.

Yàtọ̀ sí pé ọ̀rẹ́ lẹ̀ jẹ́ ẹni burúkú tàbí ènìyàn dáadáa, ọ̀rẹ́ lè jẹ́ ẹni tí a ní àjọṣe tí kò rinlẹ̀ pẹ̀lú. Irú ọ̀rẹ́ bàyìí ni ojúlùmọ̀. Ojúlùmọ̀ ni ẹni tí a mọ̀ ṣùgbọ́n tí a kò lè finú hàn tàbí sọ ẹ̀dùn ọkàn wa fún. Wọ́n sábà máa ń jẹ́ ẹni tí a ṣe alábàápàdé níbì kan, ẹni tí ó jẹ́ ọ̀rẹ́ sí ọ̀rẹ́ tímọ̀tímọ̀ wa àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bákan náà, ọ̀rẹ́ ìmùlẹ̀ tàbí ọ̀rẹ́ tímọ̀tímọ̀ wà. Irúfẹ́ ọ̀rẹ́ yì í ni àwọn tí ó dàbí ọmọ ìyá tí wọ́n ń dúró ti ara wọn. Àwọn bàyìí ma ń fi àṣírí pamọ́ sọ́wọ́ ara wọn. Wọ́n lè jẹ́ ọ̀rẹ́ làti kékeré tàbí kí ó jẹ́ pé ìgbà tí wọ́n dàgbà ni ọ̀rẹ́ wọn rinlẹ̀.

### 4.2 Àbùdá Ọ̀rẹ́ Gidi

Lára àwọn ohun tí ó ṣe pàtàkì lááárín ọ̀rẹ́ tí ó sì jẹ́ àbùdá ọ̀rẹ́ gidi ni

- Ṣíṣe òótọ́ pẹ̀lú ara ẹni.
- Ọ̀rẹ́ gbọ́dọ̀ jẹ́ onínú ire.
- Ṣíṣe ìrànlọ́wọ́ fún ara wọn.
- Ọ̀rẹ́ gbọ́dọ̀ le gbọ́ ara wọn yé.
- Wọ́n gbọ́dọ̀ ní ẹ̀mí ìdaríjì pàápàá nígbà tí ède-àìyédè bá wáyé
- Gbígba ara wọn ní ìmọ̀ràn rere.
- Wíwá ìlọsíwájú ara wọn.
- Ṣíṣe àwárí ara wọn lóòrèkóòrè.
- Ọ̀rẹ́ gbọ́dọ̀ tu ara wọn nínú nígbà tí àjálù bá ṣẹlẹ̀.

## 4.3 Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Ọ̀rẹ́

Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹgbé ẹyẹ ni ẹyẹ ń wọ́ tọ̀, àwọn tí èrò wọn bá papọ̀ nípa oríṣìíríṣìí nǹkan bí i gbígba afẹ̀, ríronú àti níní ìmọ̀ ni ó yẹ kí wọn jẹ́ ọ̀rẹ́. Èyí yóò fi àyè sílẹ̀ fún wọn láti fi inú tán ara wọn kí wọ́n sì pọ́n ìbáṣepọ̀ wọn lé. Yorùbá gbà pé ìwà jọ ìwà ni ń jẹ́ ọ̀rẹ́ jọ ọ̀rẹ́. Kò sí nínú ìwà Yorùbá láti fi tipátipá yan ọ̀rẹ́. Èrò wọn ni pé ọmọ tí ó bá ṣípá la ń gbé jó. Nípa báyìí, wọn kìí yan ọ̀rẹ́ onírìkíṣí tí yóò mú ìfàséyìn bá wọn. Rìkíṣí ma ń da àárín ọ̀rẹ́ rú gẹ́gẹ́ bí ó ti hàn nínú òwe Yorùbá pé rìkíṣí pa wọ́n pọ̀ wọ́n dọ̀rẹ́, kò lọ́jọ́ kò lóṣù ọ̀rẹ́ bàjẹ́.

Yorùbá gbà pé ọ̀rẹ́ kítíkítí, iyèkan kàtàkàtà; bọ́rẹ̀ẹ́ kítíkítí bá kú, iyèkan kàtàkàtà ni ń gbé e sin. Ìgbàgbọ́ wọn ni pé kò sí bí ìmùlẹ̀ tàbí àjọṣepọ̀ ṣe máa wà láàárín ọ̀rẹ́ tí èniyàn fi gbọdọ̀ nífẹ̀ẹ́ ọ̀rẹ́ ju ẹbí lọ. Èrò Yorùbá ni pé okùn ẹbí le, ó sì ṣe pàtàkì ju gbogbo ìbáṣe tí ẹ̀dá lè ní pẹ̀lú ẹlòmíràn lọ.

Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé kò sí ohun tí ó dàbí ọ̀rẹ́ òtítọ́. Irú ọ̀rẹ́ yìí máa ń wá ilọsíwájú fún ẹnìkejì rẹ̀. Wọ́n gbà pé ọ̀rẹ́ tí ó lè duró tini nígbà tí nǹkan bá le koko kò wọ́pọ̀, èyí ni wọ́n fi ń sọ pé abánikú ọ̀rẹ́ ṣọ̀wọ́n.

Àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé ọ̀rẹ́ lè ṣe àkóbá fún ènìyàn bí a kò bá kíyèsára nípa fífi inú hàn ọ̀rẹ́ pátápátá, èrò wọn ni pé ọ̀rẹ́ ọdún mẹ́ta ò ṣe é finú hàn tán. Bí àpẹẹrẹ, ìgbagbọ́ Yorùbá ni pé ọ̀rẹ́ lè dani nígbà tí ó bá di ọ̀ràn owó. Èyí fara hàn nínú òwe Yorùbá tí ó sọ pé ajé ní ń ba ojú ọ̀rẹ́ jẹ́. Bákan náà, kì í ṣe ohun kàyéfì láti rí ọ̀rẹ́ tí ó ń dalẹ̀ ara wọn nítorí bí ẹbí bá lè dani, ọ̀rẹ́ náà lè dani.

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ìpínyà lè dé bá ọ̀rẹ́. Wọ́n gbà pé ogún ọmọdé kò lè ṣeré fún ogún ọdún. Lára ohun tí ó lè fa ìpínyà yìí ni ikú, ìgbéyàwó lọ sí ìlú mìíràn, dídalẹ̀ ara wọn àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Yíyan ọ̀rẹ́ lóde òní gba ọ̀nà àrà ó sì fi àyè sílẹ̀ fún oríṣìíríṣìí nńkan. A ń ní ìbáṣe pẹ̀lú onírúurú ènìyàn tí a sì ń pè wọ́n ní ọ̀rẹ́ ṣùgbọ́n tó jẹ́ pé àyè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n wà ní ọkàn wa, ìwúlò ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni wọ́n sì wà fún. Kò pọn dandan fún ènìyàn láti rírà tàbí mọ ara wọn délé kí

wọ́n tó di ọ̀rẹ́. Àwọn ìkànnì ìbánidọ́ọ̀rẹ́ ìgbàlódé (*Facebook, Instagram, Twitter*) ti ṣí àyè sílẹ̀ láti pàdé ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ ènìyàn tí wọn kò sì nílò láti mọ ẹyẹ tí ó ṣu wọ́n. Ìlànà ìbánidọ́rẹ̀ẹ́ tuntun yìí jẹ́ kí àyè wà fún ọ̀rẹ́ láti bẹ ara wọn wò láì mú ìnira lọ́wọ́. Bí ọ̀rẹ́ kò bá wà ní ìtòsí ara wọn, wọ́n lè bá ara wọn sọ̀rọ̀ kí wọ́n sì ríra wọn sójú. Bí àǹfààní ṣe wà nínú ìrúfẹ́ ọ̀rẹ́ báyìí ni àléèbù náà wà pẹ̀lú. Ọ̀pọ̀ ènìyàn ni ó ti ṣe àgbákò ikú tàbí kí wọ́n fara pa látàrí ọ̀rẹ́ tí wọ́n yàn nípasẹ̀ ìbánidọ́rẹ̀ẹ́ tuntun yìí.  Bákan náà, ọmọdé àti àgbàlagbà ń dá ọ̀rẹ́, obìnrin àti ọkùnrin náà máa ń ṣe ọ̀rẹ́ láì mú ìnira lọ́wọ́. Èyí kì í ṣe ohun kàyéfì ní àwùjọ òde òní.

## 5.0 Ìsọnísókí

Nínú ìpín kẹrin lábẹ́ módù kejì yìí a ti kẹ́kọ̀ọ́ pe:

- Ọ̀rẹ́ túmọ̀ sí níní ìbáṣepọ̀ tó dán mọ́ràn lááárín ènìyàn méjì tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.
- Yorùbá gbà pé ìwà jọ ìwà ni ń jẹ́ ọ̀rẹ́ jọ ọ̀rẹ́.
- Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé kò sí ohun tí ó dàbí ọ̀rẹ́ òtítọ́.
- Níní ọ̀rẹ́ ṣe pàtàkì ṣùgbọ̀n a gbọ́dọ̀ kíyèsí nítorí bí ọ̀rẹ́ ṣe ń lani bẹ́ẹ̀ náà ni ọ̀rẹ́ ṣe lè pani.
- Ẹ̀dá kò gbọdọ̀ gbé gbogbo ayé rẹ̀ lé ọ̀rẹ́ lọ́wọ́.
- Ẹni tí ó bá ma yan ọ̀rẹ̀ gbọ́dọ̀ ṣe èyí pẹ̀lú ẹni tí ìwà àti ìṣe wọn bára mú.
- Òtítọ́ inú àti dídúró tini kò gbọdọ̀ ṣọ̀wọ́n láàrin ọ̀rẹ́ méjì.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

a. Kí ni ìyàtọ̀ lááárín ojúlùmọ̀ àti ọ̀rẹ́?
b. Kí ni ó lè fa ìpinyà lááárín ọ̀rẹ́?
d. Ǹjẹ́ Yorùbá gbà pé ọ̀rẹ́ lè dani?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Amichai-Hamburger, Y., Kingsbury, M., and Schneider, B.H. 2013. "Friendship: An Old Concept with a New Meaning?" *Computers in Human Behaviour* 29 (33-39)

Falola, T. ati Akinyemi, A. (ed.) 2016. *Encyclopedia of the Yorùbá.* Bloomington: Indiana University Press

Owomoyela, O. 2005. Yoruba Proverbs. London: University of Nebraska Press

Policarpo, V. 2015. "What is a Friend? An Exploratory Typology of the Meanings of Friendship" *Journal of Social Science and Personal Relationships* 4 (171-191)

# ÌPÍN KARÙN-ÚN: ÌGBÀGBỌ́ AWỌN YORÙBÁ NÍPA Ẹ̀SAN

## Ìfáàrà

Ìpín yìi ṣàfihàn ẹ̀san gẹ́gẹ́ bí i èrèdí ìṣe ènìyàn ní awùjọ gẹ́gẹ́ bí ó ṣe hàn nínú ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá. Bákan náà ni a tọ́ka sí bí Olódùmarè ṣe jẹ́ Ọba ẹlẹ́san. A ṣe àyẹ̀wò bí ó ṣe jẹ́ pé gbogbo ohun tí ènìyàn bá se ló ní èrè.

**Àkóónú:**


1.0 Ìfáàrà
2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn
3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
    4.1 Kí ni Ẹ̀san?
    4.2 Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa Ẹ̀san
5.0 Ìsọnísókí
6.0 Iṣẹ́ Síṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 Ìfáàrà

Iṣẹ́ yìí ṣe àgbéyẹ̀wò ìtumọ̀ ẹ̀san àti bí ìṣe ènìyàn ṣe lè bí ẹ̀san. À tún ṣàyẹ̀wò bí ìgbàgbọ́ Yorùbá ṣe fi hàn pé àṣegbé kan kò sí ní àwùjọ.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- Ṣàlàyé ìtùmọ̀ ẹ̀san.
- Tọ́ka sí ìṣe tí ó lè bí ẹ̀san.
- Ṣàlàyé ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ẹ̀san.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

i. Ǹjẹ́ Olódùmarè máa ń san ẹ̀san fún ẹ̀dá?

ii. Jìròrò lórí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹ̀san

iii. Ẹ̀kọ́ wo ni ẹ̀san kọ wa?

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Kí ni Ẹ̀san?

Ẹ̀san túmọ̀ sí kí ẹ̀dá jèrè ìṣe tàbí iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀ yálà ní rere tàbí ní búburú. Kò sí ohun tí ènìyàn ṣe láye tí kò ní gbẹ̀san rẹ̀. Ìṣe yì í lè jẹ́ nǹkan tí a ṣe sí ẹbí, ará, ọ̀rẹ́, ìlú, ẹni tí kò súnmọ́ wa àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Kì í ṣe dandan kí ohun tí a ṣe hàn sí gbogbo aráyé kí ó tó di pé a gbẹ̀san rẹ̀. Bí àpẹẹrẹ, bí ènìyàn bá ṣe aburú ní ìkọ̀kọ̀, ó lè jẹ́ èrè aburú yìí ni yóò jẹ́ kí àwọn ènìyàn mọ àìdára tí ó ṣe.

Ohun méjì ni pàtàkì ló máa ń fara hàn nínú ẹ̀san. Èyí ni èrè àti ìjìyà. Èrè ni ẹ̀san fún nǹkan ìwúrí. Nígbà tí ènìyàn bá ṣe ohun tí yóò jẹ́ àǹfààní fún ẹ̀dá ẹgbẹ́ rẹ̀, dandan ni kí ó gba ẹ̀san rere. Ìjìyà máa ń wáyé nígbà tí ẹnìkan tàbí àkójọpọ̀ ènìyàn bá ṣẹ̀ sí òfin tàbí ìṣe àwujọ. Irúfẹ́ ìṣe aburú báyìí lè jẹ́ olè jíjà, ìpànìyàn, ilẹ̀ dídà, fífi ipá bá obìnrin láṣepọ̀, sísa oògùn burúkú sí ẹnìkejì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

### 4.2 Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Ẹ̀san

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ohun gbogbo ló ní ẹ̀san, èyí sì lè wáyé gẹ́gẹ́ bí èrè ìwà dáadáa tàbí ìjìyà ìwà búrurú, èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pé “àṣegbé kan kò sí, àṣepamọ́ ló wà”, fún ìdí èyí kò yẹ kí ènìyàn yapa kúrò ní ìlànà ọmọlúàbí dé bi pé yóò pa ẹnìkejì rẹ̀ lára. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé Olódùmarè ni Ọba ẹlẹ́san tí Ó ní agbára tí ó tóbi jù lọ láti san ẹ̀san fún ẹ̀dá. Kò sí ẹ̀dá tí ó lè bọ́ lọ́wọ́ ìdájọ́ Olódùmarè. Èrò yì í hàn nínu ẹsẹ ifá Ogbè Ate.

> Olódùmarè ló ni ilẹ̀
> Olódùmarè ló ni ìdájọ́
> Ẹ̀san ni ti Olódùmarè

Ọba yíò san fún oníkálùkù
Gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ ọwọ́ wọn

(Ogbè Atẹ)

Kókó tí ó hàn lókè yìí ni pé Olódùmarè ló ni gbogbo àṣẹ ní ìkápá. Bákan náà, kò sí ohun tí ènìyàn gbìn síwájú Olódùmarè tí kò ní ká èso rẹ̀.

Yàtọ̀ sí ẹ̀san Olódùmarè, Yorùbá ní ìgbàgbọ́ pe àwọn òrìṣà lè san ẹ̀san fún ènìyàn gẹ́gẹ́ bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ. Bí àpẹẹrẹ, bí aburú kan bá ṣẹlẹ̀ ní àárín ìlú tí ó sì rú àwọn ènìyàn lójú, wọ́n á tọ òrìṣà tí wọ́n ń bọ lọ láti rí i pé ẹni tó wà nídìí ọ̀rọ̀ náà gba ẹ̀san gẹ́gẹ́ bí ó ti yẹ.

Yorùbá gbà pé kò sí bí ènìyàn ṣe lè ma ṣe aburú tó yóò gba ẹ̀san rẹ̀ lọ́jọ́ kan. Èyí ni wọ́n fi ń sọ pé:

Bí iwájú ìkà bá dára
Ẹ̀hìn ìkà kò ní sunwọ̀n
Adifá fún òtítọ́ inú
Ọmọ òtítọ́ afìtẹ̀lẹ̀ tìrẹ̀lẹ̀tìrẹ̀lẹ̀
(Ogbè Atẹ)

Yorùbá gbàgbọ́ pé ó ṣe é ṣe kí ẹ̀san ìṣe ènìyàn má jẹ́ kíákíá. Èyí ni wọ́n fi n sọ pé “ọmọdé bú ìrókò, ó bojú wẹ̀yìn; ṣe oòjọ́ ni olúwéré ń pani ni?”. Bí ènìyàn bá ṣe nǹkan tí ó sì ti gbàgbé ohun náà, dájúdájú yóò jẹ ère tàbí ìyà ìṣe náà. Èrò Yorùbá ni pé aburú kò lè bá ẹ̀dá tí ó bá ń ṣe rere. Ìdí nìyí tí wọ́n fi ń sọ pé olóòótọ́ kan kì í kú sípò ìkà.

Kí etò àwùjọ lè máa tẹ̀síwájú ni Yorùbá ṣe ń tẹpẹlẹ mọ́ dáadáa tí ó wà nínú ṣíṣe rere àti aburú tí ó wà nínú àìdára. Bí àpẹẹrẹ, wọ́n gbà pé bí ènìyàn bá dalẹ̀, yóò bálẹ̀ lọ́. Kò sí àṣegbé nínú èrò Yorùbá. Wọ́n gbà pé àtoore àti ìkà ọ̀kan kì í gbé, àti pé àṣesílẹ̀ ni àbọ̀wábá. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé dandan ni kí ènìyàn gba ẹ̀san déédé ohun tí ó bá ṣe, pàápàá bí ó bá jẹ́ ohun burúkú. Èyí hàn nínú ìpèdè Yorùbá pé bí èkòló bá kọ ebè, ara rẹ̀ ni yóò gbìn sí i. Bákan náà ni ẹsẹ ifá kan fi hàn pé:

Afinitì ní í pẹrú
Èpè ní í polè
Ilẹ̀ dídà ní í polè
Alájọbí ní í payèkan
A dífá fún ọ̀kàn-lé-nírinwó irúmọlẹ̀
Níjọ́ tí wọ́n ń jà re ọ̀dọ̀ Olódùmarè

Ènìyàn lè ṣẹ̀ aburú sí ìlú tàbí ẹ̀dá ẹgbẹ́ rẹ̀. Irúfẹ́ ẹ̀san tí ó máa ń tara èyí jáde sábà ń jẹ́ ìjìyà tí àwùjọ ti là sílẹ̀. Bí ènìyàn bá jẹ̀bi ẹ̀sùn ìpànìyàn, ó ṣe é ṣe kí wọ́n pa á. Nígbà mìíràn ènìyàn lè hùwà búrubú kí ó sì jẹ́ lílé ẹni bẹ́ẹ̀ kúrò nínú ìlú ni yóò gbẹ̀yìn rẹ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹ̀san ìwà náà.

Òbí tàbí ìran kan ti lè ṣe aburú tàbí rere lọ́jọ́ pípẹ́ tí yóò sì jẹ́ pé àwọn tí kò nípa nínú ìṣẹ̀lẹ̀ náà ni yóò gba ẹ̀san rẹ̀. Yàtọ̀ sí àwọn ohun ti a là sílẹ̀ lókè yìí, o ṣe é ṣe kí ẹ̀san ìṣe ẹ̀dá ké lára ẹbí, tàbí ìlú lápapọ̀. Èyí sì lè jẹ́ ẹ̀san rere tàbí aburú. Àpẹẹrẹ mìíràn tí ó ń ṣàfihàn èrò Yorùbá nípa ẹ̀san ni:

Purọ́purọ́ kú, ó kú  sígbó iná
Ṣìkàṣìkà kú, ó kú sọ́dàn
Ṣòótọ́ṣòótọ́ kú, ó kú gbẹdẹmukẹ, ó fẹ̀hìntì amùleke
Ọ̀rúnmìlà awo Ayé ló dúfá fún Ayé
Nígbà tí wọ́n ń ṣe ayé, tí ayé kò rójú, tí ayé kò jọ
Wọ́n ní kí wọ́n ó kára ńlẹ̀ ẹbọ ni kí wọ́n ó ṣe
Olóòótọ́ nìkan ni ńbẹ lẹ̀hìn tí ń ṣẹbọ
Ǹjẹ́ ṣòtítọ́ ṣòdodo, ṣoore máṣìkà
Òtítọ́ abọ̀nà tooro, òṣìkà abọ̀nà gbàràrà
Ṣòtítọ́ ṣòdodo, ṣòdodo ṣòtítọ́
Ẹni tí ó ṣòtítọ́ ni imọlẹ̀ ń gbè
(Ogbè’sá)

Èké ò kunni

Ìkà ò kọmọ ènìyàn
Békèé bá nyọ́lẹ̀ dáà
Ohun burúkú á máa yọ́ wọn ṣe
A dífá fún Ṣàgbàgìrìyàn
Èyí tí yóò balé aṣòótọ́
Ṣòtítọ́, ṣòdodo
Ẹni bá ṣòtítọ́ ni imọlẹ̀ ńgbè
(Òtúrá rera)

## 5.0 Isọnísókí

Nínú ìpín karùn-ún lábẹ́ módù kejì yìí a ti kékọ̀ọ́ pe:

- Ẹ̀san túmọ̀ sí kí ẹ̀dá jèrè ìṣe tàbí iṣẹ́ ọwọ́ rẹ̀ yálà ní rere tàbí ní búburú.
- Kì í ṣe dandan kí ohun tí a ṣe hàn sí gbogbo aráyé kí ó tó di pé a gbẹ̀san rẹ̀.
- Èrè àti ìjìyà jẹ́ ohun méjì pàtàkì tí ó máa ń fara hàn nínú ẹ̀san.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ohun gbogbo ló ní ẹ̀san, èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pé “àṣegbé kan kò sí, àṣepamọ́ ló wà”,
- Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé Olódùmarè ni Ọba ẹlẹ́san tí Ó ní agbára tí ó tóbi jù lọ láti san ẹ̀san fún ẹ̀dá.
- Yàtọ̀ sí ẹ̀san Olódùmarè, Yorùbá ní ìgbàgbọ́ pe àwọn òrìṣà lè san ẹ̀san fún ènìyàn gẹ́gẹ́ bí ó ti tọ́ àti bí ó ti yẹ.
- Yorùbá gbàgbọ́ pé ó ṣe é ṣe kí ẹ̀san ìṣe ènìyàn má jẹ́ kíákíá.

Adìyẹ ìrànà kì í ṣẹran àjẹgbé ni ọ̀rọ̀ ẹ̀san nínú ìgbàgbọ́ àti èrò Yorùbá. Kò sí ohun tí ẹ̀dá ṣe láyè tí kò ní jère rẹ̀ bó pẹ́ bó yá. Ẹ̀san tí ó dájú jùlọ ni ẹ̀san Olódùmarè. Bí ìṣe rere ṣe ní ẹ̀san tirẹ̀ náà ni aburú ní ẹ̀san tirẹ̀.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

- Àwọn ẹsẹ ifá wo ló fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ẹ̀san ń bẹ?
- Kí ni ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa ṣíṣe aburú?

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Asante, M.K. 2009. *Encyclopedia of African Religion.* California: SAGE Publications Inc.

Awodiran, O.A. 2012. *Ifa: Ohun Ijinlẹ Aye (Ifa: The Philosophy of Life)*. Lagos: Fagbenga Ventures Nigeria

## MÓDÙ KẸTA

## ÌPÍN KÌÍNÍ: ÈRÒ ÀWỌN YORÙBÁ NÍPA ORÚKỌ

Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Orúkọ
4.2 Ayẹyẹ tí ó rọ̀ mọ́ ìsọmọlórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá
4.3 Díẹ̀ lára orúkọ Yorùbá àti ìtumọ̀ wọn
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáárà

Ní ilẹ̀ Yorùbá orúkọ ṣe pàtàkì, ó ṣe kókó, ọjọ́ tí a bá fẹ́ sọ ọmọ ní orúkọ ni a máa ń ṣe ayẹyẹ, àti ìtọ́mí sọ́mọ lẹ́nu. Orúkọ Yorùbá pọ̀, nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a ti ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí àwọn orúkọ Yorùbá àti ìtumọ̀ wọn.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóó le:

Ṣàlàyé kíkún nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa orúkọ
Sọ àwọn ayẹyẹ tí ó rọ̀ mọ́ ìsọmọlórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá
Ṣàlàyé pẹ̀lú àpẹẹrẹ lórí oríṣi kọ̀ọ̀kan
Sọ ìtumọ̀ díẹ̀ lára àwọn orúkọ Yorùbá

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Ṣàlàyé lórí orúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá
2. Pín orúkọ Yorùbá sí onírúurú ọ̀nà
3. Sọ márùn-ún nínú àwọn orúkọ Yorùbá àti ìtumọ̀ wọn.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ìgbàgbọ́ Yorùbá Nípa Orúkọ

Orúkọ ṣe pàtàkì fún gbogbo ẹ̀dá láyé, yálà ènìyàn, ẹranko tàbí ewéko, kò sí ẹ̀dá ènìyàn tí kò ní orúkọ tí à ń pè é, à ń fún ẹ̀dá ni orúkọ gẹ́gẹ́ bí àmì tàbí ọ̀nà ìdánimọ̀yàtọ̀ sí ara wọn. Orúkọ máa ń lẹ̀ mọ́ni lára pẹ́kípẹ́kí ni, nítorí náà kò sí ẹni tí ó ń fẹ́ kí wọ́n fi orúkọ tí kò bójúmu pé òun, nítorí àwọn Yorùbá máa ń sọ pé 'orúkọ ń ro ni, bẹ́ẹ̀ ni oríkì a sì máa ro ènìyàn', èyí túmọ̀ sì pé irúfẹ́ orúkọ tí a bá fún ènìyàn tàbí nǹkan máa ń jẹyọ nínú ìwà àti ìṣe ìgbésí ayé ènìyàn tàbí irú nǹkan bẹ́ẹ̀.

Ní ilẹ̀ Yorùbá, àṣà ìsọmọlórúkọ ṣe pàtàkì púpọ̀, èyí ni àwọn Yorùbá kò ṣe fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú un rárá. Ètò fífún ọmọ ní orúkọ jẹ́ ètò tó kan gbogbo ẹbí pátá. Tí ó bá tí ku oṣù díẹ̀ tí aboyún yóò bímọ, tọkọtaya tí ó ń retí ọmọ tuntun yóó ti máa fi inú ro irú orúkọ tí wọn yóò sọ ọmọ wọn. Yorùbá¸bọ̀ wọ́n ní ilé làá wò ká tó sọ ọmọ lórúkọ, ní ọ̀pọ̀ ìgbà ló jẹ́ pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tàbí àmì tí aboyún ba ń rí nígbà tí ó wà nínú oyún, ni yóò jẹ́ kí wọ́n mọ orúkọ tí wọ́n fẹ́ sọ ọmọ, nígbà mìíràn, ọ̀nà tí a bá gbà bí ọmọ ni yóó sọ irú orúkọ tí ọmọ yóó jẹ́. Bákan náà, àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó bá ń ṣẹlẹ̀ lásìkò tí aboyún bá wà nínú oyún, títí di àsìkò tí yóó bímọ tàbí ìgbà àti àsìkò ti aboyún bá bímọ, máa ń sọ irúfẹ orúkọ tí ọmọ yóò jẹ́.

### 4.2 Ayẹyẹ tí ó rọ̀ mọ ìsọmọlórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá

Ní ilẹ̀ Yorùbá ní ayé àtijọ́, ọjọ́ kẹsàn-án ní wọ́n ń sọ ọmọkùnrin ní orúkọ, nígbà tí wọ́n ń sọ ọmọbìnrin lórúkọ ni ọjọ́ keje. Àwọn ìbejì ni à ń sọ lórúkọ ni ọjọ́ kejọ,tí àwọn ìbejì náà bá jẹ́ ọkùnrin àti obìnrin. Tí àwọn ìbejì bá jẹ́ ọkùnrin méjì, ọjọ́ kẹsàn-án ni ìsọmọlórúkọ wọn yóó bọ́ sí, tí ó bá sì jẹ́ obìnrin ni àwọn méjéèjì ọjọ́ kẹfà ni tiwọn.

Ààrọ̀ kùtù ni à ń sọ ọmọ lórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá ní àtijọ́. Àwọn ìdílé kan máa ń ṣe orò ní ọjọ́ kẹfà tí a bá bi ọmọ, orò ìdílé tí a mọ̀ sí ìfàlọmọ tàbí ìtọ́rúsọ́mọlẹ́nu. Ẹni tí ó bá jẹ́ àgbà nínú àwọn obìnrin ilé ni ó máa ń darí ètò yìí. Wọ́n á kó àwọn èròjà bíi, iyọ̀, epo, oyin, ààdùn, obì, eku, ẹja, irú, ataare, ẹ̀kọ, àmàlà àti àwọn ohun mìíràn tí ẹnu ń jẹ, sílẹ̀, wọ́n á ti dín eku, àti ẹja yìí mọ ata wọ́n a máa fi kan ọmọ lẹ́nu, ìyá ọmọ yóó sì máa gbà á sí ẹnu ara rẹ̀, bí wọn ṣe fi ń ṣe àdúrà fún ọmọ, pẹ̀lú ìrètí pé ọmọ yóó mu ún lọ́yàn ìyá rẹ̀.Gbogbo àwọn ènìyàn tí ó wà níbẹ̀ yóó sì máa ṣe àmí sí àwọn ìwúre náà.

Lẹ́yìn èyí ni ìyààlé ilé yóó bu omi sí orí òrùlé, wọn yóó si fi ara ọmọ tuntun gba omi tí ó ń ṣàn bọ̀ nílẹ̀ láti orí òrùlé, ìyá ọmọ ni yóó máa gbé ọmọ náà sáré wọlé, sáré jáde lẹ́ẹ̀meje bí ó bá jẹ́ obìnrin, ni ẹ̀ẹmẹ́sàn-án bí ó bá jẹ́ ọkùnrin. Bí omi náà bá ti ń kan ọmọ lára, ni yóó máà ké, àwọn ènìyàn tí ó wà níbẹ̀ yóó máà rẹ́rìn-ín, wọ́n ó sì máa fi tayọ̀tayọ̀ kí ọmọ tuntn káàbọ̀ sí ayé.

Lẹ́yìn èyí ni wọ́n yóó fi àwọn ohun-èlò bíi obì, orógbó, ataare, epo pupa, oyin, ìrèké, iyọ̀, omi tútù, ọtí òyìnbó ṣe àdúrà fún ọmọ tuntun pé

| | |
|---|---|
| Obì: | kò bi ikú àti àrùn dànù, fún ọmọ náà |
| Orógbó: | kí ọmọ náà dàgbà darúgbó |
| Ataare: | kí ọmọ náà ṣẹ́gun ọ̀tá, kí ó sì bímọ púpọ̀ |
| Epo pupa: | kí ayé rọ ọmọ náà lọ́rùn |
| Oyin: | kí ayé ọmọ náà dún bí oyin kalẹ̀ |
| Ìrèké: | kí ayé ọmọ náà dùn |
| Ààdùn: | kí ayé ọmọ náà dún bí oyin |
| Iyọ̀: | kí ayé ọmọ náà dùn, kí ó má tẹ́ láàárín ẹgbẹ́ |
| Ọtí òyìnbó: | kí ọmọ náà má tẹ́ ni àwùjọ |

Omi tútù: ayé ọmọ náà yóó tutù pẹ̀sẹ̀ bí omi tútù

## 4.3 Díẹ̀ lára orúkọ Yorùbá àti ìtumọ̀ wọn

A lè pín orúkọ Yorùbá sí àwọn ọ̀nà wọ̀nyí. Àmútọ̀runwá, àbísọ, àbíkú, oríkì, orúkọ ìdílé, orúkọ oyè ìlú, orúkọ ẹ̀ṣin, àti orúkọ ìnagijẹ.

**Orúkọ Àmútọ̀runwá**

Táíwò: (Tọ́ ayé wò): ọmọ tí ó kọ́kọ́ wá sí ayé nínú àwọn ìbejì.

Kẹ́hìndé: Ọmọ tó Kẹ́yìndé ni Yorùbá gbà pé ó jẹ ẹ̀gbọ́n fún Táyéwò, wọn máa ń sọ pé akẹ́yìndé gbẹ̀gbọ́n.

Ìdòwú: ọmọ tí a bí lẹ́yìn ìbejì, Yorùbá máa ń sọ pé èṣù lẹ́yìn ìbejì ni

Àlàbá: ọmọ tí a bí lẹ́yìn Ìdòwú

Ìdògbé: ọmọ tí a bí tẹ̀lé Ìdògbé

Ọ̀jó: ọmọ tí o fi ìbí rẹ̀ kọ́rùn, nígbà tí a bíi, tí ó sì jẹ́ ọmọkùnrin

Àìná: ọmọ tí o fi ibi rẹ̀ kọ́rùn, nígbà tí a bíi tí ó sì jẹ́ ọmọbìnrin

Dàda: ọmọ tí irún rẹ̀ pọ̀, tí ó sì takókó

Ọ̀kẹ́: ọmọ tí ó wà nínú àpò fẹ́lẹ́fẹ́lẹ́, nígbà tí a bíi

Ìgè: ọmọ tí ó kọ́kọ́ yọ ọwọ́ tàbí ẹsẹ̀ síta nígbà tí a fẹ́ bí i.

Olúgbódi: ọmọ tí ó ní ìka mẹ́fà ni ọwọ́ tàbí ẹsẹ nígbà tí a bí i.Àwọn ọmọ yìí náà ni ó tún ń jẹ́ 'Odù' tàbí Òhúù

Òní: ọmọ tó máa ń ké tọ̀sán tòru

Ọ̀la: ọmọ tí a bí tẹ̀lé òní

Ọ̀túnla: ọmọ tí a bí tẹ̀lé ọ̀la

Àasà: ọmọ tí ó máa ń ké, tí a bá ti ń wẹ̀ fún un

Ìrèní: ọmọ tí a bí lẹ́yìn Ọ̀túnla

Ìrùnní: ọmọ tí a bí lẹ́yìn Ìrèní

Ìfàní: ọmọ tí a bí tẹ̀lé Ìrùnní

Ìjẹ̀ní: ọmọ tí a bí tẹ̀lé Ìfàní

Ìjọ̀ní: ọmọ tí a bí tẹ̀lé Ìjẹ̀ní

Abíọ́nà : ọmọ tí a bí sí ojú ọ̀nà, bóyá, ọ̀nà oko, ọjà, odò, òde tàbí ọ̀nà ilé

Abíọ́jà: ọmọ tí a bí sínú ọjà, pàápàá ní ọjọ́ ọjà

Jọ́ọ̀sẹ̀ (ọjọ́-ọ̀sẹ̀): ọmọbìnrin tí a bí lásìkò ọdún òrìṣàálá

Ọjọ́awo: ọmọ tí a bí lásìkò ọdún òrìṣàálá

Abíára: ọmọ tí ìyá rẹ kò mọ̀ pé òun lóyún, tí ọkọ rẹ̀ fi kú, ṣùgbọ́n lẹ́yìn ti ọkọ kú tán, ni ó tó mọ̀

Àbátàn : ọmọ ti babaláwo sọ fún ìyá rẹ̀ pé kí ó lọ bọ òrìṣà odò kí ó tó lóyún rẹ̀. Àbàtàn ni orúkọ ọmọ tí a bí náà yóò máa jẹ́.

Amúṣàn-án: ọmọ tí babaláwo sọ fún ìyá rẹ̀ kí ó lọ bọ Ọbàtálá kí á tó lóyún rẹ̀ (irú ọmọ bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ ní eégún tirẹ̀)

Amósùn/Dọ̀pẹ̀mú: Tí ìyàwó babaláwo kò bá rí ọmọ bí, ti babaláwo yìí bá fi ọ̀rọ̀ lọ babaláwo mìíràn, tí wọ́n dífá, tí Odù 'òtùá tàbí 'ìrosùn' bá yọ lójú ọpọ́n ifá. Tí obìnrin yìí bá fi lóyún, tí ó sì bímọ, Amósùn ni tí ó bá jẹ ọkùnrin. Ti irú ọmọ bẹ́ẹ̀ bá jẹ́ obìnrin Dọ̀pẹ̀mú ni orúkọ tí yóò máa jẹ́.

Ìlọ̀rí: ọmọ tí ìyá rẹ kò ṣe nǹkan oṣù, tí a fi bí i.

**Orúkọ Àbísọ**

Abíọ́dún: ọmọ tí a bí nígbà tí à ń ṣe ọdún ìbílẹ̀ kan.

Babátúndé, Babájídé: ọmọkùnrin tí a bí lẹ́yìn tí bàbá àgbà bá kú tán (bàbá ọkọ ni ó gbọ́dọ̀ jẹ́)

Yéwándé, Ìyábọ̀dé: ọmọbìnrin tí a bí lẹ́yìn tí ìyá àgbà bá kú tán (ìyá ọkọ ni ó gbọ́dọ̀ jẹ́)

Abídèmí: ọmọ tí a bí nígbà tí bàbá rẹ lọ sí ìrìnàjò

Morọ́mọkẹ́: Mo rí ọmọ kẹ́

Akinlẹ̀yẹ: Akọni ní èyẹ

Moṣebọ́látán: ìrètí wà pé ọ̀lá mi kò tíì tán

Ọlábọ̀dé: ọlá tún ti dé

**Orúkọ Àbíkú**

Orúkọ Àbíkú pín sí márùn-ún

(i) Orúkọ tí ó jẹ mọ́ ẹ̀bẹ̀
(ii) Orúkọ tí ó jẹ mọ́ ìhàlẹ̀
(iii) Orúkọ tí ó jẹ mọ́ àìbìkítà
(iv) Orúkọ tí ó jẹ mọ́ yẹ̀yẹ́
(v) Orúkọ tí ó jẹ mọ́ ìbẹ̀rù

**Orúkọ tí ó je mọ́ ẹ̀bẹ̀**

Málọmọ: Má lọ sí ọ̀run tàbí má kúrò láyé mọ́

Dúrósinmí: Dúró láyé kí ó sin òbí rẹ

Ọmọlàńbẹ̀: À ń bẹ ọmọ ki ó má lọ

Dúróoríkẹ̀ẹ́: Dúró kí a máa kẹ́ ọ

Mátànmí: Má tàn mí jẹ

**Orúkọ tó jẹ mọ́ ìhàlẹ̀**

Kòsọ́kọ́: kò sí ọkọ tí a ó fi gbẹ́ ilẹ̀ òkú

Orúkọtán: kò sí orúkọ mọ́

Àkísààtán: kò sí àkísà tí a ó fi sin òkú mọ́

**Orúkọ tó jẹ mọ́ yẹ̀yẹ́**

Máko: má kó mi lẹ́rù lọ

Ajá: orúkọ ẹranko

Àkújí: ẹni tí ó ti kú, tí ó tún jí

**Orúkọ tó jẹ́ mọ́ àìbìbítà**

Kílàńkó: ki ni à ń ṣe ìkomọ rẹ̀ fún

Àńwòó : à ń wò ó bóyá yóò dúró tàbí yóó lọ

Sèyíówùọ́: ṣe èyí tí ó bá wù ọ́

Omítánlójú: omi (ẹkún) ti tán lójú

**Orúkọ tó jẹ mọ́ ìbẹ̀rù**

Àńdùú: à ń du ọmọ yìí

Káṣìmaàwó: kí a ṣì máa wò ó bóyá yóó kú tàbí yóó yè

**Orúkọ ìdílé**

Fìjàbí: ọmọ tí ìdílé jà sí kí wọ́n tó bí i

Fọláwiyọ́: ọlá náà pọ̀ débi pé wọ́n fi ń fọwọ́

Ọlákúnlé: ọlá kún ilé

Oyèékànmí: oyè kàn mi

**Orúkọ Ẹ̀sìn**

Èyí ni ó fi ẹ̀sìn ìdílé hàn

Àwọn Onífá ni wọ́n máa ń jẹ́ orúkọ bíi:

Ọrẹ̀lọ́wọ̀, Ọ̀rẹ́kọ̀yà, Ọ̀pẹ́lánì, Dọ̀pẹ̀mú, Adébákin, Fádèyí, Awóṣèké àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn Olórìṣà okoni wọ́n máa ń jẹ́ orúkọ bíi:

Ọ̀pátọ́lá, Ṣóyínká, Sówẹ̀mímọ́, Ẹfúngadé, Ṣónúbi, Ṣómẹ́fun, Ọ̀pádọ̀tun, Ẹfúnyẹlà, Ọ̀pátúnjí, Ọláọ̀pá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn Ọlọ́ṣun ni wọ́n máa ń jẹ́ orúkọ bíi:

Ọ̀ṣúnkúnlé, Ọ̀sundínà, Ọ̀ṣúnbùnmi

Àwọn Eléégún ni wọn máa ń jẹ́ orúkọ bíí:

Dáṣọfúnjó, Ọ̀jẹ́wálé, Ọ̀jẹ́níkẹ̀ẹ́, Ọ̀wọ̀ṣọ, Bámimọ́rẹ́ Agọ̀ọ́gbémí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn Oníṣàngó ni wọ́n máa ń jẹ́ orúkọ bíi:

Ṣàngókúnlé, Aníṣẹ́ẹ́rẹ́, Làbádọ̀tun, Ìtíolú, Ṣàngótóyè, Ṣàngódìran àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn Ọlọ́ya ni wọ́n máa ń jẹ́ orúkọ bíi:

Ọyátẹ́gbẹ́, Ọlọ́ya, Ọyátóún, Ọyágbẹ̀yẹ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn Ológùn-ún ni wọ́n máa ń jẹ́ orúkọ bíi:

Ògúndélé, Ògúnkànmí, Ògúndáre, Ògúndìran, Ògúnfúnkẹ́ àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Àwọn Olórò ni wọ́n máa ń jẹ́ orúkọ bíi:

Oròdíjìí, Ìtádìjí, Ìtáwuyì, Olóròódé, Oròwùsì àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Orúkọ tó fi iṣẹ́ ìdílé hàn**

**Iṣẹ́ ìlú lílù**

Ọ̀pákúnlé, Àyándoṣù, Àyánníyì, Akínjọ́gbìn, Onígbìndé, Bángbégbìn, Oyèélàrán, Ọ̀párìndé àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Iṣẹ́ Ọdẹ**

Ọdẹ́wálé, Ọdẹ́fúnnkẹ́, Ọdẹ́bùnmi, Ọdẹlọlá àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ**

Ògúnlàdé, Ọláògún, Ajíbówú, Ẹ̀múgbèmí, Ògúnṣọlá, Ògúnníyì, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ

**Iṣẹ́ Olóólà**

Alábẹdé, Abẹ̀ṣínà, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Iṣẹ́ Gbẹ́nàgbẹ́nà**

Ọnàtólú, Ọnàtúndé, Ọnàbánjọ, Ọnàgbéèmí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ

**Orúkọ Ìnagijẹ**

Orúkọ ìnagijẹ yàtọ̀ gédégédé sí orúkọ àmútọ̀runwá tàbí àbísọ, orúkọ tí à ń jẹ́ lẹ́yìn tí a bá ti dàgbà ni. Ènìyàn a máa fún ara rẹ̀ ní ìnagijẹ bákan náà, àwọn ènìyàn, ọ̀rẹ́, aládùúgbò, ẹgbẹ́ tàbí ọ̀gbà lè fún ènìyàn ní orúkọ ìnagijẹ tí ó buyì kún ọmọlúàbí. Orúkọ ìnagijẹ ṣábà máa ń jẹyọ láti ara ìrísí, ìṣesi, iṣẹ́ tàbí ìhùwàsí ẹni tí a fún ní orúkọ náà.

Díẹ̀ lára àwọn orúkọ ìnagijẹ ni:

Awélọ́rùn, Ìbàdíàrán, Ẹyínńjomi, Ojúyọbọ́, Èjíwùmí, Atẹ́ẹ̀rẹ́, Márìndọ̀tí, Olówóòkéré, Olówólayémọ̀, Arígbábuwó, Ajímátìí, Owónifáàrí, Ẹyínafẹ́, Eyíngóòlù àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

**Orúkọ Oríkì**

Oríkì ní orúkọ kejì tí a máa ń fún ọmọ ní ọjọ́ tí a bá sọ ọ́ lórúkọ, oríkì yìí ni àwọn ìyá àti bàbá àgbà kúndùn láti máa fi pe ọmọ, wọ́n sì máa ń tẹ̀ ẹ́ mọ́ àwọn ọmọ mìíràn lára gẹ́gẹ́ bí orúkọ àkọ́kọ́, oríkì yìí yàtọ̀ sí oríkì ti ewì, orúkọ pọ́nńbélé ni. Gbogbo ilẹ̀ Yorùbá ni ó máa ń fún ọmọ ni oríkì, ó fẹ́rẹ̀ẹ́ jẹ́ pé àwọn Ìjẹ̀bú nìkan ni ó yàtọ̀, tí kì í fún ọmọ ni oríkì, Oríkì ọkùnrin yàtọ̀ sí ti obìnrin. Bátànì ohùn (d – d – m) wà bẹ́ẹ̀ ni bátànì (d – m – m) wà. Ladele et al (2006:162)

| **Oríkì ọkùnrin** | **Oríkì Obìnrin** |
|---|---|
| Àyìndé | Àlàkẹ́ |
| Àyìnlá | Àsúnlé |
| Àlàmú | Àwẹ̀lé |

| | |
|---|---|
| Àlàbí | Àpèkẹ́ |
| Ì̀ṣọ̀lá | Àyìnkẹ́ |
| Àlàgbé | Àyọ̀ní |
| Àkàno | Àsàkẹ́ |
| Àlàní | Àdùfẹ́ |
| Àyànó | Àríkẹ́ |
| Àdìó | Àjíkẹ́ |
| Àdìsá | Àpínkẹ́ |

**Igbàgbọ́ Àwọn Yorùbá Nípa Orúkọ**

Àwọn ẹ̀yà Yorùbá kì í fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ọ̀rọ̀ orúkọ, ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé orúkọ máa ń ro ènìyàn. Bí orúkọ ọmọ bá ti ri ni yóò ṣe máa hùwà, èyí ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé 'Orúkọ ọmọ ni ìjánu rẹ̀'. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹnìkan kì í jẹ́ àwádé àti pé bi a kò bá fẹ́ pe ara wa ní, ẹ gbọ, tí a fẹ́ kí á mọ ẹni ti à ń bá wí tàbí tí à ń pè ó di dandan ki olúkálùkù ènìyàn ní orúkọ, sísọ ọmọ lórúkọ jẹ́ àṣà pàtàkì ní ilẹ̀ Yorùbá àwọn òwe Yorùbá kàn sì ń fi ìdí èyí múlẹ̀ sí i.

Àwọn Yorùbá máa ń pòwe pé "Bí kò bá nídìí obìnrin kì í jẹ́ Kúmólú", òwe yìí fi hàn pé ní ìgbàkugbà tí ikú bá pa akọni ilé jẹ, obìnrin máa ń jẹ́ orúkọ ọkùnrin nínú ẹbí, èyí sì ń fi àpadàsí-burúkú hàn ni. Bákan náà àwọn Yorùbá máa ń sọ pé "Orúkọ ọmọ ni ìjánu rẹ̀" ohun tí òwe yìí túmọ̀ sí ni pé bí ọmọ bá ní orúkọ rere, orúkọ rere yìí yóò máa jẹ́ kìlọ̀ kìlọ̀ fún un láti máse hu ìwà búburú. Yóò máa làkàkà láti hu ìwà rere bíí ti àwọn tó ti jẹ́ orúkọ yìí ri èyí ló mú àwọn àgbà sọ pé kí Ọlọrun jẹ́ kí a lè mọ ọmọ mọ orúkọ rẹ̀. Ìgbàgbọ́

àwọn Yorùbá ni pé bí orúkọ ọmọ ba ti rí ni ọmọ yóò ṣe máa hùwà, ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé orúkọ níí ro ọmọ, síwájú síi, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé irú orúkọ tí a bá sọ ọmọ lè fi irú ènìyàn ti ọmọ béẹ̀ yóò jẹ́ tàbí tí yóò dà lọ́la hàn, láàrin àwọn Yorùbá àwọn ènìyàn a máa pòwe pé orúkọ tí a sọ ọmọ níí mọ́ ọmọ lára. Ìdí èyí ni àwọn àgbà ṣe máa ń pòwe pé “A sọ ọmọ ni Ṣódé, ó lọ sébi, ó dé, a sọ ọmọ ní Ṣóbọ̀, ó lọ àjò, ó bọ̀, a wá sọ ọmọ ni Ṣórìnlọ, ó lọ s’ajò kò dé mọ́, tani kò mọ̀ pé ilé lọmọ ti mú orúkọ anù lọ. Òwe yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé bí a bá sọ ọmọ lórúkọ búburú, búburú le bá ọmọ náà, bí a bá sì sọ ọmọ lórúkọ rere, ire ni yóò máa bá irúfẹ́ ọmọ náà.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín kínní lábẹ́ módù kẹta yìí a ti kékọ̀ọ́ pe:

- Orúkọ ṣe pàtàkì fún gbogbo ẹ̀dá láyé, , à ń fún ẹ̀dá ni orúkọ gẹ́gẹ́ bí àmì tàbí ọ̀nà ìdánimọ̀yàtọ̀ sí ara wọn.
- Àwọn ẹ̀yà Yorùbá kì í fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ọ̀rọ̀ orúkọ, ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé orúkọ máa ń ro ènìyàn.
- irúfẹ́ orúkọ tí a bá fún ènìyàn tàbí nǹkan máa ń jẹyọ nínú ìwà àti ìṣe ìgbésí ayé ènìyàn tàbí irú nǹkan bẹ́ẹ̀.
- Àárọ̀ kùtù ni à ń sọ ọmọ lórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá ní àtijọ́. Àárọ̀ kùtù ni à ń sọ ọmọ lórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá ní àtijọ́.
- A lè pín orúkọ Yorùbá sí àmútọ̀runwá, àbísọ, àbíkú, oríkì, orúkọ ìdílé, orúkọ oyè ìlú, orúkọ ẹṣin, àti orúkọ ìnagijẹ.
- A tún tẹ̀síwájú láti ṣàlàyé oríṣirííṣi orúkọ Yorùbá ọ̀nà tí a pín wọ́n sí àti ìtumọ̀ àwọn orúkọ náà.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kí ni àwọn ohun èlò tí Yorùbá máa ń lò fún ìsọmọlórúkọ ní ayé àtijọ́

2. Sọ àpẹẹrẹ orúkọ ìnagijẹ méjì mìíràn yàtọ̀ sí àwọn tí a sọ nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí

3. Ṣàlàyé lórí ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa orúkọ

4. Sọ orúkọ rẹ àti ìdí tí wọ́n fi sọ ọ́ ní àwọn orúkọ bẹ́ẹ̀.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Gàníyù, W. 2009. *Bawò Àṣà àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá*. Ibadan, Graville Publishers.

Ladele et al. 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá*. Ibadan. Gavima Press Ltd.

Adeoye, C.L. 2005. *Àṣà àti ìṣe Yorùbá.* Ibadan University Press Plc.

## ÌPÍN KEJÌ: ÈRÒ ÀWỌN YORÙBÁ NÍPA ÌLERA

Nínú Módù yìí, a ṣàlàyé kíkún lórí ojú tiYorùbá fi wo ìlera, akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yìí yóò ní òye kíkún nípa ìlera. A yiiri ìtumọ̀ ìlera wo, àti èrò àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ìlera.

Àkóónú

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

 4.1 Ohun tí ìlera jẹ́

 4.2 Bí a ṣe lè wà ní ìlera

 4.3 Àkọsílẹ̀ àwọn onímọ̀ nípa ìlera

 4.4 Àrídìmú nípa ìlera

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

A ó ṣàlàyé kíkún lórí ojú tiYorùbá fi wo ìlera, akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yìí yóò ní òye kíkún nípa ìlera. A ó yiiri ìtumọ̀ ìlera wo, àti ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ìlera.

### 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí akẹ́kọ̀ọ́ yóò:

- Ní òye kíkún nípa ìlera
- Mọ ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ìlera
- Mọ̀ nípa ipò tí ètò ìlera wà lóde òní

## 3.0 Ìbéèrè ìṣáájú

3.1 Ṣe àkóyawọ́ àlàyé nípa ìlera

3.2 Sọ àwọn ọ̀nà tí a lè gbà láti jẹ́ kí aláboyún àti ọmọdé wà ní ìlera pípé

3.3 "Àwọn oníṣègùn ìbílẹ̀ Yorùbá wúlò lóde òní" Dá sí ọ̀rọ̀ yìí.

## 4.0 Ìbẹ̀rẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Ohun tí ìlera jẹ́

Onírúurú ìtumọ̀ ni àwọn èniyàn àwùjọ fún ìlera, àwọn kan gbà pé èniyàn wà ní ìlera nígbà tí a kò bá ṣe àìsàn, àwọn mìíràn tún gbà pé ìlera ju pé kí èniyàn má ṣe àìsàn lọ, nítorí náà, ìlera jẹ́ wíwà ní alàáfíà pípé lọkan, lára àti lẹ́mìí. Àjọ tí ó ń mójútó ètò ìlera ní àgbáyé (WHO) rí ìlera bí ààyè tí èniyàn bá wà nígbà tí gbogbo àgọ́ ara, ọpọlọ àti ìgbé ayé èniyàn bá wà ní àlàáfíà yàtọ̀ sí pé kí èniyàn má nìí àrùn tàbí àìsàn.

### Ìgbàgbọ́ Àwọn Yorùbá Nípa Ìlera

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní ìlera lọrọ̀, ìgbàgbọ́ wọn ni pé bí ẹ̀dá bá wà ní ìlera pípé a jẹ́ pé ọlọ́rọ̀ ni irú ẹni bẹ́ẹ̀. Ìlera ni ipò tí èniyàn wà nígbà tí kò bá ṣe àárẹ̀ tàbí àìsàn. A tún lè sọ wípé ìlera ni tí èniyàn kò bá ní ìnira tàbí egbò, bákan náa, ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ìlera tún ní í ṣe pẹ̀lú kí èniyàn wà ní àlàáfíà nínú àgọ́ ara kí ó sì tún ní ìbàlẹ̀ ọkàn láti gbé pẹ̀lú àwọn èniyàn àwùjọ, bí èniyàn kan kò bá ní gbogbo ohun tí a sọ lókè yìí, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ kò ní ìlera pípé. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni a le gbà láti wà ní ìlera pípé.

Lákọ̀ọ́kọ́ lọ́nà àti dènà aarùn àti láti wà ní ìlera pípé ó dára kí èniyàn máa wẹ kí ó sì tún máa fọ ọwọ́ lóòrèkóòrè, ó kéré tán èèyàn gbọ́dọ̀ fọ ẹyín kí ó sì wẹ ní àárọ̀ àti alẹ́ láti lè wà ní ìlera pípé, èyí ni àwọn Yorùbá ṣe gbàgbọ́ tí wọ́n sì máa nsọ pé ìmọ́tótó ló lè

ṣẹ́gun àrùn gbogbo. Bákan náà àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé irúfẹ́ oúnjẹ tí èèyàn bá ń jẹ le jẹ́ kí ènìyàn wà ní ìlera pípé, èyí ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé ènìyàn ń jẹun láti wà láàyè ni, ènìyàn kìí jẹun láti kú.  Àwọn oúnjẹ bíi èso, ewébẹ̀, ẹran, ẹyin, ẹ̀wà, ẹja, iṣu àti oúnjẹ mìíràn máa ń ṣara lóore, ṣùgbọ́n kò dára kí èèyàn máa fi ìgbà gbogbo jẹ oúnjẹ inú ọ̀rá, agolo, ìgò àti páálí tí a ti fi àwọn kẹ́míkà pèèlò rẹ̀ bí a bá fẹ́ ní ìlera pípé. Bákan náà ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé omi mímu ṣe pàtàkì bí a bá fẹ́ wà ní àlàáfíà. Lékè gbogbo rẹ̀, ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ohun yòówù tí ènìyàn bá fẹ́ jẹ gbọdọ̀ jẹ́ ní ìwọ̀ntúnwọ̀nsì torí wàhálà ni àjẹjù ohunkóhun máa ń mú bá ara.

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá tún ni pé ṣíṣe eré ìdárayá máa ń ràn ènìyàn lọ́wọ́ láti wà ní ìlera eré ìdárayá bí i kẹ̀kẹ́ wíwà, rírin ìrìn ìgbafẹ́ tí kò jìnnà púpọ̀, ijó jíjó àti bọ́ọ̀lù gbígbá máa ń ràn ara lọ́wọ́ láti nà èyí sì máa múni wà ní ìlera. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ìlera tún ni pé bí ẹ̀dá bá ní ìfọ̀kànbalẹ̀ yóò ní ìlera torí wọ́n gbàgbọ́ pé ìrònú pani ó ju àìsàn ara lọ.

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ọmọ àti ipò pàtakì tí wọ́n to ọmọ sí ni kò jẹ́ kí wọ́n fi ọwọ yẹpẹrẹ mú ìlera aláboyún àti ọmọ wẹ́wẹ́. Ní báyìí a ṣàyẹ̀wò díẹ̀ nínú ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà mójútó ìlera aláboyún àti ọmọ wẹ́wẹ́.

Ní kété tí ìyàwó àsẹ́ṣẹ́gbe kó bá ti ri nǹkan oṣù rẹ̀ mọ́ ni àwọ́n Yorùbá tí máa ń bẹ̀rẹ̀ ìtọ́jú oríṣìíríṣìí fún un ní ilẹ̀ Yorùbá. Bí wọ́n ṣe ń gbo ewé fún aboyún yìí ni wọn yóò máa ṣe àgbo fún un láti mu àti láti wẹ̀ kí ara ẹ̀jẹ̀ ọ̀run àti ìyá tí ó ru oyún rẹ̀ lè wà ní àlàáfíà. Èyí nìkan kọ́ wọ́n tún máa ń ṣe onírúurú aájò kí a lè gbọ́ ohùn ìyá àti ọmọ ní ọjọ́ ìkúnlẹ̀, èyí túmọ̀ sí pé kí ọjọ́ ìkúnlẹ̀ le rọrùn àti kí àfọ̀n le gbó kí ó tó wọ̀. Bí àwọn Yorùbá bá wá kẹ́fín pé ọmọ fẹ́ wáyé ní kògbókògbó, oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni wọ́n máa ń gbà láti de irúfẹ́ oyún bẹ́ẹ̀. Wọ́n lè gbé irúfẹ́ oyún bẹ́ẹ̀ kọ́, wọ́n sì lè fi òrùka sí aláboyún bẹ́ẹ̀ lọ́wọ́ bí ọjọ́ ìkúnlẹ̀ bá sì tó wọn yóò yọ òrúka bẹ́ẹ̀ kúrò lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀ ní ọmọ yóò sì wáyé ní ìrọwọ́rọsẹ̀.

Bí ọmọ bá ti dáyé tán, onírúurú ìtọ́jú ni àwọn Yorùbá máa ń fún àwọn ọmọ wọn kí ìlera wọn lè dúró déédé torí wọn gbàgbọ́ pé ìlera lòògùn ọrọ̀ àti pé ẹni tó bá ti ní àlàáfíà, ohun gbogbo ló ni. Lára àwọn àgbó tí àwọn òbí máa ń fún ọmọ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá fún ìlera

pípé ni àgbo wọ́bọ́, àgbò jẹ̀dí, àgbo gìrì àti àgbo eyín. Tí ikùn ọmódé bá ń kùn tí ọmọ kò sì rí ìgbẹ́ yà déédé, àgbo wọ́bọ́ ni wọ́n máa ń fún ọmọ mú. Èyí ni yóò mú ọmọ yàgbẹ́ wọ́ọ́rọ́wọ́ tí ara rẹ̀ yóò sì balẹ̀. Bákan náà ni wọn máa ń fún ọmọ ní àgbo jẹ̀dí ní ìgbà tí ìdí ọmọ bá ń pariwo tí kò sì rí ìgbẹ́ yà lọ́nà àtijẹ́ kí ọmọ yàgbẹ́ pẹ̀lú ìrọ̀rùn. Láti kékeré ni àwọn àgbà ní ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́ ti máa ń fún ọmọ ni àgbo gìrì mú kí ara ọmọ le rọ̀ gbẹ̀jẹ̀gbẹ̀jẹ̀, èyí tí yóó dènà kí gìrì kọlu ọmọ láìrò tẹ́lẹ̀. Àgbo àti ọsẹ eyín ni wọ́n máa ń fún ọmọ bẹ̀rẹ̀ láti oṣù kejì sí ìkẹta tí ọmọ bá ti dáyé lọ́nà àtimú kí eyín híhù rọ ọmọ lọ́rùn. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé eyín ìsàlẹ̀ ni ó dára kí ọmọ kọ́kọ́ mú jáde ṣùgbọ́n tiwọ́n bá rìí pé ọmó fẹ́ kọ́kọ́ hu eyín òkè onírúurú òògùn ni wọn yóò lò kí ò lè pa eléyìí sórí. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé bí ọmọ bá fi eyín òkè ṣaájú, yóò ni ọmọ náà lára púpọ̀ yóò sì máa ṣe amódi. Ṣàsà ní àìsàn tàbí àìlera ọmọ́dé ti kò ní àgbo tí wọn yóò lò fún un ní ilẹ̀ Yorùbá, èyí rí bẹ́ẹ̀ nítorí pàtàkì tí wọ́n ka ìlera sí.

Àṣà kò dúró sójú kàn, bí ìgbà ṣe ń yí bẹ́ẹ̀ náà ni àṣà ń bá a yí. Lóde òní, ṣíṣe àyẹ̀wò sí ọ̀dọ̀ dókítà lóòrè kóòrè a máa dènà àìsàn nítorí pé àwọn oníṣègùn òyìnbó yóò ti ṣàyẹ̀wò tí yóò jẹ́ kí wọ́n mọ àwọn ohun tó yẹ ní mímójútó lásìkò. Pabambarì ohun tí ń múni wà ní ìlera ni kí a sùn lásìkò tó yẹ kí ara lè jí pépé. Ẹni tí kìí sùn a máa ṣàìsàn ní gbogbo ìgbà àmọ́ ṣáá o, oorun àsùnjù kò dára fún àgọ́ ara, yíyàgò fún igbó, sìgá àti ọtí líle pẹ̀lú àwọn oògùn olóró mìíràn le jẹ́ kí a wà ní ìlera pípé, ní kúkúrú àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé oúnjẹ tí ènìyàn ń jẹ tàbí mu lè jẹ́ kí ó ní ìlera pípé.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín keji lábẹ́ módù kẹta yìí a ti kẹ́kọ̀ọ́ pe:

- Nígbà tí àwọn kan gbà pé ènìyàn wà ní ìlera nígbà tí kò bá ṣe àìsàn, àwọn mìíràn tún gbà pé ìlera ju pé kí ènìyàn máa ṣe àìsàn lọ, nítorí, náà, ìlera jẹ́ wíwà ní alàáfíà pípé lọkan, lára àti lẹ̀mìí.
- Àjọ tí ó ń mójútó ètò ìlera ní àgbáyé (WHO) rí ìlera bí ààyè tí ènìyàn bá wà nígbà tí gbogbo àgọ́ ara, ọpọlọ àti ìgbé ayé ènìyàn bá wà ní àlàáfíà.

- Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ní pé ìlera lọrọ̀.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé irúfẹ́ oúnjẹ tí èèyàn bá ń jẹ le jẹ́ kí ènìyàn wà ní ìlera pípé.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé omi mímu ṣe pàtàkì bí a bá fẹ́ wà ní àlàáfíà.
- ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ohun yòówù tí ènìyàn bá fẹ́ jẹ gbọdọ̀ jẹ́ ní ìwọ̀ntúnwọ̀nsì torí wàhálà ni àjẹjù ohunkóhun máa ń mú bá ara.
- Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ìlera tún ni pé bí ẹ̀dá bá ní ìfọ̀kànbalẹ̀ yóò ní ìlera torí wọ́n gbàgbọ́ pé ìrònú pani ó ju àìsàn ara lọ.
- Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ọmọ àti ipò pàtakì tí wọ́n to ọmọ sí ni kò jẹ́ kí wọ́n fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú ìlera aláboyún àti ọmọ wẹ́wẹ́.

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

1. Kí ní ìlera?
2. Ṣàlàyé àwọn ohun tí ó lè mú ènìyàn wà ní ìlera pípé.
3. Jíròrò nípa ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ìlera?

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí

Adéoyè, C.L. 1979. *Àṣà Àti Ìṣe Yorùbá*. Ibadan: University Press Limited.

Johnson, S. 2001. *History of the Yorubas from the Earliest Times to the Beginning of the British Protectorate*. Lagos: CSS Limited.

Kelly, R. 2010. *Family Health and Medical Guide*. World Publishing: United States of America.

Ọlátúnbọ̀sún, F. 2012. *Ojúlówó Èdè, Àṣà àti Lítíréṣọ̀ Yorùbá fún ilé-ìwé Sẹ́kọ́ńdírí Àgbà* Òṣogbo: Ọlátúnbọ̀sún Publisher.

Ọlọ́fínṣao O.M. 2006. *Àgbéyẹ̀wò Orin Abiyamo Nílé Ìwòsàn.* B.A. Long Essay in the Department of Linguistics and African Languages, Obafemi Awolowo University. Ile-Ife Nigeria.

**ÌPÍN KẸTA: ÈRÒ ÀWỌN YORÙBÁ NÍPA ORÍ**

**Ìfáàrà:** Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a o ti máa ṣàlàyé pàtàkì orí láàárín àwọn Yorùbá, ìtumọ̀ orí,
àkúnlẹ̀yàn àti àkúnlẹ̀gbà, àti ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ nípa orí.

Àkóónú

1.0 Ìfáárà
2.0 Èròǹgbà
3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú
4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́
4.1 Orí
4.2 Orí, àkúnlẹ̀yàn àti Àkúnlẹ̀gbà
4.3 Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa orí
5.0 Ìsọníṣókí
6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe
7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

## 1.0 Ìfáárà

Orí jẹ́ ohun tí ó ṣe pàtàkì láàárín àwọn Yorùbá. Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí ohun ti wọn lè sọ láì sọ̀rọ̀ nípa orí. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni a o ti máa ṣàlàyé pàtàkì orí láàárín àwọn Yorùbá, ìtumọ̀ orí, àkúnlẹ̀yàn àti àkúnlẹ̀gbà àti ohun tí Yorùbá gbàgbọ́ nípa orí.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

- Ṣàlàyé ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ nípa orí

- Sọ ìtàn tí ó rọ mọ́ yíyan orí
- Sọ ìyàtọ̀ àti ìjọra tí ó wà láàárín àkúnlẹ̀yàn àti àkúnlẹ̀gbà

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

(1) Ṣàlàyé ohun tí Yorùbá ń pè ni orí

(2) Sọ díẹ̀ lára ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa orí

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Igbàgbọ́ Yorùbá Nípa Orí

## 4.2 Àkúnlẹ̀yàn, Àkúnlẹ̀gbà àti Orí

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ki ẹ̀dá ènìyàn tó wá sí ilé-ayé, yóó kọ́kọ́ dé àgbàlá Ìjàlámọ̀pín, láti yan orí, (Fálọlá, 2013:182), Ìjàlámọ̀pín ni àwọn mìíràn tún ń pè ní Àjàlá Alámọ̀ ti ń mọ orí. Ẹni tí ó bá dé ọ̀dọ̀ Àjàlámọ̀pín tí ó gbé orí tí ó wù ú, láìfi ti Àjàlá ṣe, ẹni náà ni ó yan ohun tí ó fẹ́, irú èyí ni àpẹẹrẹ àkúnlẹ̀yàn. Ẹni tí ó bá jẹ́ kí Ìjàlámọ̀pín gbé orí fún oun, irú ẹni yìí ni àpẹẹrẹ àkúnlẹ̀gbà. Irú èyí ni ó ṣẹlẹ̀ sí Oríṣẹ̀ẹ̀kú ọmọ Ògún, Orílèémèrè ọmọ Ìjà àti Àjùwàpẹ́ ọmọ Ọ̀rúnmìlà tí àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta jẹ́ ọ̀rẹ́ tímọ́tímọ́. Nígbà tí wọ́n ń ti ìkọ̀lẹ́ ọ̀run bọ̀ wá sí ìsálú ayé, wọ́n sọ fún wọn pé àwọn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta gbọ́dọ̀ lọ sí ọ̀dọ̀ Àjàlá wọn kò gbọdọ̀ yà sọ́tùn-ún tàbí sósì, ká má tíẹ̀ wá sọ pé wọ́n ya ibìkankan.

Bí wọ́n ṣe ń lọ, Oríṣẹ̀ẹ̀kú ọmọ Ogun gbọ́ pé baba rẹ̀ ń múra ogun, ó pinnu láti lọ ran bàbá rẹ̀ lọ́wọ́ láti jagun. Àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ rán an létí ìkìlọ̀ tí wọ́n ṣe fún wọn pé, wọn kò gbọdọ̀ yà sí ibìkankan. Ó gbọ́, kò sì lọ sí ọ̀dọ̀ bàbá rẹ̀ mọ́. Orílẹ̀émèrè pẹ̀lú gbọ́ pé bàbá rẹ̀ ń jà, òun náà fẹ́ lọ ran bàbá rẹ̀ lọ́wọ́. Wọ́n tún rán an létí ìkìlọ̀, òun náà kò lọ mọ́. Nígbà tí ó yá Àjùwàpẹ́, gbọ́ pé bàbá rẹ̀, Ọ̀rúnmìlà ń dífá, òun náà sì pinnu láti lọ bá bàbá rẹ̀, àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ náà tún rán an léti ìkìlọ̀, ṣùgbọ́n Àjùwàpẹ́ kọ etí dídí sí ìkìlọ̀, ó lọ sí ọ̀dọ̀ bàbá rẹ̀. Nígbà tí ó dé ibẹ̀ ó sọ ibi tí ó ń lọ fún bàbá rẹ̀ àti ìkìlọ̀ tí wọn sọ fún un. Ọ̀rúnmìlà ní kí ó rúbọ, kí ó wa ọ̀gọ̀ iyọ̀ mẹ́tà àti ẹgbẹ̀rún méjìlá owó ẹyọ lọ́nà mẹ́ta kí ó fi rúbọ, ó sì ṣe bẹ́ẹ̀. Wọ́n fún un lára iyọ̀ àti ẹgbẹ̀rún méjìlá owó ẹyọ láti mú dání lọ́nà ìrìnàjò rẹ̀.

Nígbà tí Àjùwàpẹ́ dé ọ̀dọ̀ àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀, kò bá wọn níbẹ̀ mọ́, ó sì tẹ̀síwájú lọ sí ọ̀dọ̀ Àjàlá. Oríṣẹ̀ẹ̀kú àti Orílèémèrè dé ọ̀dọ̀ Àjàlá, wọn ò bá Àjàlá nílé, wọ́n tọ́ka ibi tí àwọn orí tí Àjàlá ti mọ sílẹ̀ wà fún wọn. Lẹ́yìn tí wọ́n ti dúró fún ọjọ́ méjì, wọ́n kò lè ní sùúrù mọ́, wọ́n gbé orí tí wọ́n rò pé ó dára ní tiwọn, wọ́n sì bá tiwọn lọ.

Lójú ọ̀nà, nígbà tí wọn ń lọ, òjò líle bẹ̀rẹ̀ sí níí rọ̀, ó sì ń pa orí tí wọ́n gbé lọ́dọ̀ Àjàlá, orí yìí bẹ̀rẹ̀ sí ní í yìnrìn, nítorí òjò kò dá tí wọn fi dé ilé ayé, nígbà tí wọ́n dé ilé ayé orí tí wọ́n gbé ti fẹ́rẹ̀ẹ́ bàjẹ́ tán, nítorí orí tí wọ́n gbé kò dára tó. Nítorí náà, gbogbo ohun tí wọ́n ń dáwọ́ lé kò yọrí sí rere, wọ́n kò rí̀ṣe, bẹ́ẹ̀ ni wọ́n ń jìyà.

Àjùwàpẹ́ tó rúbọ nígbà tí ó ń lọ sí ilé Àjàlá, lójú ọ̀nà ìrìnàjò rẹ̀ ó dé ibi tí wọn ti ń sebẹ̀, ó fún wọn ní iyọ̀, ó dé ọ̀dọ̀ àwọn tí wọn ń fi abẹ́rẹ́ gúnyán, ó bá wọn gúnyán, wọ́n sì darí rẹ̀ sí ọ̀dọ̀ Àjàlá. Nígbà tí ó dé ilé Àjàlá, òun náà kò bá Àjàlá nílé, ó bá ẹni tí Àjàlá jẹ lówó, tí ó fẹ́ gba owó rẹ̀ dandan, Àjùwàpẹ́ sanwó tí Àjàlá jẹ fún olówó. Nígbà tí onígbèsè lọ tán, Àjàlá yọ́ kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ sọ kalẹ̀ láti orí àjà tí ó fi ara pamọ́ sí. Inú Àjàlá dùn sí Àjùwàpẹ́ tí ó bá a san gbèsè. Nítorí náà, ó fún Àjùwàpẹ́ ni orí tí ó dára. Òjò bẹ̀rẹ̀ sí ní rọ̀ nígbà tí òun náà ń bọ̀ wá sí ayé, òjò kò ba orí Àjùwàpẹ́ jẹ́. Nígbà tí ó dé ilé ayé ó là, ó lu, ó lówó lọ́wọ́ rẹpẹtẹ, gbogbo ohun tí ó ń dáwọ́ lé ló yọrí sí rere.

Àjùwàpẹ́ gba àkúnlẹ̀gbà, nígbà tí àwọn ọ̀rẹ́ rẹ̀ gba Àkúnlẹ̀yàn, nítorí fúnra wọn ni wọn gbé orí tí ó wù wọ́n. Àjùwàpẹ́ kúnlẹ̀ gba orí tirẹ̀ lọ́dọ̀ Àjàlá, ó sì jẹ́ orí rere.

.

## 4.3 Ìgbàgbọ́ Yorùbá nípa Orí

Àwọn Yorùbá ka orí sí púpọ̀, wọn sì gbàgbọ́ pé ohun yòówù tí ènìyàn lè fẹ́ dà, tàbí ṣe láyé, lọ́wọ́ orí ni. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pe “ohun gbogbo lọ́wọ́ orí”. Bí ayé ènìyàn bá dára, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé orí ni. Bí ayé ènìyàn bá sì tún kù díẹ̀ káàtó orí náà ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé kí a bi léèrè. Ìdí nìyí ti àwọn Yorùbá fi máa ń sọ pé orí làbá bọ, ká fòrìṣà sílẹ̀, orí ní gbeni, òòṣà kan kò leè gbèèyàn. Ìdòwú (1962:172) gbà pé ó yẹ kí a máa

bọ orí fún ìdí méjì pàtàkì. Àkọ́kọ́ ni pé orí ni alákòóso ara, àti gbogbo ohun tí ẹ̀dá ènìyàn jẹ́. Ìkejì ni pé, ti a bá bọ orí, a ó rí ìyọ́nú orí, orí yóó si gbé irúfẹ́ ẹni tí ó ń bọ ọ́.

Ọ̀kan pàtàkì nínú àwọn òrìṣà tí àwọn Yorùbá ń bọ ni orí jẹ́. Àwọn Yorùbá gba orí gẹ́gẹ́ bí Ẹlẹ́dàá tàbí ẹnìkejì wọn. Orí yìí kan náà ní wọ́n tún máa ń pè ni Àyànmọ́, kádàrá, ìpín, àkúnlẹ̀gbà tàbí àkúnlẹ̀yàn. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé oríṣìí orí méjì ló wà, èkínní ni orí inú nígbà tí èkejì jẹ́ orí ìta. Àwọn Yorùbá rí orí gẹ́gẹ́ bí alákòóso ara àti pé orí ni oríkèéríkèé ara yòókù so mọ́. Àwọn oníṣègùn òyìnbó náà gbà pé bí ẹ̀yà ara yòókù kò bá sí níbẹ̀ tí nǹkankan kò bá ti bá orí ènìyàn sì lè wà láàyè ṣùgbọ́n tí ìdágìrì bá ti bá orí gbogbo ẹ̀yà ara yòókù kò wúlò mọ́.

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé kò sí òrìṣà tí ó tó orí àti pé òun ló súnmọ́ ènìyàn ju gbogbo àwọn òrìṣà yòókù lọ. Ìdí nìyí tí ó fi jẹ́ pé gbogbo ohun tí àwọn Yorùbá bá ń fẹ́ ní ilé ayé wọn, wọ́n sábà máa ń bẹ orí wọn láti se è fún wọn. Àwọn Yorùbá gbà pé àwọn òrìṣà yòókù máa ń ran orí lọ́wọ́ ni. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pé “orí làbá bọ kí á fi òrìṣà sílẹ̀ nítorí orí ló lè gbeni òrìṣà kan kò lè gbeni”. Nínú odù ògúndá-méjì ẹsẹ kan sọ pé:

> Orí àtètèníran
> Àtètè gbéni kòòṣà
> kò sóòṣà tí í dáni í gbè
> Lẹ́yìn orí ẹni
> Orí ẹni ni í pé kó yẹni.

Ní ìgbà tí ìyàwó bá ń lọ sí ilé ọkọ ní ilẹ̀ Yorùbá wọ́n á ní “mórí lọ, má mẹ́wà lọ, orí ní báni gbélé ọkọ oòjọ́ lẹwà ń bọ̀”, wọ́n tún  máa ń sọ pé “orí la fi í mẹ́ran láwo, tí a kì í fi í méegun. Àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé orí lẹ́lẹ́jọ́ àti pé àtàrí lọlọ́ṣẹ àwúre, wọ́n tún máa ń

sọ pé kìlọ̀ forí inú rẹ kó má ba tòde jẹ́, gbogbo ìgbàgbọ́ Yorùbá wọ̀nyí ń fi pàtàkì orí hàn ni.

Àwọn olórin ní ilẹ̀ Yorùbá náà máa ń fi pàtàkì orí hàn nínú orin wọn. Díẹ̀ lára àwọn orin náà ni ìwọ̀nyí:

i. Orí mi o, Ẹ̀lẹ̀dáà mi ò/2ce
Má jẹ̀ n mòsì láyé o, orí mi o
Má jẹ̀ ń mọ̀yà láyé o, orí mi o.

ii. Ẹ gbéjẹ́ fórí o, ẹ gbéjẹ́ fórí
Orí ló mọlọ́là bó dọ̀la
Ẹ dákun ẹ ṣe pẹ̀lẹ́ o
Nítorí Ọ̀la, ẹ gbéjẹ́ fórí

iii. Orí mi má gbàgbé àdéhùn wa
Ẹ̀dá mi má gbàgbé àdéhùn wa /2ce

iv. Orí ló mọṣé àselà o
Àkọsílẹ̀ ọmọ ẹ̀dá ti dúró o
Béèyàn bá kàwé ogún
Béèyàn bá kàwé ọgbọ̀n
Tó bá fẹ́ ya oníranù
Kò dí i lọ́wọ́
Àkọsílẹ̀ ọmọ ẹ̀dá ti dúró o.

Nínú odù ògúndá méjì Ọ̀rúnmìlà pé gbogbo àwọn òrìṣà yòókù jọ, o bi wọ́n léèrè pé ta ni ó tó aláàásán bá ròkun? Ṣùgbọ́n ko sí èyí tí ó fihàn pé òun lè dúró tini di ìgbẹ̀yìn ayé ẹni nínú wọn àfi orí nìkan.

Bákan náà nínú odù Ọ̀yẹ̀kú méjì, a rí ìtàn babaláwo tó ṣe àìní ire gbogbo, ó sọ èrò ọkàn rẹ̀ fún Ọ̀rúnmìlà, Ọ̀rúnmìlà sọ fún un pé kó lọ sọ fún Èṣù, Èṣù ní kó lọ sọ fún akápò Ifá, akápò Ifá ní kí ó lọ bá orí rẹ̀ sọ ọ́, torí ọ̀rọ̀ tó ń dun akápò kò dun Ọ̀rúnmìlà àti èṣù ṣùgbọ́n orí ló ń dùn.

Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ohun tí ènìyàn bá dà làyé, ó wà lọ́wọ́ orí rẹ̀. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń sọ pé "Ẹni tí ó gbọ́n, orí ẹ̀ ló ní kó gbọ́n, ènìyàn tó gọ̀, orí rẹ̀ ló ní kó gọ̀ bí iṣu. Ènìyàn kò fẹ́ ká rẹrù ká sọ̀ orí ẹni ló ń sọ ni. Àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé ohun tí ènìyàn yóò jẹ́ wà lọ́wọ́ orí rẹ̀. Ẹlòmíràn yan orí rere ní ìgbà tí ẹlòmíràn yan orí ògúlùtu. Ẹlòmíràn yan ẹ̀mí gígùn ní ìgbà tí ẹlòmíràn yan ẹ̀mí kúkurú ní tirẹ̀. Nítorí náà, tí ẹnìkan bá kú lójijì tàbí ní rèwerèwe àwọn Yorùbá máa ń sọ pé àyànmọ́ irú ẹni bẹ́ẹ̀ ni torí pé a ti kúnlẹ̀ a yan ìpín a délé ayé tán, lojú ń kán gbogbo wa. Àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé "Ìṣẹ̀bọ ni ìṣòògùn, bí a ṣe wáyé páàrí làárí, a dífá fún Adékànḿbí tí i ṣe ọba ìlú Tẹlẹ́dàálàṣẹ, èyí tí orí rẹ̀ yóò burú títí, tí yóò pa bàbá rẹ̀ tí yóò fi ìyá rẹ̀ saya.

Odù ogbègúndá sọ fún wa pé láti Ọ̀run ni olùkúlùkù ti yan orí rẹ̀ wáyé ṣùgbọ́n ó yani lẹ́nu pé ní kété tí a tì kúrò ní ìsálú Ọ̀run tán ni a ti gbàgbé ohun tí a yàn. Ìdí nìyí tí a fi máa ń lọ sí ọ̀dọ̀ Barapetu láti lọ wo ohun tí a ó ò jẹ́ láyé nítorí òun la mọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹlẹ́rìí-ìpín. Kò sì sí ẹ̀sìn tí kò gbàgbọ́ pé àyànmọ́ wà.

## Àwọn Olùrànlọ́wọ́ Orí

Àwọn Yorùbà gbàgbọ́ pé orí ni àwọn olùrànlọ́wọ́ àti alábàáṣíṣẹ́pọ̀, àwọn yìí ni àwọn Yorùbá sì gbàgbọ̀ pé wọ́n lè yí orí burúkú padà sí rere tàbí ni ìdákejì ó le ṣe àkóbá

fún orí. Yorùbá gbàgbọ́ pé, àtúnṣe lè wà fún orí tí kò dára, gẹ́gẹ́ bí a ti rí i nínú ẹsẹ Ifá "Ọ̀yẹ̀kú Ìká" pé

Gúnnugún bá lórùlé
Ojú tólé, ojú tóko
Adíá fún ṣànìyàn
Tíí ṣẹ̀rú ìpín lọ́run
Wọ́n ní gbogbo wa
La ti yan ohun ta ó dà
Wọ́n ní, ṣùgbọ́n ohun tí á bá yàn
Tí ó bá dára
Ọ̀rúnmìlà nì ó máa bá wa
Fẹbọ gbé e sójú ọ̀nà.

**Ìwà**

Àwọn Yorùbá bọ̀ wọ́n ní "ká mú rágbá, ta rágbá ká mú ràgbà ta ràgbà, ìwà lójù. Èyí nìkan kọ́, wọ́n tún máa ń sọ pé ọ̀tọ̀ ni ìwà rere bẹ́ẹ̀ ni ọ̀tọ̀ sì ni ìwà búburú. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ bákan náà pé ìwà rere lẹ̀ṣọ́ ènìyàn. Wọ́n tún máa ń sọ pé ìwà rere ní í jẹ́ kí a rí ọmọ àdúgbò fẹ́. Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ìwà jẹ́ olùrànlọ́wọ́ pàtàkì fún orí àti pé bí ìwà rere ṣe lè tún orí burúkú ṣe, bẹ́ẹ̀ ni ìwà burúkú lè ba orí rere jẹ́. Nítorí náà, ìwà ẹnìkọ̀ọ̀kan tàbí ìdílé kọ̀ọ̀kan lè ba ohun tí ó dára jẹ́ tàbí kí ó tún ohun tí kò sunwọ̀n ṣe. Nítorí náà, ìwà ṣe pàtàkì nítorí pé ó ń ran orí lọ́wọ́ láti sọ ọ́ di rere tàbí búburú. Ẹni tí ó bá ni orí rere nígbà náà ní láti fi ìwà rere kún un.

**Ọ̀rẹ́**

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ọ̀rẹ́ jẹ́ pàtàkì fún orí. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń pòwe pé "ọ̀rẹ́ ẹni ní í bání pilẹ̀ ọlà, ara ilé ẹni ní í kó o. Ọ̀rẹ́ rere a máa fúnni ní ìmọ̀ràn àti ìtọ́ni tí ó lè fa ire báni, bẹ́ẹ̀ ni ọ̀rẹ́ burúkú lè sọ orí rere ẹlòmíràn di orí burúkú nítorí àgùntàn tí ó bá ajá rìn, yóò jẹ ìgbẹ́, Bíbélì pẹ̀lú tilẹ̀ sọ pé ẹgbẹ́ búburú a máa ba ìwà rere jẹ́.

**Ọwọ́**

Ọwọ́ náà jẹ́ ọ̀kan nínú àwọn olùrànlọ́wọ́ orí. Ìdí èyí ni àwọn Yorùbá fi máa ń sọ pé "àtẹ́lẹwọ́ ẹni kì í tanni jẹ". Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé bí orí bá dára tàbí tí ó sunwọ̀n ṣùgbọ́n tí ènìyàn jẹ́ alápá-má-ṣiṣẹ, irú ọwọ́ bẹ́ẹ̀ lè sọ orí rere ènìyàn di orí burúkú. Tí ọwọ́ bá dúró láti ran orí lọ́wọ́, bí irú orí bẹ́ẹ̀ bá tilẹ̀ burú ọwọ́ lè ràn án lọ́wọ́ láti ṣe àtúnṣe tí ó yẹ.

**Ẹsẹ̀**

Yorùbá bọ̀ wọ́n ní, "Ibi orí bá ń gbéni í rè kí ẹsẹ̀ má sàì sin ni lọ", àwọn Yorùbá tún máa ń sọ pé "kójú má ríbi ẹsẹ̀ loògùn rẹ̀. Nítorí náà, bi orí bá dára,  ẹsẹ̀ gbọdọ̀ máa sìn ín lọ sí ibi dáradára náà tí ó fẹ́ lọ, kí ó ba lè yege.

**Ẹbọ Rírú**

Ẹbọ rírú ṣe pàtàkì láti lè tún orí tí kò sunwọ̀n ṣe àti láti máa jẹ́ kí orí tí ó ti dára tẹ́lẹ̀ padà di burúkú. Nínú àpẹẹrẹ odù ogbègúndá, nígbà tí Orílèémèrè ọmọ Ìjà, Oríṣẹ̀ẹ́kú ọmọ Ògún àti Àjùwàpẹ́ ọmọ Ọ̀rúnmìlà lọ yan orí tí ó jẹ́ pé Àjùwàpẹ́ ọmọ Ọ̀rúnmìlà tí ó rú ẹbọ nìkan ló ní orí rere, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ẹbọ rírú lóòrè kóòrè le sọ orí burúkú di orí rere.

**Ẹnu**

Ẹnu náà jẹ́ olùrànlọ́wó pàtàkì fún orí. Èyí ló mú àwọn Yorùbá sọ pé àìlèsọ̀rọ̀ ni ìbẹ̀rẹ̀ orí burúkú, torí bí ènìyàn bá ní orí rere ṣùgbọ́n tí ó bá kú lẹ́nu orí rere ẹni bẹ́ẹ̀ lè di burúkú. Ẹlòmíràn sì lè sọ̀rọ̀ dáràn ní ìgbà mìíràn. Ọ̀rọ̀ rere ní í yọ obì lápò, ọ̀rọ̀ burúkú ní í yọ ọfà nínú apó.

**Àyà Níní**

Àwọn Yorùbá máa ń sọ pé àyà níní tó oògùn lọ́tọ̀, èyí túmọ̀ sí pé bí ènìyàn bá ní orí rere, ó tún gbọdọ̀ gbójú láti kojú àwọn alábàápàdé ilé ayé gbogbo. Nítorí náà, àyà níní jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn olùrànlọ́wọ́ orí ní ilẹ̀ Yorùbá.

**5.0 Ìsọníṣókí**

Nínú ìpín kẹta lábẹ́ módù kẹta yìí a ti kékọ̀ọ́ pe:

- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ki ẹ̀dá ènìyàn tó wá sí ilé-ayé, yóó kọ́kọ́ dé àgbàlá Ìjàlámọ̀pín, láti yan orí.
- Àwọn Yorùbá ka orí sí púpọ̀, wọn sì gbàgbọ́ pé ohun yòówù tí ènìyàn lè fẹ́ dà, tàbí ṣe láyé, lọ́wọ́ orí ni. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pe “ohun gbogbo lọ́wọ́ orí”
- Bí ayé ènìyàn bá dára, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé orí ni, bí ayé ènìyàn bá sì tún kù díẹ̀ káàtó, orí náà ni àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé kí a bi léèrè.
- Orí yìí kan náà ní wọ́n tún máa ń pè ni Àyànmọ́, kádàrá tàbí àkúnlẹ̀yàn.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé oríṣìí orí méjì ló wà, èkínní ni orí inú nígbà tí èkejì jẹ́ orí ìta.
- Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé kò sí òrìṣà tí ó tó orí àti pé òun ló súnmọ́ ènìyàn ju gbogbo àwọn òrìṣà yòókù lọ.

- Àwọn olórin ní ilẹ̀ Yorùbá náà máa ń fi pàtàkì orí hàn nínú orin wọn.
- Àwọn Yorùbà gbàgbọ́ pé orí ni àwọn olùrànlọ́wọ́ àti alábàáṣíṣẹ́pọ̀, àwọn yìí ni àwọn Yorùbá sì gbàgbọ̀ pé wọ́n lè yí orí burúkú padà sí rere tàbí ni ìdákejì, ó le ṣe àkóbá fún orí

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé ohùn ti Yorùbá gbàgbọ́ nípa orí
2. Jíròrò lórí àwọn olùrànlọ́wọ́ orí

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí


Abimbọla, W. 2015. *Àwọn ojú odu mẹ́rìndínlógún*. Ibadan. University Press Plc.

Balogun, O.A. 2007. The concepts of ori and Human Destiny in Traditional Yorùbá thought: A Soft-Deterministic interpretation Nordic.*Journal of African studies* 16.1 pp116-130.

Falola, T. 2013. Esu: Yorùbá God, power and the imaginative frontiers. North Carolina: Carolina Academic Press.

Ogúnadé, R.O. 2004. The Yorùbá concept of Orí in relation to Human Destiny. *An Encyclopedia of the Arts*. Vol. 10 (10). P127-134.

Idowu, B. 1962. *Olódùmarè: God in Yorùbá Belief.* Lagos. Longman Nigeria Ltd.

Ladele et al. 2006. *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjinlẹ̀ Àṣà Yorùbá. Ibadan*. Gavima Press Ltd.

Fẹmi-Amao O. 2015. The concept of fate in selected Yorùbá Novels. Unpublished M.A. Thesis, Ibadan. University of Ibadan.

Ọlálẹ́yẹ, S.K. 2014. Àkọsẹ̀jayé: Trend and status in Yorùbá communities of south western

Nigeria. Ilorin journal of religious studies.

## IPIN KẸRIN: ÈRÒ ÀWỌN YORÙBÁ NÍPA IKÚ

### Ìfáàrà

Nínú ìpín kẹrin yìí, a bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí ohun tí ikú jẹ́, a sì tún ṣàlàyé kíkún nipa èrò àwọn Yorùbá nípa ikú àti ìhà tí àwọn Yorùbá kọ sí ìsìnkú àti bí wọ́n ṣe ń palẹ̀ òkú mọ́ ní ilẹ̀ Yorùbá.

Àkóónú

1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

### 1.0 Ìfáàrà

Ìpín yìí bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí ohun tí ikú jẹ́, a tún wo èrò awọn Yorùbá nípa ikú, ìpínsísọ̀rí ikú àti bí a ṣe ń ṣe ìsìnkú ní ilẹ̀ Yorùbá.

### 2.0 Èròǹgbà àti àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóó lè:

Ṣàlàyé kíkún nípa ohun tí ikú jẹ́

Jíròrò lórí ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ikú

Sọ̀rọ̀ nípa ìsìnkú láàrin àwọn Yorùbá

**3.0 Ìbéèrè ìṣáájú**

1. Ṣàlàyé ohun tí ikú jẹ́
2. Ṣe àgbeyẹ̀wò èrò àwọn Yorùbá nípa ikú
3. Jíròrò lórí márùn-ún nínú àwọn oríṣìí ikú tí ó wà

4.0 Ìbẹ̀ẹ̀rẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́

**1. Èrò Àwọn Yorùbá Nípa Ikú**

Nǹkan ìbànújẹ́ ni ikú jẹ́ l'órílẹ̀ ayé. Àwọn Yorùbá bẹ̀rù ikú gidigidi. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń gba àdúrà pé kí àwọn máa fi ọjọ́ ọlọ́jọ́ lọ. Àṣà pàtàkì ni àṣà ìsìnkú jẹ́ láàrin àwọn Yorùbá, bí arúgbò kan bá sì gbó, tí ó tọ́, kí ó tó jáde l'áyé tí iná wọn tí ó kú fi eérú b'ojú, tí ọ̀gẹ̀dẹ̀ tí ó kú fọmọ rẹ̀ rọ́pò, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ó yẹ kí wọ́n ṣe ayẹyẹ pàtàkì fún irú òkú báyìí.

Oríṣìíríṣìí ni èrò àwọn Yorùbá nípa ikú:

- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé gbogbo ẹni tí a bí sí ilé ayé ni yóò kú. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń pòwe pé:

1. Gbèsè ni ikú, kò sí ẹni tí kò ní san án.
2. Àfọwọ́bà fi-sílẹ̀ ni ilé ayé.
3. Kò sí ẹni tí kò ní kú, kò sí ẹni tí oko bàbá rẹ̀ kò ní dígbòòrò.

- Àwọn Yorùbá rí ikú bí òrìṣà tí kì í gbọ́ ẹ̀bẹ̀ tí kò sì ní ojú àánú. Ènìyàn rere ló máa ń wù ú láti fi ṣe oúnjẹ. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi máa ń sọ pé:

  Ikú fi ìkà sílẹ̀

  Ẹni rere ló mú lọ

- Àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé ìgbà tí nǹkan bá ń dùn fún ọ̀pọ̀ ẹ̀dá ni ikú máa ń mú wọn lọ. Èyí ni wọ́n ṣe ń sọ pé:

  Ikú tí í fọ́lé adùn

  Ikú tí í fọ́lé oyin

- Èrò àwọn Yorùbá tún ni pé ọjọ́ orí kò ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ikú. Bẹ́ẹ̀ ni aájò tàbí òògùn kò ran ikú:

  Babaláwo á kú

  Oníṣègùn á rọ̀run

  Adáhunṣe kò ní gbẹ́yìn

- Èrò àwọn Yorùbá mìíràn tún ni pé ẹlẹ́sẹ̀ kò ní í lọ lájìyà àti pé ikú ènìyàn búburú kì í dára.

  Ikú asebi bí i kú ajá

  Ikú ìkà bí i ikú ìgalà

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ oríkì ni àwọn baba ńlá wa fún ikú torí wọn gbàgbọ́ pé ikú ní fọ ilé adùn.

Ikú níí pa babaláwo bi ẹni tí kò gbọ’fà
Ikú pa àlùfáà tí ó gbójú bi ẹni tí kò lỌ́lỌ́run ọba
Ikú ló pa Abírí tí Abiri fi kú

Ikú pa Abìrì, Abìrì re Ọ̀run alákeji
Ikú Àlùmúńtù
Ikú ọ̀gẹ̀gẹ́ ọlọ́nà
Agbapá l’ọ́wọ́ adáhunṣe
O sọ Babaláwo d’ọ̀gbẹ̀rì
Ìgbà tí ó bá fa lá-rìn-ká so lu’kọ
A pé kí túlu lọ bẹ ọ̀nà wò
À ní kí oníṣègùn
Lọ gba owó ìdá-oori-mú
L’ọ́wọ́ ọkùnrin

**2. Èro Yorùbá Nípa Ikú Gẹ́gẹ́ bí Òpin Ìrìnàjò Ẹ̀dá Láye Àti Ìpadà Sílé**

Èrò àwọn Yorùbá ni pé rírán tí Olódùmarè ran àwọn ẹ̀dá ènìyàn àti òrìṣà wá sí òde ìsálá ayé kò sọ pé kí wọ́n máa gbé ibẹ̀ títí láé ṣùgbọ́n láti ṣe iṣẹ́ pàtàkì tí Olódùmarè rán ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá fi máa ń sọ pé “ó ní ọjà tí a wá tà ní dúníyàn”. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá sì ni pé bí ó bá ti yá olúkálukú ni yóò padà sí ọ̀run tí a mọ̀ gẹ́gẹ́ bí ilé tí a ti wá láti lọ jábọ̀ fún ẹni tí ó rán wa níṣẹ́.

Àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé oníkálùkù ẹ̀dá ènìyàn ni ó kúnlẹ̀ níwájú Ẹlẹ́dàá tí ó sì yan ohun tí yóò ṣe tàbí jẹ́ nínú ayé. Ohun tí ó sì dájú ni pé bi ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan bá ti parí iṣẹ́ tí ó wáyé wá ṣe ni yóò lọ sọ́run láti jábọ̀ iṣẹ́ ìríjú rẹ̀ fún Olódùmarè, èyí kò sì yọ àwọn òrìṣà sílẹ̀. Àpẹẹrẹ èyí jẹyọ nínú odù ìwòrì méjì nínú ìtàn Ọ̀rúnmìlà nígbà tí ó fi ayé sílẹ̀, tí ó sì padà sí àjùlé ọrun. A tún máa ń gbọ́ pé, Ọya wọlẹ̀ nílé Irá, Ṣàngó wọlẹ̀ ní Kòso, Òrìṣà-oko wọlẹ̀ ní Ìràwọ̀-àgbà.

Àwọn ẹ̀sìn mẹ́tẹ̀ẹ̀ta ló fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ayé lọjà àti pé ọ̀run nílé gbogbo ẹ̀dá. Kò sí bí ènìyàn yóò ṣe dàgbà tó, yóò padà kú lọ́jọ́ kan ni. Èyí ni àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé "Ilé làbọ̀ sinmi oko?. Nínú Bíbélì àwọn ẹlẹ́sìn krístíẹ́nì, ìdágbére ti Jésù ṣe fún àwọn ọmọ ẹ̀yìn rẹ̀ nínú Johanu 14:1-3 ń fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ọ̀run nílé gbogbo wa. Àwọn ẹlẹ́sìn mùsùlùmí pẹ̀lú sọ pé ohun gbogbo ti a wá ṣe làyé ti wà nínú ìwé àkọsílẹ̀ kan tí a ń pè ní Um-ul-kitab, èyí fihàn pé gbogbo mùsùlùmí àti káfìrí ló ń padà lọ sí ọ̀run láti gba ìdájọ́ tí ó bá tọ́ sí olúkálùkù. Ìdí nìyí ti àwọn Yorùbá fi gbàgbọ́ pé bí ènìyàn lo ẹgbẹ̀rún ọdún láyé yóò padà sọ́run lọ́jọ́ kan, nítorí kò sẹ́ni ti kò ní kú, kò sẹ́ni tí oko baba rẹ̀ kò ní dìgbòòrò.

Oríṣìíríṣìí orin tí àwọn Yorùbá tún máa ń kọ ní àwùjọ yálà ní àsìkò ẹ̀sìn tàbí ìsìnkú tún n fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ sí i pé ikú jẹ́ òpin ìrìnàjò ẹ̀dá láyé àti ìrìnàjò sí ọ̀run tí wọ́n gbàgbọ́ pé ó jẹ́ ilé ẹ̀dá gbogbo. Fún àpẹẹrẹ:

i. Ilé ló lọ tàràrà
Bàbá relé o
Ilé lo lọ tarara

ii. À ti gbé baba rélé / 2ce
À ti gbé e é /2ce baba rele

iii. Jèrúsálẹmù tỌ̀run
Orin mi, ìlú
Ilé mi bí n bá kú
Ẹ̀kún ìbùkún mi
Ibi ayọ̀, ìgbà wo ni n o rojú rẹ
Ọlọ́run mi.

iv. Àtìpó ni a jẹ́ láyé

Àlejò nii wá ò e
Ọjọ́ kan ni baba yóò pè wá
Pé ọmọ máa bọ̀, ko wá sílé ò e /2ce

v. À ń sọ̀rọ̀ ilẹ̀ bùkún nì
Ilẹ̀ dídán àti ilẹ̀ ẹwà
Gbà gbogbo là ń sọ tògo rẹ̀
Yóò ti dùn tó láti dé ibẹ̀

Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa ẹni tí ó kú ni pé ó ń lọ bá àwọn bàbá rẹ̀ tí ó wà lọ́run ni àti pé àwọn bàbá yìí yóò ti pèsè àyè sílẹ̀ fún un. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń kí òkú àgbà pé "Bí o bá délé, kí o kílé, bí o bá dọ́nà, kí o kí èrò ọ̀nà, bí o bá dé ọ̀run ṣe ọ̀run ire, má jẹ ọ̀kùn, má jẹkòló, má bá wọn kọ́lé onímọ̀ lọ́run. Oríṣìíríṣìí ọ̀rọ̀ ìdágbére tí àwọn arúgbó máa ń sọ fún àwọn ọmọ wọn ní ìgbà ti wọ́n bá fẹ́ kú tún n fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ sí pé ọ̀run nilé gbogbo ènìyàn. Àwọn arúgbó yìí sábà máa ń sọ pé àwọn ti ń rí àwọn bàbá wọn àti pé kí àwọn ọmọ wọn tún ẹ̀yìn wọn ṣe.

Lọ́nà mìíràn ẹ̀wẹ̀, ọ̀pọ̀lọpọ̀ oúnjẹ tí àwọn ènìyàn máa ń sin pẹ̀lú oku pé ki ebi máṣe pa á lọ́na ìrìnàjò rẹ̀ túbọ̀ tán ìmọ́lẹ̀ sí i pé ayé lọjà, ọ̀run nilé, bákan náà ni oríṣìíríṣìí ẹ̀sọ́ ni wọ́n máa ń ṣe fún òkú bẹ́ẹ̀ ni wọn yóò fi ìpara olóòórùn dídùn kùn ún. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé ẹni tí ó lọ sí ìrìnàjò kò gbọdọ̀ rin ìrìn àbùkù lọ sí ilé rẹ̀ èyí tí ó ti fi sílẹ̀ ní ọjọ́ pípẹ́. Èyí fi ìgbàgbọ́ Yorùbá múlẹ̀ sí i pé ayé kì í ṣe àwáìlọ, ọ̀run nìkan ni àrèmabọ̀.

**3. Ìpínsísọ̀rí Ikú**

Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni ikú lè gbà pa ènìyàn, ẹlòmíràn a fọwọ́ rọrí kú, nípa títojú oorun dójú ikú. Bẹ́ẹ̀ ni ọ̀pọ̀ ń kú ikú oró tí wọ́n kò sì ni ojú oróórì, bí àpẹẹrẹ, ẹni tí ó kú nínú ìjàm̀bá mọ́tò tàbí ìjàm̀bá ọkọ òfurufu lè jóná ráúráú kí a má sì rí eérú rẹ̀. Bákan náà, ẹlòmíràn lè fi ẹsẹ̀ lásán kọ tí yóò sì tí ipasẹ̀ bẹ́ẹ̀ di èrò ọ̀run alákeji lójijì.  Bí ènìyàn bá ṣe kú àti àkókò tí ènìyàn bá kú ní yóò ṣe àfihàn bí a ó ti ṣe sin òkú rẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá. A kò lè sin òkú ọ̀dọ́ bí a ó ṣe sin òkú arúgbó. Ọ̀nà méjì pàtàkì ni a lè pín òkú sí ní ilẹ̀ Yorùbá. Òkú ẹkun/ìbànújẹ́ àti òkú ayọ̀. Òkú ìbànújẹ́ ni òkú èwe tàbí òkú ẹni tí ó fi òbí rẹ̀ sáyé lọ. Òkú ayọ̀ ni òkú arúgbó, pàápàá arúgbó ti ọmọ gbẹ̀yìn rẹ̀. Àdúrà tí àwọn Yorùbá máa ń gbà ni pé kí wọ́n gbẹ̀yìn arúgbó wọn, nítorí náà, ohun ayọ̀ gidigidi ni fún ẹni tí òbí rẹ̀ gbó tí ó sì fi sí ayé lọ. Irúfẹ́ ọmọ tí àwọn òbí fi ṣáyé yìí máa ń fi ìdùnnú rẹ̀ hàn pé òun gbẹ̀yìn òbí òun nípa pípe ẹbí, ọ̀rẹ́ àti ojúlùmọ̀ láti wá ṣe àjọyọ̀ pẹ̀lú rẹ̀, ọmọlóòkú yìí yóò sì pèsè jíjẹ àti mímú fún àwọn abániyọ̀ yìí lọ́pọ̀lọpọ̀.

**Òkú Ẹ̀kọ**

Òkú àgbàlagbà tí ó gbó, tí ó tọ́ ki ó tó kú ni a mọ̀ sí òkú ẹ̀kọ ní ilẹ̀ Yorùbá. Bí o tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ènìyàn kò le ṣe aláìsunkún bí ẹni wọn bá kú ṣùgbọ́n ẹkún ẹdun àgbéjókòó sun ni kì í ṣe ẹkún oró rárá, nitorí pé arúgbó ni ó kú.  Ní ìgbà tí arúgbó bá kú ni ilẹ̀ Yorùbá ẹkún tí àwọn ọmọ, ará, ọ̀rẹ́ àti ẹbí ń sun ni pé wọn ò tún lè ríra jọ gba ìmọ̀ràn mọ́ àti ti ìnáwó òkú tí ó délẹ̀, bí a bá yọ ìwọ̀nyí kúrò, ìsàlẹ̀ ọkàn àwọn tí arúgbó wọn bá kú máa ń kún fún ayọ̀. Ó tilẹ̀ jẹ́ àṣà àwọn Yorùbá láti máa kí ẹni ti òbí rẹ̀ kú pé “ó kú ewu, ó kú àsẹ̀yìndè, pé ó rẹ́yìn ọ̀táa rẹ̀”. Nítorí náà, ó jẹ́ àṣà pàtàkì ní ilẹ̀ Yorùbá ní ìgbà tí arúgbó bá kú láti fi ilé pọ́n ọtí fi ọ̀nà ro ọkà, fi agbada dín ẹran fún àwọn ọ̀rẹ́, àrà àti ẹbí wọn, láti dúpẹ́ pé wọ́n gbẹ̀yìn arúgbó wọn.

**Òkú-Inú**

Ọmọ ti a kò bí kí ó tó kú sínú ìyáa rẹ ni a mọ̀ sí òkú-inú. Àwọn Yorùbá tún máa ń pè é ni "ẹ̀jẹ̀ dídà" tàbí kí wọ́n sọ pé "ara kọjá mọ́ obìnrin lára". Ní ìgbà tí ìṣẹ̀lẹ̀ bí irú èyí bá wáyé àwọn Yorùbá a máa kẹ́dùn ṣùgbọ́n wọn kò ní sunkún. Nínú kíkí tí wọ́n bá ń ki ara wọn ni wọ́n ti máa ń fi ìbákẹ́dùn hàn, wọ́n á ní "Ẹ pẹ̀lẹ́ o, omi ló dànù, agbè kò fọ́". Èyí nìkan kọ́, wọ́n tún máa ń sọ pé: "Ọlọ́run á ṣe eléyìí tí ó dára". Bí obìnrin ti ẹ̀jẹ̀ dà lára rẹ̀ yìí bá ti gbélé fún bí ọjọ́ díẹ̀, tí ara rẹ̀ ba sì ti yá, yóò bẹ̀rẹ̀ sí jáde.

**Òkú-Ọmọ-Ọwọ́**

Bí ọmọ ọwọ́ tàbí ọmọdé bá kú ní ilẹ̀ Yorùbá, ìbànújẹ́ ńlá ni fún àwọn òbí rẹ̀, gbogbo àwọn ènìyàn ló sì máa ń ba àwọn irúfẹ́ òbí bẹ́ẹ̀ kẹdùn. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni àwọn Yorùbá máa ń gbà kí ẹni tí ọmọ rẹ̀ kú yìí, wọ́n á ní, "Ọlọ́run yóò fi èyí tí yóò bá wa gbé pààrọ̀" wọ́n tún lè sọ pé "Olódùmarè kò ní pè é lọ́wọ́ yín o, ní ìgbà mìíràn wọ́n tún lè sọ pé "àwọn yòókù á mọ́ ọn yín lọ́wọ́". Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé emèrè ọmọ ni ọmọ tí a bí, tí ó kú ní kékeré èyí lo fà á tí wọ́n fi ń sín òkú ọmọ ọwọ́ sí inú igbó pé kí ó lọ bá àwọn emèrè ẹgbẹ́ ẹ rẹ̀ gbé.

**Òkú Ọ̀dọ́**

Ikú wúndíá tàbí ọ̀dọ́mọkùnrin ni a mọ̀ sí òkú ọ̀fọ̀, òkú ìbànújẹ́ pátápátá ni, òkú ẹkún sì ni pẹ̀lú. Gbogbo àwọn ènìyàn òkú ni yóò máa sunkún àsungbéra sánlẹ̀, àwọn abánikẹ́dùn a sì máa pàrọwà fún àwọn ènìyàn òkú pé kí wọ́n ṣe sùúrù, kí wọ́n sì mú ọkàn le. Ọ̀ọ̀dẹ̀ ni wọ́n máa ń sin irúfẹ́ òkú báyìí sí ni ilẹ̀ Yorùbá. Ogójì ọjọ́ ni àwọn ẹbí òkú ọ̀fọ̀ fi máa ń gbélé ní ilẹ̀ Yorùbá.

**Òkú Omi**

Bí ènìyàn kan bá kú sínú omi, àwọn Yorùbá kì í gbé irúfẹ́ òkú bẹ́ẹ̀ wá sílé torí wọ́n gbàgbọ́ pé yóò fa àkúfà. Fún ìdí èyí, etí odò tí ó kú sí náà ni wọn yóò sin ín sí. Àwọn oníyemọja tàbí àwọn tó ń sin òrìṣà odò ni wọ́n máa ń pè láti wá báwọn ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ ètùtù fún ẹni tó kú sómí náà. Òkú ọ̀fọ̀ ni òkú ẹni tó kú sómi.

**Òkú Ẹni Tó Jábọ́**

Bí ènìyàn bá jábọ́ láti orí òkè tàbí igi ọ̀pẹ̀ tí ó sì kú, ìdí òkè tàbí igi yìí ni wọn yóò sin irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ si, kí ó má baà fa àkúfà. Òkú ọ̀fọ̀ náà ni òkú ẹni tó jábọ́ lórí òkè tàbí igi jẹ́ ni ilẹ̀ Yorùbá.

**Òkú Aboyún**

Ọ̀fọ̀ tí kò sunwọ̀n rárá ni ikú aboyún jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá. A kì í sin òkú aboyún sílé, inú igbó orò ni a máa sin-ín sí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ètùtù ni wọ́n ní láti ṣe, àwọn olórò ló sì gbọdọ̀ gbé òkú náà lọ sínú igbó lọ sin. Ìdí tí èyí fi rí bẹ́ẹ̀ ni pé wọn kò gbọdọ̀ sin òkú yìí pẹ̀lú ọlẹ̀ inú rẹ̀, inú igbó orò ni wọn yóò ti yanjú wọn sí ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Ìbànújẹ́ ńlá ni ikú aláboyún jẹ́ ni ilẹ̀ Yorùbá.

**Òkú Ẹni Tó Pokùn So**

Òkú ìbànújẹ́ ni òkú ẹni tó pokùn so jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá, orò ni o sì máa ń gbé òkú irúfẹ́ ẹni bẹ́ẹ̀ sin lẹ́yìn tí wọ́n bá ti tú u dáadáa.

**Òkú Ògún**

Ní ìgbà tí wọ́n bá sà ẹ̀nìkan pa tàbí yìnbọ pa ẹ̀nìkan ní ilẹ̀ Yorùbá ni a máa n sọ pé ó jẹ́ òkú ògún, àwọn ọdẹ tàbí àwọn olôgùn-ún ló máa ń sin irú òkú yìí lẹ́yìn ọ̀pọ̀lọpọ̀ ètùtù nítorí kí ó má baà yọ ẹni tí ó pa á lẹ́nu.

**Òkú Sànpọ̀nná**

Bí ìgbóná, olóde tàbí sànpọ̀nná bá kọlu ẹnìkan ní ilẹ̀ Yorùbá tí ó sì fi bẹ́ẹ̀ kú, a kò gbọdọ̀ ba ara jẹ́ tàbí sun ẹkún, àwọn ẹbí ẹni tí sànpọ̀nná pa yìí gbọdọ̀ máa yọ̀ ni ki inú má baà bí Ọbalúayé. Ìdí nìyí ti wọ́n ṣe máa ń pe Ọbalúayé ní òrìṣà alápadúpẹ́. Àwọn adósù òrìṣà yìí ló máa ń gbé òkú ẹni tó kú náà lọ si igbó orò tàbí òòṣà láti sin ín, gbogbo nǹkan ìní ẹni tí sànpọ̀nná pa ni wọ́n máa ń ko fún àwọn tó sin òkú rẹ̀, wọn kì í gbélé ọ̀fọ̀ ẹni tí sànpọ̀nná bá pa ní ilẹ̀ Yorùbá.

**Òkú Àgbà**

Òkú ijó, ayọ̀ àti oúnjẹ ni òkú àgbà jẹ́, ẹkún tí àwọn ènìyàn máa ń sun nígbà tí arúgbó bá kú jẹ́ ẹkún ẹ̀dùn àti ẹkún owó. Gbàrà tí arúgbó bá ti ku ni wọn yóò fi ọwọ́ rẹ̀ rọrí fún, èyí ni láti fihàn pé, ikú ìrọ̀rùn ni arúgbó náà kú.

**Ìtúfọ̀:** Ní ilẹ̀ Yorùbá ẹkun ni a fi máa ń túfọ̀ òkú. LẸ́yìn èyí ni wọn yóò gbé òkú si orí ìbùsùn tí wọn yóò sì fi aṣọ funfun bò ó. Gbogbo èrò to bá wá kí wọn pẹ̀lú ẹkún ni wọn yóò máa wọlé ṣùgbọ́n wọ́n kì í pẹ́ kí wọ́n tó sinmi irúfẹ́ ẹkún bẹ́ẹ̀. Bí ó bá jẹ́ pé ìletò ni òkú náà kú sí wọ́n ní láti ránṣẹ́ lọ sọ fún Baálẹ̀ tàbí Ọba kí wọ́n tó túfọ̀ fún gbogbo ará ìlú. Wọ́n ní láti fún ọba ní owó ìtúfọ̀ àti owó ìṣákọ́lẹ̀, èyí ni owó àṣẹ àti ìyọ̀ǹda láti gbẹ́ ìbojì nítorí àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé Ọba ló ni ilẹ̀.

**Adìẹ Ìrànà:** Èèwọ̀ ni ó jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá ki òkú sun ẹ̀yìn odi. Ìgbà tí wọ́n bá ń gbe òkú bọ̀ wá sílé ni wọ́n máa ń tu adìẹ ìrànà. Ẹnu odi ìlú ni wọn yóò ti da ẹ̀jẹ̀ adìẹ náà sílẹ̀ kí àwọn tó lọ gbe òkú tẹ̀ ẹ́ mọ́lẹ̀ wọ̀lú láti dènà rírú òkú mìíràn wá láti ẹ̀yìn odi, òkú tó kú sílé náà tún máa ń gba adìẹ ní ìgbà tí àwọn ọmọ òkú bá ń gbé pósí yípo ìlú ká ní ilẹ̀ Yorùbá.

**Ìbojì Gbígbẹ́:** Iṣẹ́ àna ni isà gbígbẹ́ jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá. Gbogbo àwọn àna pátápátá ni wọ́n máa ń gbẹ́ bojì, èyí tí kò bá wá gbẹ́ nínú rẹ̀ yóò san ọtí "Iwàlẹ̀" fún àwọn yòókù. Iṣẹ́ àṣe làágùn gidi ni ibojì gbígbẹ́. Fún ìdí èyí, oríṣìíṣìí ọtí àti oúnjẹ ni yóò máa rọ̀jò fún àwọn àna. Àwọn àna náà ló máa ń lọ ge igi ìròsùn tí wọ́n fi máa ń tẹ́ pẹpẹ lé òkú lẹ́yìn tí wọ́n bá gbé òkú sínú ibojì kí wọ́n tó wọ́ ìlẹ̀pa bò ó.

**Ìwẹ̀kú:** Ki a tó sin òkú ní ilẹ̀ Yorùbá, ó di dandan kí wọ́n wẹ̀ fún un ni ẹ̀yìnkùlé, lẹ́yìn tí wọ́n ti fá irun orí rẹ̀ ní àfádán. Ìwẹ̀ ìkẹ́yìn ni èyí jẹ́ fún òkú, wọ́n sì gbọdọ̀ farabalẹ̀ wẹ̀ ẹ́ dáadáa. Ọkùnrin ní í wẹ̀ òkú ọkùnrin ní ìgbà tí obìnrin sì ń wẹ òkú obìnrin ní ilẹ̀ Yorùbá.

**Ìtẹ́kùú:** Bí a bá ti wẹ òkú tán ni a ó fi aṣọ àlà dì í. Lẹ́yìn èyí oríṣìíríṣìí aṣọ ni wọ́n fi ń bo òkú. Bí àwọn ọmọ ṣe ń da aṣọ oríṣìíríṣìí bo òkú bẹ́ẹ̀ ni àwọn ẹbí náà yóò dáwó ra aṣọ láti fi bo òkú èyí ni wọ́n ń pè ní aṣọ ẹbí láyé àtijọ́. Èyí yàtọ̀ sí aṣọ ẹgbẹ́jọda tí a sọ di aṣọ ẹbí lóde òní. Gbọ̀ngàn ni wọ́n máa ń tẹ́ òkú sí níbi tí gbogbo ènìyàn ti lè rí i. Ìdí tí wọ́n fi ń tẹ́ òkú ni láti fi hàn àwọn ènìyàn pé ó fi ọwọ́ rọrí kú ni.

**Ìsìnkú:** Inú ibojì ti wọ́n ti tẹ ẹní àti oríṣìíríṣìí aṣọ si ni wọ́n máa ń gbé pósí tàbí òkú sí, wọ́n sì tún máa ń kó àwọn nǹkan ti ẹnu ń jẹ sínú bojì. Bákan náà ni wọn yóò fi ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹni pààpàrá bo igi ìròsùn náà kí wọ́n tó wọ́ erùpẹ̀ lé e. Dáwódù tàbí bẹ́ẹ̀rẹ̀ ilé ló kọ́kọ́ máa ń bu ìlẹ̀pa sí òkú, kí àwọn ọmọléyìn rẹ̀ náà tó ṣe bẹ́ẹ̀.

**Ìnáwó Òkú**: Sísin òkú lo ṣe pàtàkì jù nínú ètò ìsìnkú ní ilẹ̀ Yorùbá. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń sọ pé "Ẹni gbẹ́lẹ̀ ló pòkú mọ́, ẹni ń sunkún, ariwo lásán ló ń pa". Ní kete tí wọ́n bá ti sin òkú tán, ìnáwó òkú ló kan, ṣùgbọ́n bí kò bá sí agbára ìnáwó òkú, àwọn ọmọlóòkú lè so òkú rọ̀. Èyí ni pé kí wọ́n sún ìnáwó òkú sí ọjọ́ iwájú. Àwọn Yorùbá kórìíra àkú-ìsin, nítorí náà kí á gbé òkú rọ̀ kì í sábà ṣẹlẹ̀ láàrin wọn.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín kẹrin lábẹ́ módù kẹta yìí a ti kékọ̀ọ́ pe:

- Nǹkan ìbànújẹ́ ni ikú jẹ́ l'óríl ẹ̀ ayé. Àwọn Yorùbá bẹ̀rù ikú gidigidi, èyí ni wọ́n ṣe máa ń gba àdúrà pé kí àwọn máa fi ọjọ́ ọlọ́jọ́ lọ.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé gbogbo ẹni tí a bí sí ilé ayé ni yóò kú.
- Àwọn Yorùbá rí ikú bí òrìṣà tí kì í gbọ́ ẹ̀bẹ̀ tí kò sì ní ojú àánú.
- Àwọn Yorùbá tún gbàgbọ́ pé ìgbà tí nǹkan bá ń dùn fún ọ̀pọ̀ ẹ̀dá ni ikú máa ń mú wọn lọ. Èyí ni wọ́n ṣe ń sọ pé: Ikú ti fọ́lé adùn, Ikú ti fọ́lé oyin.
- Èrò àwọn Yorùbá tún ni pé ọjọ́ orí kò ní nǹkan ṣe pẹ̀lú ikú. Bẹ́ẹ̀ ni aájò tàbí òògùn kò ran ikú:
- Èrò àwọn Yorùbá ni pé rírán tí Olódùmarè ran àwọn ẹ̀dá ènìyàn àti òrìṣà wá sí òde ìsálayé kò sọ pé kí wọ́n máa gbé ibẹ̀ títí láé ṣùgbọ́n láti ṣe iṣẹ́ pàtàkì tí Olódùmarè rán ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn.
- Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá tún ni pé bi ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan bá ti parí iṣẹ́ tí ó wáyé wá ṣe ni yóò lọ sọ́run láti jábọ̀ iṣẹ́ ìríjú rẹ̀ fún Olódùmarè.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni ikú lè gbà pa ẹ̀dá ènìyàn.

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

1 Jíròrò lórí ikú gẹ́gẹ́ bí ipò ìsinmi

2 Ǹjẹ́ bí Yorùbá ṣe ń ṣe òkú àgbà ni wọ́n ń ṣe ti ọmọdé?

3 Irúfẹ́ àwọn ènìyàn wo ni Yorùbá gbà pé 'wọ́n wàjà àti pé kí ni ìdí rẹ̀?

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí

Adéoyè, C.L. 1979. *Asa Ati Ise Yoruba.* Ibadan: University Press Limited.

Johnson, S. 2001. *History of the Yorubas from the Earliest Times to the Beginning of the British Protectorate*. Lagos: CSS Limited.

Ìdòwú, E.B. 1963. *Olodumare: God in Yoruba Belief*. London: Longman.

**ÌPÍN KARÙN-ÚN: ÈRÒ ÀWỌN YORÙBÁ NÍPA ÀWỌN ỌBA ALAYÉ**

Nínú Módù yìí, a ó ṣàlàyé kíkún lórí èrò àwọn Yorùbá nípa àwọn ọba alayé ní ilẹ̀ Yorùbá. Akẹ́kọ̀ọ́ àti òǹkàwé yìí yóò ní ìmọ̀ tó yè kooro nípa irúfẹ́ ènìyàn tí àwọn Ọba alayẹ́ jẹ́, bi a ṣe ń j'Ọba àti ipò Ọba láàárín ìlú àti àwùjọ àti èrò àwọn Yorùbá nípa àwọn ọba alayé.

Àkóónú


1.0 Ìfáàrà

2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú

4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

4.1 Àwọn Ọba Alayé Ní Ilẹ̀ Yorùbá

4.2 Èrò Àwọn Yorùbá Nípa Àwọn Ọba Alaye

4.3 Bí a ṣe ń j'Ọba Ní Ilẹ̀ Yorùbá

5.0 Ìsọníṣókí

6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


## 1.0 Ìfáàrà

A bẹ̀rẹ̀ ìpín yìí pẹ̀lú àlàyé lórí àwọn ọba alayé ní ilẹ̀ Yorùbá. A wo irúfẹ́ ènìyàn tí àwọn ọba alayé jẹ́. Bí a ṣe ń jọba àti èrò àwọn ènìyàn nípa àwọn ọba aládé ní ilẹ̀ Yorùbá.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Ní òpin ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ àti àwọn òǹkàwé yìí yóò lè:

- Sọ̀rọ̀ nípa irúfẹ́ ènìyàn tí àwọn ọba alayé jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá
- Ṣàlayé nípa bí wọ́n ṣe ń j'ọba ní ilẹ̀ Yorùbá
- Sọ èrò àwọn Yorùbá nípa àwọn ọba alayé.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣáájú**

3.1 Ṣe àlàyé lẹ́kùn-ún rẹ́rẹ́ lórí ipò ọba alayé ní ilẹ̀ Yorùbá

3.2 Jíròrò nípa èrò àwọn Yorùbá nípa àwọn ọba alayé.

**4.0 Ìbẹ̀ẹ̀rẹ̀ Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**1. Àwọn Ọba Alayé Ní Ilẹ̀ Yorùbá**

Ní ilẹ̀ Yorùbá, Ọba ni olórí ìlú, àwọn sì ni wọ́n ń ṣàkóso ìlú. Ètò àlááfíà ìlú, gbígbé òfin kalẹ̀ àti ẹjọ́ dídá jẹ àwọn Ọba lógún. Àwọn Yorùbá sì tún gbàgbọ́ pé gbogbo ohun tí Ọba bá sọ ti di àṣẹ. Èyí ló fà á tí Yorùbá fi ń sọ pé ‘àṣẹ ni Ọba ń pa, Ọba kan kì í dábàá’. Wọ́n sì tún gbà pé Ọba ni aláṣẹ èkejì Òrìṣà nítorí pé yàtọ̀ sí àwọn Òrìṣa tí ó wà nílé ayé, Ọba ló tún ní àṣẹ láti darí ìlú, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé wọ́n máa ń ní àwọn Ìjòyè tí wọ́n jọ ń ṣèlú. Ọba gẹ́gẹ́ bí olórí ìlú ni ó ń ṣàkóso ìlú. Ọba ni ó sì ga jùlọ nínú àwọn aṣàkóso ní ilẹ̀ Yorùbá. A ní Ìjòyè, Olú àti Baálẹ̀ (ní àdúgbò, ìletò àti abúlé) ṣùgbọ́n Ọba ni ó ń ṣàkóso ìlú. Gbogbo ẹjọ́ tàbí aáwọ̀ tí àwọn tí a mẹ́nubà lókè yìí kò le dá tàbí parí, Ọba ni yóò parí rẹ̀. Ọba ni ó ń fi àwọn Ìjòyè tó kù jẹ ní gbogbo Ilẹ̀ Yorùbá.

Bí Ọba kan bá wàjà ní ilẹ̀ Yorùbá, ó di dandan kí Ọba mìíràn jẹ nítorí kò dára kí ìlú wà láìsí olórí. Ipò Ọba sì máa ń ṣí sílẹ̀ fún àwọn ọmọ ẹbí tí ó ń j’Ọba ní irúfẹ́ àsìkò yìí, àmọ́ èyí kò sọ pé ọmọ bàbá kan náà nìkan ni ó lẹ́tọ̀ọ́ láti j’Ọba. Àmọ́ kí a tó lè fi ẹnìkan j’Ọba, a gbọ́dọ̀ bi Ifá léèrè bóyá irú ẹni bẹ́ẹ̀ dára tàbí kò dára. Èyí nìkan kọ́, wọ́n tún gbọ́dọ̀ béèrè bọ́yá ìgbà ẹni náà yóò san tẹrú tọmọ tàbí òdì kejì rẹ̀.

## 2. Èrò Àwọn Yorùbá Nípa Àwọn Ọba Alayé

Ọba ni alásẹ̀ èkejì òrìṣà nínú ìgbàgbọ́ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí Olódùmarè ṣe jẹ́ alákòóso aye àti ọ̀run, bẹ́ẹ̀ gẹ́gẹ́ ni ọba jẹ́ alákòóso ìlú tàbí ìjọba rẹ̀ láyé níbí. Ọ̀wọ̀ ńlá tí ènìyàn ní sí Olódùmarè náa ni Yorùbá ní sí ọba. Kò sí ẹni tí ó láyà láti wo ọba alayé lójú ní ilẹ̀ Yorùbá àyàfi ẹni tí ó bá fé jẹ iyán rẹ̀ níṣu. Èyí ni wọ́n ṣe máa ń ki àwọn ọba alayé báyìí:

> Ọba tótó bí aró
> Ọba rẹ̀rẹ̀ bí osùn
> Ẹ̀rù ọba ni mo bà
> Ọba tótó ọba tótó

Ọ̀wọ̀ ńlá ni tọba ní ilẹ̀ Yorùbá. Bọ́mọdé rọ́ba, a wólẹ̀. Bágbà rí i, a ṣe bákan náà. Wọn a yíràá sọ́tùn-ún, àti sósì láti fi ìbọ̀wọ̀ wọn fún ọba hàn. Ọkùnrin tàbí ìjòyè kan kò láyà àtide fìlà kí ọba ní ilẹ̀ Yorùbá nitorí pé àwọn Yorùbá ri àwọn ọba alayé bí ìgbakejì Olódùmarè. Bí àwọn ọba alayé ṣe ni ẹ̀rù lára tó ní ilẹ̀ Yorùbá, wọn kì í jókòó gẹlẹtẹ tàbí gúnwà lórí ìlú pẹ̀lú ìkáwọ́jọ. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn ọba alayé ní àwọn ìjòyè wọn gẹ́gẹ́ bí ìsọ̀ǹgbè láti ràn wọ́n lọ́wọ́ nítorí àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé àjèjé ọwọ́ kan kò gbẹ́rù dórí, síbẹ̀ àwọn ọba ní ilẹ̀ Yorùbá ló ni kòkáárí ètò òṣèlú. Gbogbo ohun tí ọba bá fàṣẹ sí ni ṣíṣẹ. Ìdí nìyí tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé ohun ti ọba bá sọ abẹ ló gé e. Bí ọ̀rọ̀ ogun bá ṣẹlẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá, ọba ló gbọdọ̀ pàsẹ bóyá kí wọ́n lọ tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́. Èyí n àwọn Yorùbá fi máa ń sọ pé:

> Ọba níí sígun
> Ọba níí paná ogun

Bí ọ̀rọ̀ òfin bá délẹ̀, ọ̀dọ̀ ọba ni gbogbo rẹ̀ ń lọ. Ẹni bá rúfin, ọba ni yóò fi àṣẹ sí ìdájọ́ rẹ̀. Èyí tí ọba bá sọ ni abẹ gé. Apàṣẹ wàá ni ọba alayé jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá, àṣẹ rẹ̀ kò ṣe é yí padà àyàfi tí ọba bá fẹ́ ṣe bẹ́ẹ̀ fúnra rẹ̀. Bákan náa, àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé ìjíròrò lórí ìdàgbàsókè ìlú wà lọ́wọ́ ọba torí ọba ni yóò jíròrò lórí bí ìlú yóò ṣe dàgbà sókè. Bẹ́ẹ̀ ni bí ọ̀rọ̀ tó rújú bá délẹ̀, ọba ni yóò pé àwọn aláwo láti wá ṣe àyẹ̀wò láti lè mọ ọ̀nà àbáyọ. Lẹ́yìn àyẹ̀wò yìí, bí ètùtù ṣíṣe bá jẹyọ, ọba náà ni yóò fi àṣẹ sí ètùtù tàbí ẹbọ rírú náà.

Igbàgbọ́ àwọn Yorùbá mìíràn nípa ọba alayé ni pé gẹ́gẹ́ bí olórí ìlú, gbogbo ẹ̀sìn ìbílẹ̀ ni ó gbọdọ̀ máa ṣe. Bí ọdún Ifá, Ṣàngó tàbi Ògún bá délẹ̀, ọba gbọdọ̀ kó ipa tirẹ̀. Èyí túmọ̀ sí pé ó gbọdọ̀ sọ̀tún sòsì láì dá ibìkan sí, ọba alayé ni ilẹ̀ Yorùbá kò gbọdọ̀ yan ẹ̀sìn kan ni pọ̀sìn tàbí yan òmíràn fẹ́.

Èrò àwọn ènìyàn ní ilẹ̀ Yorùbá ni pé ọba ló nilẹ̀. Ẹ̀dá yòówù tí ó bá ni ohun kan láti ṣe gbọdọ̀ fi to ọba léti kí ó sì gbà àṣẹ ọba láti ṣe irúfẹ́ ohun bẹ́ẹ̀. Bí a bá wá rí ẹni tó ri ara rẹ̀ bí ẹni tí ó ṣe pàtàkì tí kò sì gbà àṣẹ lọ́dọ́ ọba tí ó fi ṣe ohun kan, ẹni bẹ́ẹ̀ yóò jìyà títẹ òfin ọba lójú.

Igbàgbọ́ àwọn Yorùbá nípa agbára ọba alayé tún fara hàn nínú àyọlò ìsàlẹ̀ yìí tí ó sọ pé:

Ọba ló nilẹ̀
Jọ̀wọ́ jẹ́ n rílẹ̀ tẹ̀

Èrò àwọn Yorùbá ni pé gbogbo ohun tí ó wà lórí ilẹ̀ ayé jẹ́ ti ọba alayé, èyí sì jẹyọ nínú ọ̀nà tí àwọn eléégún máa ń gbà júbà àwọn ọba alayé ní ilẹ̀ Yorùba:

Ẹ̀kúù mi,
Ẹ̀kú ọba
Agọ̀ọ̀ mi
Agọ̀ abọ̀rìṣà
Ọba ló ni mi tẹ̀kútẹ̀kú
Ọba ló ni mí tagbádá taṣọ
Tẹ̀wù òdòdó tí mo mú tẹ́lẹ̀ lógìdó

Bí ẹnìkan bá fẹ́ kọ́lé tàbí dáko ní ilẹ̀ Yorùbá láyé àtijọ́, ọwọ́ ọba ni yóò ti tọrọ ilẹ̀. Yóò rí olórí àdúgbò rẹ̀ bẹ́ẹ̀ ni ẹni tí ó dúró fún ọba òun ni yóò fún un ní àṣẹ àtilo ilẹ̀ náa. Gẹ́gẹ́ bí ọba, èro àwọn Yorùbá ni pé ohunkóhun tí ọbá bá ṣe, àṣegbé ni. Ní ilẹ̀ Yorùbá, bí ọba kan bá rí obìnrin tí ó wù ú, ó lágbára láti gbẹ́sẹ̀ lé irúfẹ́ obìnrin bẹ́ẹ̀ kí ó sì di aya rẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀. Ẹ̀bùn ọlọ́kanòjọ̀kan ní wọ́n máa ń mú wá fún ọba ni àkòkò ọdun láti ọ̀dọ̀ àwọn ọlọ́dún gbogbo. Àìmoye ènìyàn ni ó máa ń fún ọba lẹ́bùn ní ilẹ̀ Yorùbá lọ́nà àtidi ìríjú ọba.Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé agbára ọba kò láfiwé èyí ni wọn ṣe máa ń bẹ̀rù rẹ̀ tí wọ́n sì máa ń sa ipá wọn láti pese fún ọba, kí ìbínú rẹ̀ kí ó má baà ru si wọn. Àwọn ìgbèríko àti ìlú kékèèké tí ọba jọba lé lórí máa ń san ìṣákọ́lẹ̀ fún ọba láti ìgbà dé ìgbà kí ọba má baà kógun jà wọ́n, torí wọ́n gbàgbọ́ pé ìrọ̀rùn igi ni ìrọ̀rùn ẹyẹ.

### 3. Ọba Jíjẹ Ní Ilẹ̀ Yorùbá

Ní ilẹ̀ Yorùbá, Ọba jíjẹ kì í ṣe ohun yẹpẹrẹ rárá nítorí èyí kì í ṣe ìgbésẹ̀ tí ó máa ń wáyé ní ìgbà gbogbo. Bí Ọba kan kò bá kú, òmíràn kì í jẹ. Ohun tí èyí túmọ̀ sí ni pé lẹ́yìn tí Ọba kan bá wàjà ní ìlú tóó ní ẹ̀tọ́ láti fi òmíràn jẹ. Yàtọ̀ sí ìgbà tí Ọba kan bá wàjà, a tún ma ń fi Ọba jẹ nígbà tí Baálẹ̀ kan bá gba ìgbéga sí ipò Ọba, àmọ́ èyí kò wọ́pọ̀ láàárín àwùjọ. Ní ayé àtijọ́, àwọn afọbajẹ, ìjòyè àti àwọn aráàlú nìkan ni ó ní àṣẹ láti fi ènìyàn

kan j’Ọba, ṣùgbọ́n, ní òde òní, ìjọba gbọ́dọ̀ fi àṣẹ sí ẹni tí ìlú bá fà kalẹ̀, láìsí àṣẹ ìjọba, irú Ọba bẹ́ẹ̀ kò ní gba ọ̀pá-àṣẹ bí ó tilẹ̀ gba adé. Ọ̀nà mẹ́ta ni ètò Ọba jíjẹ ní ilẹ̀ Yorùbá pín sí:

- Ìgbésẹ̀ kínní ni fífi Ọba hàn: ìgbésẹ̀ yìí níí ṣe pẹ̀lú fífi ẹni tí ìlú àti Ifá mú hàn fún tẹrú tọmọ fún ọjọ́ méje tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ.
- Ìgbésẹ̀ kejì ni mímú ọba wọ ìpèbí: lẹ́yìn tí àwọn ènìyàn bá ti mọ ẹni tí ó fẹ́ j’Ọba, àwọn afọbajẹ àti àwọn Ìjòyè yóò fi Ọba náà pamọ́ sí ìpèbí tí ó le wà lẹ́yìn odi tàbí ibi tí ó pamọ́. Ìdí tí a fi ń ṣe èyí ni láti kọ́ Ọba ní àwọn ohun tí ó yẹ, láti ró wọn ní agbára àti láti wúre fún Ọba náà. Àwọn kan tún gbàgbọ́ pé Ọba tuntun náà yóò jẹ ọkàn Ọba àná (Ọba tí ó wàjà). Bí Ọba náà bá ṣe ń jẹ ọkàn náà, wọn yóò máa bi í pé “kí ni ò ń jẹ?” Ọba náà yóò si máa dáhùn pé “mò ń jẹ Ọba”. Ìgbésẹ̀ yìí gan-an ni wọ́n gbà ní Ọba jíjẹ.
- Ìgbésẹ̀ kẹta ni dídá Ọba padà sí àárín ìlú àti Ìgbadé Ọba: Lẹ́yìn tí Ọba bá jáde ní ìpèbí ni àwọn Afọbajẹ yóò gbé adé ìṣẹ̀nbáyé lé Ọba náà lórí. Èyí jẹ́ àkọsílẹ̀ ṣókí bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èyí yàtọ̀ láti ìlú sí ìlú.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìpín karùn-ún lábẹ́ módù kẹta yìí a ti kékọ̀ọ́ pe:

- Ní ilẹ̀ Yorùbá, Ọba ni olórí ìlú, àwọn sì ni wọ́n ń ṣàkóso ìlú.
- Ètò àlááfíà ìlú, gbígbé òfin kalẹ̀ àti ẹjọ́ dídá jẹ àwọn Ọba lógún.
- Àwọn Yorùbá gbàgbọ́ pé gbogbo ohun tí Ọba bá sọ ti di àṣẹ, èyí ló fà á tí Yorùbá fi ń sọ pé ‘àṣẹ ni Ọba ń pa, Ọba kan kì í dábàá’.
- Àwọn Yorùbá gbà pé Ọba ni aláṣẹ èkejì Òrìṣà nítorí pé yàtọ̀ sí àwọn Òrìṣa tí ó wà nílé ayé, Ọba ló tún ní àṣẹ láti darí ìlú.
- Ọba ni ó sì ga jùlọ nínú àwọn aṣàkóso ní ilẹ̀ Yorùbá.

- Gbogbo ẹjọ́ àti aáwọ̀ ni Ọba máa ńyóò parí rẹ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá.
- Ọba ni ó ń fi àwọn Ìjòyè tó kù jẹ ní gbogbo Ilẹ̀ Yorùbá.
- Gẹ́gẹ́ bí ọba, èro àwọn Yorùbá ni pé ohunkóhun tí ọbá bá ṣe, àṣegbé ni.
- Ní ilẹ̀ Yorùbá, Ọba jíjẹ kì í ṣe ohun yẹpẹrẹ rárá torí èyí kì í ṣe ìgbésẹ̀ tí ó máa ń wáyé ní ìgbà gbogbo.
- Yàtọ̀ sí ìgbà tí Ọba kan bá wàjà, a tún ma ń fi Ọba jẹ nígbà tí Baálẹ̀ kan bá gba ìgbéga sí ipò Ọba.
- Ọ̀nà mẹ́ta ni ètò Ọba jíjẹ ní ilẹ̀ Yorùbá pín sí

## 6.0 Iṣẹ́ ṣíṣe

1. Ṣàlàyé ipò tí àwọn Ọba alayé wà láwùjọ.
2. Ṣàlàyé ṣókí lórí ìsọ yìí 'mo j'Ọba'.
3. Walẹ̀jìn lórí ìgbésẹ̀ Ọba jíjẹ ní ilẹ̀ Yorùbá.

## 7.0 Ìwé ìtọ́kasí

Adébáyọ, A. 2012. *An Intergrative notion of Punishment in Traditional Yorùbá Culture*. Ph.D Thesis. Department of Philosophy. University of Ìbàdàn, Ìbàdàn, Nigeria.

Adéoyè, C.L. 1979. *Àṣà Àti Ìṣe Yorùbá*. Ibadan: University Press Limited.

Ìdòwú, E.B. 1963. *Olódùmarè: God in Yorùbá Belief*. London: Longman.

Johnson, S. 2001. *History of the Yorubas from the Earliest Times to the Beginning of the British Protectorate*. Lagos: CSS Limited.